**COURSE GUIDE**

**YOR 113**

# INTRODUCTION TO THE HISTORY OF THE YORÙBÁ PEOPLE (Ìfáárà sí Ìtàn Ìṣẹ̀dálẹ̀ Àwọn Yorùbá)


**Course Team:**

OLÚBÁYỌ̀ ỌLÁDIMÉJÌ ADÉKỌ́LÁ (Course writer)-B.A Hons. (Ifẹ), M.A. Ph.D Ìbàdàn
Prof. Arinpe G. Adejumọ (Course Editor)-
Institute of African Studies, University of Ibadan, Ibadan, Nigeria.


**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA**

© 2018 by NOUN Press
National Open University of Nigeria
Headquarters
University Village
Plot 91, Cadastral Zone
Nnamdi Azikiwe Expressway
Jabi, Abuja

Lagos Office
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island, Lagos

e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

All rights reserved. No part of this book may be reproduced, in any form or by any means, without permission in writing from the publisher.

Printed 2018, 2023

ISBN: 978-978-058-884-7

## CONTENTS PAGE

Introduction.......................................................................... iv
Course Aim........................................................................... iv
Course Objectives................................................................ iv
Working through this Course............................................... iv
Course Materials………………………………………... iv
Study Units........................................................................... v
Textbooks and References………………………………… v
Assessment……………………………………………….... vi
Assignment Files.................................................................. vi
Tutor-Marked Assignment……………………………….... vi
Final Examination and Grading …………………………… vi
Course Marking Scheme………………………………….... vii
Course Marking Scheme…………………………………… vii
How to Get the Best from this Course…………………….. vii
Facilitators/Tutors and Tutorials……………………………. ix
Summary …………………………………………………... ix

## ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ

Módù Kìnní: Ìṣẹ̀dálẹ̀ Àwọn Ìran Yorùbá
Ìpín Kìnní
Àwọn Yorùbá àti Orírun Wọn
Ìtàn Àtẹnudẹ́nu Kìnní Nípa Orírun Yorùbá
Ìtàn Atẹnudénu kejì Nípa Orírun Yorùbá
Àkọsílẹ̀ àwọn òǹkọ̀wé Òde-Òní Nípa Orírun Yorùbá
Àrídìmú Nípa Orírun Àwọn Yorùbá

Ìpín Kejì
Àwọn Ọmọ Odùduwà
Ìtànkálẹ̀ Àwọn Ọmọ Odùduwà
Àwọn Ẹ̀yà Yorùbá
Ọ̀yọ́, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú
Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì àti Oǹdó

Ìpín Kẹta
Èdè Yorùbá
Èdè Yorùbá àti Àwọn Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Mìíràn
Ìyàtọ̀ Èdè àti Àwọn Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Mìíràn
Kíkọ Èdè Yorùbá sílẹ̀
Oríkì àti Ìwúlò rẹ̀ ní àwùjọ Yorùbá

Ìpín Kẹrin
Èrò Yorùbá Nípa Àwọn Ẹ̀mí Àìrí
Èrò Yorùbá Nípa Owó
Èrò Yorùbá Nípa Ọmọ
Èrò Yorùbá Nípa Àìkú tàbí Àtubọ̀tán Ayé
Èrò Yorùbá Nípa Ikú àti Ìyè lẹ́yìn Ikú

Ìpín Karùn-ún
Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Olódùmarè
Ìgbàgbọ́ Nípa Ìṣẹ̀dá Ayé àti Ọ̀run
Ìgbàgbọ́ Nípa Orí àti Àyànmọ́
Ìgbàgbọ́ Nípa Ẹgbẹ́ Awo àti ìmùlẹ̀
Ìgbàgbọ́ Nípa Àwọn Aláṣekù àti Ìbọ

**MÓDÙ KEJÌ**

Ìpín Kìnní: Àṣà Àti Ọdún Ìbílẹ̀ Yorùbá
Kín ni àṣà?
Àṣà Ìkíni
Àṣà Ìwọṣọ
Àṣà Oge Ṣíṣe
Àṣà Ilà Kíkọ

Ìpín Kejì: Àwọn Ẹ̀ka Àṣà Yorùbá 2
Àṣà Ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́
Ogún pínpín
Ìsìnkú àti òkú Ṣíṣe
Ìgbéyàwó
Ìsọmọlóruúkọ

Ìpín Kẹta: Àwọn Òrìṣà Yorùbá
Òrìṣà-ńlá tàbí Ọbàtálá
Ọ̀rúnmìlà
Èṣù
Ṣàngó
Ògún

Ìpín Kẹrin: Ọdún Ìbílẹ̀ Yorùbá
Ọdún Egúngún
Ọdún Agẹmọ
Ọdún Ifá
Ọdún Òkèbàdàn
Ọdún Òrìṣà-Oko

Ìpín Karùn-ún: Àṣà Ilẹ̀ Níní àti Lílò Láàrin Àwọn Yorùbá
Ilẹ̀ Níní Láwùjọ Àwọn Yorùbá
Ilẹ̀ Lílò Láàrin Àwọn Yorùbá
Ọfọ̀ Ilẹ̀ Láàrin Àwọn Yorùbá
Ilẹ̀ Gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá
Rògbòdìyàn Ilẹ̀ Láyé Àtijọ́ àti Lóde Òní

**MÓDÙ KẸTA:**

Ìpín Kìnní: Ètò Ìjọba Ìbílẹ̀ Yorùbá Láyé Àtijọ́
Ètò Ìdílé Nínú Ìṣèjọba Ìbílẹ̀ Yorùbá Láyé Àtijọ́
Fífi Ọba àti Ìjòyè Jẹ Ní Ilẹ̀ Yorùbá Láyé Àtijọ́
Fífa Ọmọ Oyè sílẹ̀
Ìwádìí lọ́wọ́ Ifá
Ètùtù fún ọmọ Oyè tí Ifá bá mú
Ìfinijoyè Ìdílé tàbí Oyè Ìlú

Ìpín Kejì
Iṣẹ́ Àgbẹ̀
Ìṣẹ́ Ọdẹ

Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ-Ògún
Iṣẹ́ Aṣọ Híhun
Iṣẹ́ Epo Fífọ̀

Ìpín Kẹta
Iṣẹ́ Ohùn Pípè
Iṣẹ́ Ìṣègùn
Iṣẹ́ Arọ́ Dídá
Iṣẹ́ Iṣẹ́ Ìkòkò Mímọ
Iṣẹ́ Ọsẹ Dúdú

Ìpín Kẹrin: Ìlù, Orin àti Ijó Láàrin Àwọn Yorùbá
Ìwúlò Ìlù àti Orin
Àgbe ṣíṣe ni Ìdílé Aláyàn
Àwọn Ìlù tí a ń lù
Ohun tí a ń fi ìlù wí
Ibi tí Àwọn Ìlù yìí ti wá

Ìpín karùn-ún: Eré Ìdárayá Ní Ilẹ̀ Yorùbá Lọ́jọ́ Ọjọ́un
Ayò Ọlọ́pọ́n
Eré Àrín
Ẹkẹ tàbí Ìjàkadì
Èré Òkòtó Títa
Eré Òṣùpá

**Ìfáàrà Sí Kọ́ọ̀sì Yìí**

A pín kọ́ọ̀sì yìí sí Módùlù mẹ́ta, bẹ́ẹ̀ ni a pín módùlù kọ̀ọ̀kan sí ìpín márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.
Nínú módùlù kìnní, ìpín kìnní ni a ti wo ìṣẹ̀dálẹ̀ àwọn ìran Yorùbá. A wo orírun wọn àti àwọn ìtàn àtẹnudétí tí a gbọ́ nípa wọn, bẹ́ẹ̀ ni a wo àkọsílẹ̀ àwọn òpìtàn òde-òní nípa àwọn ènìyàn yìí, tí a sì rí àwọn nǹkan kan dì mú nípa ìgbé-ayé wọn láti ìgbàdégbà.
Nínú ìpín kejì módùlù kìnní yìí kan náà ni a ti mẹ́nuba àwọn ọmọ Odùduwà àti ìtànkálẹ̀ wọn. A wo àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́¸Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú bẹ́ẹ̀ ni a kò sàì ṣàlàyé nípa àwọn ẹ̀yà Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì àti Oǹdó nínú ìpín yìí.
Nínú ìpín kẹta módùlù kìnní yìí ni a tún ti ṣe àgbéyẹ̀wò èdè Yorùbá tí a sì wo àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mìíràn tí a kò le kà sí èdè sísọ. À tọpinpin àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ yìí, a sì wo ìyàtọ̀ wọn sí èdè. A tún wò ní ṣókí àwọn ìlànà tí a gbà kọ èdè Yorùbá sílẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni a wo oríkì àti ìwúlò rẹ̀ ní àwùjọ Yorùbá.
Ní ìpín kẹrin módùlù yìí ni a ti sọ̀rọ̀ èrò Yorùbá nípa àwọn ẹ̀mí àìrí, owó, ọmọ àìkúléwe tàbí àtubọ̀tán ayé. Èrò Yorùbá nípa ikú àti ìyè lẹ́yìn ikú ni a fi ka ́ ìpín yìí nílẹ̀.
Ní ìpín karùn-ún tí ó parí módùlù yìí ni a ti wo ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá Nípa Olódùmarè, ìṣẹ̀dá ayé àti ọ̀run, bẹ́ẹ̀ ni a tún mẹ́nuba ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn yìí nípa ẹgbẹ́ awo àti ẹgbẹ́ ìmùlẹ̀. Ní ìparí ìpín yìí ni a ti wo ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa àwọn Aláṣekù àti Ìbọ.
Ní módùlù kejì ẹ̀wẹ̀, a wo àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá pàtàkì kan ní ìpín kìnní àti èkejì. Lára àwọn ẹ̀ka àṣà yìí ni ìkíni, ìwọṣọ, oge ṣíṣe àti ilà kíkọ. Àwọn mìíràn ni àṣà ìran-ra-ẹni-lọ́wọ́, ogún pínpín, ìsìnkú àti òku ṣíṣe, bẹ́ẹ̀ ni a wo àṣà ìgbéyàwó àti ìsọmọlórúkọ.
Ní ìpín kẹta ẹ̀wẹ̀, a sọ̀rọ̀ lórí àṣà ilẹ̀ níní àti lílò láàrin àwọn Yorùbá láyé àtijọ́, a wo orúkọ agbègbè kan àti ìtumọ̀ wọn. A tẹ̀ síwájú nípa wíwo àṣà ẹjẹ́ jíjẹ́ àti ìbúra, bẹ́ẹ̀ ni a wò ó bí àwọn Yorùbá ṣe ń tọ́jú oyún àti ọmọ àti pàápàá jù lọ, bí a ṣe ń kọ́ ọmọ ní ẹ̀kọ́ ilé láti kékeré.
Ìpín kẹrin, módùlù kejì yìí ni ó sọ̀rọ̀ lórí àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá bíi Ọ̀rúnmìlà, Ṣàngó, Ọbàtálá, Ṣànpọ̀nná, Ògún àti Èṣù.
Ìpín karùn-ún ṣàlàyé lórí àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá pẹ̀lú àpẹẹrẹ ọdún egúngún, Agẹmọ ní ilẹ̀ Ìjẹ̀bú, ọdún Òkè-bàdàn ní ìlú Ìbàdàn àti ọdún Òrìṣà-Oko ní ìlú Ìràwọ̀. Níbí ni a ti ṣàlàyé àwọn ìdí tí a fi ń ṣe àwọn ọdún yìí títí di àkókò yìí.
Ní módùlù kẹta tí ó jẹ́ èyí tí ó gbẹ̀yìn, ìpín kìnní rẹ̀ sọ̀rọ̀ lórí ètò ìdílé nínú ìṣèjọba ìbílẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́. A tẹ̀síwájú nípa ìwádìí àti ètùtù tí ó máa ń wáyé kí wọ́n tó gbé ọba sórí ìtẹ́, bẹ́ẹ̀ ni a mẹ́nuba ìfinijoyè tí ó máa ń wáyé láàrin ìdílé tàbí oyè ìlú.
Ìpín kejì nínú módùlù yìí sọ̀rọ̀ lórí àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá kan bí iṣẹ́ arọ́, aró dídá, epo fífọ̀ àti aṣọ híhun nígbà tí ìpín kẹta tẹ̀sísíwájú láti wo iṣẹ́ ohùn pípè, iṣẹ́ ìṣègùn, iṣẹ́ ìkòkò mímọ àti iṣẹ́.
Ìpín kẹrin ni ó sọ̀rọ̀ nípa ìlù, orin àti ijó láàrin àwọn Yorùbá pẹ̀lú àlàyé lórí agbe ṣíṣe ní ìdílé àwọn àyàn, àwọn ìlù tí wọ́n máa ń lù àti ohun tí wọ́n máa ń fi ìlù sọ, bẹ́ẹ̀ a sọ̀rọ̀ lórí ibi tí àwọn ìlù yìí tí hù wá.
Nínú ìpín karùn-ún ni a ti sọ̀rọ̀ nípa eré ìdárayá láàrin àwọn Yorùbá láyé àtijọ́. Àwọn eré pàtàkì tí a mẹ́nubà ní eré ayò ọlọ́pọ́n, eré àrín, ẹkẹ tàbí ìjàkadì bẹ́ẹ̀ ni a sọ̀rọ̀ lórí eré òkòtò títa àti àwọn irúfẹ́ eré òṣùpá tí àwọn ọ̀dọ́mọdé máa ń ṣe.

## ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Àfojúsùn Kọ́ọ̀sì yìí ni láti rí i pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọ̀nyí mọ ìtàn tí ó jẹ mọ́ ìsẹ̀dáẹ̀ àwọn baba-ńlá Yorùbá. Èyí ni yóò le jẹ́ kí wọ́n lè sọ̀rọ̀ ní àwùjọ àwọn onímọ̀ níbikíbi tí wọ́n bá bá ara wọn lọ́jọ́ iwájú.
Èyí nìkan kọ́, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le ní ìmọ̀ kíkún nípa bí àwọn baba-ńlá Yorùbá ṣe ń tẹsíwájú nínú ètò idṣèlú àti ìbára-ẹnigbépọ̀ ti àlàáfíà ṣe ń jọba láàrin wọn.
Àwọn akékọ̀ọ́ yóò le mọ pàtàkì èdè àti bí Yorùbá ṣe níyì tó ní àwùjọ àgbáyé gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rí tí a lè mú lónìí. A tún fẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ àwọn ìyàtọ̀ pẹ́ẹ́ pẹ̀ pé tí ó wà nínú èdè àdúgbò kọ̀ọ̀kan láàrin àwọn Yorùbá
Wọn yóò mọ̀ nípa bí àwọn baba-ńlá waṣ e mú ìdàgbàsókè bá èdè Yorùbá títí di òní olónìí. Akẹ́kọ̀ọ́ yóò le mọ èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àidrí gbogbo, pàápàá ní àkókò tí a wà yìí.

## OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́

Bí olùkọ́ ṣe ní ojúṣe tirẹ̀ láti fi yé akẹ́kọ̀ọ́ yékéyéké, kí wọ́n sì ní ìmọ̀ tí ó péye lórí ìṣẹ̀dálẹ̀ àwọn baba-ńlá Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ fi ara balẹ̀ láti gba ìmọ̀ kún ìmọ̀ lọ́dọ̀ àwọn aṣaájú wọn nínú ìmọ̀ ìtàn, àṣà, ìsèṣe, èdè Yorùbá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ múra láti ka àwọn ìwé tí olùkọ́ tóka sí nínú ìwé ilé-ìwé ìléwọ́ yìí àti pé wọ́n ní láti máa wá ìdáhùn sí gbogbo àwọn ìbéèrè tí a gbé síwájú wọn. Akẹ́kọ̀ọ́ kò gbọdọ̀ ṣe ọ̀lẹ nínú akitiyan rẹ̀ láti ní ìtẹsíwájú nínú ìmọ̀ ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá pàápàá ní àkókò ọ̀làjú tí a wà yìí.
Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ fi ara balẹ̀ láti gbọ́ ìtọ́sọ́nà àwọn olùkọ́ rẹ̀ kí o lè ṣe kóríyá nínú ẹ̀kọ́ rẹ̀. Akẹ́kọ̀ọ́ kò gbọdọ̀ jalè iòmọ̀ ẹlòmíràn tàbí jí iṣẹ́ oníṣẹ́ wò tàbí kí ó da iṣẹ́ oníṣẹ́ kọ.
Ojúṣe mìíràn ní pé akẹ́kọ̀ọ́ ni láti wá àwọn ìwé tí wọ́n kọ fún un, kí ó sì kà wọn dáadáa. Bí kò bá le fi owó rẹ̀ rà wọ́n, kí ó máa lọ sí ilé ìyáwèé kàwé tí ó ti le rí àwọn ìwé wọ̀nyí kà.
Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ máa dá iṣẹ́ àmúrelé tàbí iṣẹ́ aìmúṣe rẹ̀ padà ní àkókò tí ó yẹ, bẹ́ẹ̀ ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ fi ara hàn ní àsìkò ìdánwò àṣekágbá láìṣe àwáwí kankan.
Ní ìparí, kí akẹ́kọ̀ọ́ máa bèèrè àwọn ìbéèrè tí kò yé e nípa bíbá olùkọ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀.

## ÌGBÉLÉWỌ̀N TÍ OLÙKỌ́ YÓÒ MÁÀKÌ (TMA)

Ọ̀nà ìgbéléwọ̀n kínní ni iṣẹ́ ṣíṣe tí olùkọ́ yóò fi ọwọ́ sí, nígbà tí ọ̀nà kejì yóò jẹ́ iddánwò alákọsílẹ̀. Àwọn ọ̀nà méjèèjì yìí dá lórí iṣẹ́ àmúṣe tí yóò jẹ́ dídájọ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ èyí tí yóò sì ní ìpinnu lórí àsìkò tí akẹ́kọ̀ọ́ yóò dá iṣẹ́ náà padà fún olùkọ́ rẹ̀. Iṣẹ́ àmúrelé yìí yóò kó idá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rtùn-ún máàkì, ní ìrètí pé ìmọ̀ akékọ̀ọ́ yóò wúò fún un nínú iṣẹ́ aìmúṣe àti ìdánwò fún aṣeyege rẹ̀.
Iṣẹ́ ṣíṣe wà ní ìparí ìpín kọ̀ọ̀kan, bẹ́ẹ̀ ni a ní ìrètí pé akẹ́kọ̀ọ́ yóò wá ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè tí ó wà níbẹ̀. A ò yẹ àwọn iṣẹ́ ṣíṣe yìí wò, bẹ́ẹ̀ ni a ó fún akẹ́kọ̀ọ́ ní máàkì fún ìdáhùn sí ìbéèrè mẹ́ta. Yóò jẹ́ ẹyọ kan ní Módù kan – módù kìnní dá lórí ìṣẹ̀dálẹ̀. Àwọn Ìran Yorùbá, èkejì Ìlórí Àṣà àti ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá, nígbà tí ẹ̀kẹta dá lórí 'Etò Ìjọba Ìbílẹ̀ Yorùbá Láyé Àtijọ́, Iṣẹ́ ìṣẹ̀nbáyé Yorùbá, ìlù, orin àti ijó pẹ̀lú Eré Ìdárayá láàrikn Àwọn Yorùbá.
Iṣẹ́ ṣíṣe àti ìgbéléwọ̀n yìí ni akẹ́kọ̀ọ́ yóò fi papọ̀ sí olùkọ́ kí ọjọ́ ìdánwò tó pé., wàyí o, bí ìdí kan pàtàkì bá wà fún akẹ́kọ̀ọ́ láti má dá iṣẹ́ náà padà saájú ọjọ́ tí a

fún un, irú akẹ́kọ̀ọ́ bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ fi ìdí yìí tó olùkọ́ rẹ̀ létí, tí olùkọ́ yìí yóò sì piunnu àtisún ọjọ́ ìdápadé náà síwájú.

## ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ ÀTI ÒSÙNWỌ̀N MÁÀKÌ

Ìdánwò àṣekágbá fún kọ́ọ̀sì yìí yóò wáyé ní ọjọ́ tí àwọn aláṣẹ ilé-ẹ̀kọ́ àti olùkọ́ bá fiẹ nu kò sí, èyí tí yóò sì jẹ jáde nínú àtẹ ìdánwò.
Láàrin wákàtí méjì ni akẹ́kọ̀ọ́ yóò dáhùn ìbéèrè tí a bá gbé síwájú rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni ọgọ́ta máàkì ni a ó si fi ṣe òdiwọ̀n rẹ̀.
Akẹ́kọ̀ọ́ tí kò bá ní í lè wà nínú ìdánwò yìí fún ìdí pàtàkì kan tàbí òmíràn ní láti fi ẹ̀rí tí ó gbámúṣé hàn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn aláṣẹ Ilé-èkọ́ ni yóò pinnu ohun amúṣe lórí rẹ̀.

## ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ

Máàkì gbígbà nínú iṣẹ́ àmúṣe yóò dá lórí bí akẹ́kọ̀ọ́ ṣe dángájiá sí nínú iṣẹ́ tí a fun un láti ṣe gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àmúrelé.
Atẹ̀ ìsàlẹ̀ yìí ń ṣe òdiwọ̀n máàkì gbígbà nínú kọ́ọ̀sí yìí. Bí àpẹẹrẹ

| **Ìgbéléwọ̀n** | **Máàkì** |
|---|---|
| Iṣẹ́ àmúṣe 1-3<br>A ó mú iṣẹ́ mẹ́ta tí ó bá dára jù láti fi ṣe àkọsílẹ̀ máàkì ti akẹ́kọ̀ọ́ gbà | Ogójì (40%) |
| Ìdánwò àṣekágbá | Ọgọ́ta (60%) |
| Àròpọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%) |

## MÓDÙ KÍNNÍ

### 1.0 Ìfáàrà:

Nínú Módù yìí a ó ti gbọ́ àlàyé orísun àti orírun àwọn ìran Yorùbá. Akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yìí yóò ní òye kíkún nípa ìsẹ̀dálẹ̀ àwọn Yorùbá láti inú àwọn ìtàn àtẹnudẹ́tí tí a máa ń gbọ́ lẹ́nu àwọn baba-ńlá wọn àti àwọn òpìtàn òde-òní.
A ó wo orírun àwọn ìran Yorùbá àti bí wọ́n ṣe tàn káàkiri gbogbo àgbáyé, lẹ́yìn èyí ni a ó wo àwọn ẹ̀yà tí àwọn Yorùbá pín sí àti ibi tí wọ́n tagbò dé ní apá ìhà Gúúsù Ìwọ̀-Oòrùn ilẹ̀ àwọn Ènìyàn Dúdú ni Afíríkà àti ni gbogbo àgbáyé. Síwájú sí i, níbí yìí ni a ó ti ṣe àlàyé ọ̀nà tí ìran àwọn Yorùbá pín sí, tí a ó sì ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan àti ibi tí wọ́n tẹ̀dó sí.
Ní ìparí, a ṣe àlàyé àwọn ìjọra àti ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ tí ó wà láàrin àwọn ẹ̀yà yìí.

## ÌPÍN KÍNNÍ: Àwọn Yorùbá Àti Orírun Wọn

### Àkóónú:

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àwọn Yorùbá àti orírun wọn
4.2 Ìtàn Àtẹnudétí kìnní nípa orírun Yorùbá
4.3 Ìtàn Àtẹnudétí kejì nípa orírun Yorùbá
4.4 Àkọsílẹ̀ àwọn onìtàn òde òní nípa orírun Yorùbá
4.5 Àrídìmú nípa orírun Àwọn Yorùbá
5.0 Àgbálọgbábọ̀
6.0 Ìsọnísókí
7.0 Iṣẹ́ Síṣe
8.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà:

Ìpín yìí bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àlàyé lórí àwọn ohun tí a gbọ́ láti inú ìtàn àtẹnudétí àti àkọsílẹ̀ àwọn ònpìtàn òde òní lórí ibi tí ìran Yorùbá ti sẹ̀. A wo àwọn oríṣìíríṣìí ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ èyí láti le ní ìdánilójú nípa ìṣẹ̀dálẹ̀ àwọn ìran yìí, kí a lè ní àrídìmú tí ó dájú nípa wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìtàn wọ̀nyí yàtọ̀ díẹ̀díẹ̀, a rí i pé wọ́n ń ní ìbáṣepọ̀ díẹ̀díẹ̀ pẹ̀lú.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Nígbà tí a bá parí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó mọ:

- níní ìdánilójú nípa ìṣẹ̀dálẹ̀ ìran Yorùbá
- ibi tí àwọn Yorùbá ti sẹ̀ wá
- bí ìran Yorùbá ṣe ń dàgbà sí i nínú ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye.

## 3.0 Ìbéèrè ìsáájú :

1. Kọ ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá kan tí o mọ̀ sílẹ̀
2. Ṣe àlàyé kíkún lórí Odùduwà àti àwọn ọmọ rẹ̀

## 4.0 Ìbéèrè Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Àwọn ìran Yorùbá àti Orírun wọn:

Onírúurú ìtàn àtẹnudẹ́tí la gbọ́ lẹ́nu àwọn baba-ńlá tàbí àwọn tí wọ́n ṣe Yorùbá sílẹ̀ lórí ibi tí ìran yìí ti sàn wá bí odò. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn òpìtàn àti àwọn olùwádìí láàrin àwọn Yorùbá tún fi yé wa ìgbà tí àwọn Yorùbá ti dé sí agbègbè tí wọ́n wà lónìí yìí.

## 4.2 Ìtàn Àtẹnudẹ́tí Kìnní Nípa Orírun Yorùbá

Ìtàn àtẹnudẹ́tí kìnní ṣe àlàyé pé láti orílẹ̀-èdè Mọ́kà (Mecca) ni àwọn baba-ńlá Yorùbá ti wá tẹ̀dó sí agbègbè ibi tí wọ́n wà lónìí yìí. Níbí yìí ni a ti gbọ́ pé Odùduwà tí a pè ní baba-ńlá àwọn ìran Yorùbá ti gbéraṣọ, tí ó bínú fi ilú Mọ́kà sílẹ̀. Àwọn mìíràn sọ pé Odùduwà ṣe èyí nígbà tí èdè-àìyedè kan bẹ́ sílẹ̀ nítorí ìjà oyè jíjẹ, bẹ́ẹ̀ ni àwọn kan sọ pé Odùduwà kọ̀ láti tẹ̀ lé ẹ̀sìn mùsùlùmí tí àwọn baba rẹ̀ ń ṣe ni. Nítorí náà, òun àti àwọn tí ó gba tirẹ̀ fi ìlú Mẹ́kà sílẹ̀, wọ́n sì wá ìhà Gúúsù Ifẹ̀-Oòdáyé Ìwọ-Oòrun ilẹ̀ Afíríkà, wọn sì tẹ̀dó sí agbègbè kan tí a mọ̀ sí Ifẹ̀ Oòdáyé níbí tí a gbọ́ pé wọ́n bá àwọn ẹ̀dá ènìyàn kan níbẹ̀, wọ́n gba agbára lọ́wọ́ wọ́n, wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe àkòso ibẹ̀.

## 4.3 Ìtàn Àtẹnudẹ́tí kejì Nípa Orírun Yorùbá

Ìtàn ìgbà ìwáṣẹ̀ mìíràn tí ó jẹ mọ́ ìgbàgbọ́ àti ẹ̀sìn Yorùbá fi yé wa pé, nígbà tí Olódùmarè kọ́kọ́ sẹ̀dá ayé àti ọ̀run ni ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, Olódùmare àwọn irúnmọlẹ̀ ọ̀kànlénírinwó (401) irúnmọlẹ̀ tí a tún mọ̀ sí òrìṣà. Lára àwọn òrìṣà yìí ni Ọbàtálá wà, èyí tí Ẹlẹ́dàá sọ fún pé kí ó lọ dá ìyàngbẹ ilẹ̀ nítorí pé kìkì alagbalúgbú omi ni ayé wà nígbà náà. Ọlọ́run fún Òrìṣà-ńlá tí a tún máa ń pè ní Ọbàtálá ní adìẹ ọlọ́mọ ìka ẹsẹ̀ márùn-ún àti ẹrùpẹ̀ tí ó kún inú ilé ìsáná kan, bẹ́ẹ̀ ni Olódùmarè sọ fún Òrìṣà-ńlá pé kí ó da ẹrùpẹ̀ náà sí ojú omi, kí ó sì fi adìẹ náà sílẹ̀ láti tàn án ká. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ọbàtálá kò dé ibi tí ó ń lọ tí ó fi mu ẹmu yó lójú ọ̀nà, tí ó sì sùn lọ, a rán Odùduwà láti lo ṣe iṣẹ́ náà àti pé ibi tí a ti ṣe ìtànka erùpẹ̀ yìí, tí ó sì di ìyàngbẹ ilẹ̀ ni a ń pè ni Ifẹ̀-Oòdáyé. Nínú ìtàn yìí, a gbọ́ pé lẹ́yìn tí a dá Ifẹ̀-Oòdáyé, Olódùmarè rán àwọn ọ̀kanlénú (401) òrìṣà wọ̀nyí láti rọ̀ wà sí òde ayé láti ìsàlú ọ̀run lọ́hùn-ún, Ó sì fún òrìṣà kọ̀ọ̀kan ní iṣẹ́ àti ipa tí yóò kó láti mú kí ayé wà ní àlàáfíà. Lára àwọn òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀ yìí ni a ti rí Òrìṣà-ńlá tàbí Ọbàtálá, Ọ̀rúnmìlà, Èṣù Ẹlẹ́gbárá, Sànpọ̀nná, Yemọja, Olókùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nípa báyìí, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Ilé-Ifẹ̀ ni ayé ti bẹ̀rẹ̀ àti pé láti ibí ni gbogbo ẹ̀dá ènìyàn ti tàn káàkiri àgbáyé.

## 4.4 Àkọsílẹ̀ Àwọn Òǹkọ̀tàn Òde-Òní nípa Orírun Yorùbá

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a ti gbọ́ ọ̀kan-ò-jọ̀kan àlàyé ni a tún máa ń gbọ́ tí a sì tún máa ń kà lẹ́nu àti nínú àkọsílẹ̀ àwọn òǹpìtàn òdeòní.

Gẹ́gẹ́ bí èrò onímọ̀ ìtàn Adéagbo Akínjọgbin (1996) àwọn mìíràn sọ pé Yorùbá kò wá láti Mọ́kà bí kò ṣe láti agbègbè ibi kan lẹ́yìn ìpàdépọ̀ odò Ọya àti Benue tí wọ́n sì wá sí ìhà Gúúsù Ìwọ̀ Oòrùn Ilẹ̀ Adúláwọ̀. Wọ́n sọ fún wa pé àṣà, èdè àti ìrísí àwọn Yorùbá jọ ti àwọn olùgbé odò ọya àti Benue.

## 4.5 Arídìmú Nípa Orírun Àwọn Yorùbá

Bí a bá wo àwọn ìtàn àtẹnudétí àti ti àkọsílẹ̀ àwọn òǹpìtàn Yorùbá, a ó rí i pé àwọn tí a ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ìran Yorùbá gbà pé Ilé-Ifẹ̀ ni orírun wọn àti pé ibi yìí ni gbogbo àwọn Yorùbá máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bi ibi tí ayé ti bẹ̀rẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Bí a bá tún kíyèsí àwọn ìtàn àtẹnudétí òkè yìí a ó rí i pé gbogbo ìran Yorùbá ni wọ́n gbà pé Odùduwà ni baba-ńlá wọn. Ìbáà ṣe Mọ́kà ni Odùduwà ti wá sí Ifẹ̀ Oòdáyé tàbí ó wà láti ìsàlú ọ̀run, ó hàn gbangba pé Odùdùwà ní ó tẹ̀ wọ́n dó sí ilé-Ifẹ̀.

## 5.0 Ìsọnísókí

O ti gbọ́ àlàyé nípa àwọn ibi tí àwọn Yorùbá ti lè ṣè wá. Onírúurú ìtàn ni a ti gbọ́ nípa àwọn ènìyàn yìí, bẹ́ẹ̀ ni àwọn akọlù ìtàn àtẹnudétí wọ̀nyí kò sàì mú kí á mọ bí Yorùbá ṣe wáyé. A gbọ́ pé láti ilẹ̀ àwọn Lárúbááwá, pàápàá ní ìlú Mọ́kà ni Odùduwà ti gbérasọ kí ó tó dúró ní agbègbè tí a pè ní Ifẹ̀-Oòdáyé, èyí tí a ń pè ní Ilé-Ifẹ̀ lónìí.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kín ní àwọn ìjọra àti àtẹnudétí wo ló tọ́ka sí orírun Yorùbá?
2. Kín ní àwọn ìjọra àti ìyàtọ̀ tí a le tọ́ka sí nínú àwọn ìtàn tí ó ṣàlàyé orírun Yorùbá?
3. Ṣàlàyé ipò tí Ilé-Ifẹ̀ wà láàrin àwọn Yorùbá

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Johnson 1921. *History of the Yorùbás from the Earliest Times to the Beginning of the Protestorate.* Lagos: C.M.S.

Àtànda, J.A. 1996. "The Yorùbá people: Their origin, Culture and Civilization" *in Odunjọ J.F. Memorial Lecture Series 5,* Ibadan, I.U.P.

Fadipe, N.A. 1970 *The Sociology of the Yorùbá,* Ibadan, I.U.P.

Eluyemi, O. *This is Ile-Ife,* Ile Ife, Adesanmi Printing Press.

Akinjọgbin, I.A. 1996. 'The Growth of Yoruba studies in the Western Region of Nigeria 1955-1965" in O.O. Ọlatunji (ed.) *The Yoruba History, culture and Language.* J.F. Ọdunjọ Memorial Lecture series 5, Ibadan, I.U.P.

## MÓDÙ KÍNNÍ

## ÌPÍN KEJÌ: ÀWỌN ỌMỌ ODÙDUWÀ ÀTI ÌTÀNKÁLẸ̀ WỌN

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
(1) Àwọn ìran wo ni a mọ̀ sí ọmọ Odùduwà?
(2) Ṣàlàyé sókí lórí àwọn ẹ̀yà tí àwọn Yorùbá pín sí.
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àwọn Ọmọ Odùduwà
4.2 Ìtànkálẹ̀ àwọn ọmọ Odùduwà
4.3 Àwọn Ẹ̀yà Yorùbá
4.4 Ọ̀yọ́, Ẹ̀gbá àti Ìjẹ̀bú
4.5 Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì àti Oǹdó
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà:

Bí a bá ń sọ nípa àwọn ọmọ Odùduwà níbí, a wo àwọn tí a ń pè ni ọmọ Odùduwà yìí lọ́nà kan tàbí òmíràn. Lọ́nà kìnní, àwọn ọmọ Yorùbá kọ̀ọ̀kan, bẹ́ẹ̀ ni a ó wo àwọn ti Odùduwà bí fúnra rẹ̀.
Níbí yìí ni a ó ti mọ iye ojúlówó ọmọ àti ọmọ-ọmọ tí Odùduwà bí àti ipa tí wọ́n kó nínú ìtànkálẹ̀ ìran Yorùbá. A ó wo àwọn ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan tí Yorùbá pín sí. Bí àpẹẹrẹ, Ọ̀yọ́, Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú, Ìjẹ̀sà, Èkìtì àti Òǹdó.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó lè:
- mọ̀ nípa àwọn ìran tí a ń pè ní Yorùbá
- mọ̀ bí ẹ̀yà Yorùbá kọ̀ọ̀kan ṣe fọ́nká sórí ilẹ̀ Yorùbá lóde òní.
- fi ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan hànde ní agbègbè tí wọ́n tẹ̀dó sí
- mọ bí ìbáṣepọ̀ ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ṣe ṣe gúnmọ́ tó.

### 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.0 Àwọn Ọmọ Odùduwà:

Gbogbo àwọn ìran Yorùbá ni a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ọmọ Odùduwà níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé Odùduwà ni wọ́n gbà gẹ́gẹ́ bí baba-ńlá wọn tí ó sè wọ́n sílẹ̀ ní ìlú Ifẹ̀-Oòdáyé tí a mọ̀ sí Ilé-Ifẹ̀ lónìí. Bí a bá wò orúkọ tí a ń tọ́ka sí yìí, èyí ni Odùduwà, ó ní ìtumọ̀ kan tí àwọn òpìtàn sọ pé a ní láti fi ìtumọ̀ rẹ̀ hàn. Àwọn mìíràn túmọ̀ Odùduwà sí 'Odù tí ó dá ìwà' tàbí 'Odù tí ó dá wà'.
Nínú ẹ̀sìn àti ìgbàgbọ́ Yorùbá, a máa ń rí 'Odù' nínú ẹsẹ Ifá, èyí tí ó túmọ̀ sí 'orí' nítorí náà, a lè sọ pé Odùduwà túmọ̀ sí 'orí' tí ó dá ìwàláàyè ìran Yorùbá

sílẹ̀. A tún lè sọ pé èyí túmọ̀ sí 'orí' tí ó dúró gedegbe tàbí 'orí' tí ó tayọ láàrin àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀
Èyí ó wù kí á túmọ̀ rẹ̀ sí, a ó rí i pé Odùduwà tayọ láàrin ẹbí àti ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ ní Mọ́kà tí ìtàn àtẹnudétí náà ti wá.

## 4.1 Àwọn Ọmọ Odùduwà àti Ìtànkálẹ̀ Wọn:

A gbó ọ nínú ìtàn àtẹnudétí mìíràn pé Odùduwà bí ọmọ kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Ọ̀kànbí àti pé Ọ̀kànbí yìí ni ọmọ kan náà tí Odùduwà bí ṣùgbọ́n Ọ̀kànbí ni tirẹ̀ bí ọmọ méje. Ìtàn yìí tẹ̀síwájú pé àwọn ọmọ-ọmọ Odùduwà wọ̀nyí ni wọn fi Ifẹ̀-Oòdáyé sílẹ̀, tí wọ́n sì jáde lọ kúrò ní Ifẹ̀ láti lọ gba ilẹ̀, kí wọ́n sì tẹ ìlú dó fúnra wọn. Báyìí ni a máa ń gbọ́ Onísabẹ ti Sabẹ, Alákétu ti Kétu, Onípópó ti Pópó, Ọ̀ràngún ti Ìlá, Olówu ti ìlú Òwu, Aláàfin ti Ọ̀yọ́ àti Ọba ti ìlú Bìní. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọba tí a dárúkọ wọ̀nyí sì wà lónìí, a tún rí àwọn ẹ̀yà mìíràn tí wọ́n dá dúró láti agbàgbè kan sí èkejì. Nínú wọn ni Ọ̀yọ́, Ẹ̀gbà, Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì, Ìjẹ̀bú àti Oǹdó. A ó máa wo àwọn wọ̀nyí ní sísẹ̀-n-tẹ̀lé.

## 4.2 Ẹ̀yà Ọ̀yọ́ Ẹ̀gbá àti Ìjebú

**Ọ̀yọ́**: Àwọn ẹ̀yà Yorùbá Ọ̀yọ́ lókìkí púpọ̀, wọ́n sì gbajúmọ̀ láàrin àwọn Yorùbá láyé àtijọ́ títí ó fi di àkókò yìí. Kò sí ẹ̀yà Yorùbá tí ó lè kọ iyán àwọn Ọ̀yọ́ kéré láwùjọ. Ní ayé àtijọ́, a mọ àwọn Ọ̀yọ́ gẹ́gẹ́ bí alágbára àti jagunjagun tó dá nítọ́. Ẹ̀yà Ọ̀yọ́ jagun gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ agbègbè ní ìhà Gúúsù Ìwọ-Oòrùn Adúláwọ̀ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Nàìjíríà kò tí ì wáyé gẹ́gẹ́ bí orílẹ̀-èdè nígbà náà. Wọ́n gba ilẹ̀ dé ilẹ̀ àwọn Ìbàrìbá àti ilẹ̀ Tápà. Wọ́n gba ilẹ̀ dé ilẹ̀ àwọn Ìdọ̀ọ̀mì (Dahomey) bẹ̀ẹ̀ ni àṣẹ wọn ré kọjá sí ilẹ̀ Tógò àti ilẹ̀ àwọn Àgànyìn (Ghana). Aláàfin ni ọba aládé wọn, bẹ́ẹ̀ ni Ọ̀yọ́-ilé ni olú-ìlú fún àwọn ọba yòókù nígbà tí a ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí.
Àwọn ọba aládé tí ń bẹ lábẹ́ Aláàfin ní àkókò yìí jù ẹgbàágbèje lọ, bẹ́ẹ̀ ni lára àwọn ìlú àmọ̀nà ní abẹ́ Aláàfin nígbà yìí ni Ìlọrin, Ìgbẹ́tì, Ìbàdàn, Ṣakí, Ògbómọ̀ṣọ́, Ìwó, Ìbàràpá méjèèje, Orílé-Òwu, Ìṣẹ́yìn àti Ìjàyè.

**Ẹ̀gbá:** Ẹ̀yà Yorùbá pàtàkì ni àwọn Ẹ̀gbá náà jẹ́. Ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, a lè rí wọn ní Ìjàyè, Olókèméjì, Odò-Ọnà, Ìlúgùn, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n pààlà pẹ̀lú Ìbàdàn. A gbọ́ pé ọ̀pọ̀ ẹbí tí wọ́n lórúkọ láàrin àwọn Ẹ̀gbá ni wọ́n máa ń tọ́ka sí i pé Ọ̀yọ́ ni wọ́n ti wá. Ẹ̀yà Ẹ̀gbá náà lókìkí láàrin Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní.

Àwọn tí a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀gbá pín sí ọ̀nà mẹ́ta:

1. Ẹ̀gbá Ìgbẹ̀yìn tí wọ́n súnmọ́ Ìjẹ̀bú Rẹ́mọ, bẹ́ẹ̀ ni àwọn olú ìlú wọn ni Aké, Ìjẹun, Kenita àti Ìporò
2. Ẹ̀gbá Gbágùrá ni àwọn tí wọ́n pààlà pẹ̀lú àwọn Ọ̀yọ́, bẹ́ẹ̀ ni àwọn olú ìlú wọn ni Àgùrá, Ìlúgùn, Ìká, Ọ̀jọ́, Ìláwọ̀ àti bẹ́ẹ̀ lọ.
3. Ẹ̀gbá Òkè Ọna ni àwọn olú ìlú bí i Okò, Ìkèrèkú, Ìkijà, Ìdómàpà, Odo, Poolo àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọba wọn ni Osilẹ̀. Ní ayé ìgbàanì, àwọn Ẹ̀gbá kò ní ọba òtòòtọ̀ nítorí pé abẹ́ Aláàfin ni gbogbo wọ́n wà nígbà náà.

**Ìjẹ̀bú**: Àwọn ẹ̀yà Ìjẹ̀bú gbà pé Ọbańta ni ó ṣẹ wọ́n sílẹ̀. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń pe ara wọn ní ọmọ Ọbańta.
Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé onírúurú ìtàn àtẹnudétí mìíràn tún wà lórí orírun àwọn ẹ̀yà yìí (Ìjẹ̀bú),ohun tí ó dájú ni pé lábẹ́ ìran Yorùbá ni àwọn ẹ̀yà Ìjẹ̀bú náà wà, wọ́n sì

máa ń tọ́ka sí Ilé-Ifẹ̀ gẹ́gẹ́ bí orírun wọn. Ní agbègbè Ìjẹ̀bú yìí ni a ti máa ń gbọ́ orúkọ àwọn ìlú bí i Ìjẹ̀bú-Igbó, Ìjẹ̀bú Mushin, Ìjẹ̀bú-Ifẹ̀, Àgọ́-Ìwòyè, Òdógbolú, Ìkẹnne, Ṣàgámù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Oyè ọba Ìjẹ̀bú Òde ni Awùjalẹ̀, èyí tí ààfin rẹ̀ wà ní Ìjẹ̀bú-Òde.

## 4.3 Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì àti Oǹdo:

**Ìjẹ̀ṣà**: Gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà àwọn Yorùbá yòókù, ẹ̀yà Ìjẹ̀ṣà náà ní onírúurú àwọn ìtàn àtẹnudẹ́tí nípa orírun wọn. A gbọ́ pé nígbà tí àwọn Yorùbá sẹ̀sẹ̀ tẹ̀dó sí orílẹ̀ wọn, tí Aláàfin wà lórí ìtẹ́, tí ó sì kọ́kọ́ tẹ̀dó sí Ilé-Ifẹ̀, àwọn ẹ̀yà Ìjẹ̀ṣà ni wọ́n wà ní agbègbè tí a mọ̀ sí Ìbòkun, tí wọn ń fi àwọn ẹrú wọn ṣiṣẹ́ lábẹ́ olórí wọn tí a mọ̀ sí Ìjẹ-òrìṣà tí àkékúrú rẹ̀ wá di Ìjẹ̀ṣà lónìí.
Àwọn Ìjẹ̀ṣà wọ̀nyí ní agbára àti okun láti dojúkọ iṣẹ́ tí a bá gbé fún wọn láti ṣe, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í janpata ibikibi tí a bá tì wọ́n sí. Lẹ́yìn-ọ̀-rẹyìn ni a gbọ́ pé Aláàfin fi Ọwajù ṣe olórí wọn láti Ilé-Ifẹ̀. Ìtàn àtẹnudẹ́tí mìíràn sọ pé lára àwọn Èkìtì ni àwọn Ìjẹ̀ṣà ti dìde, tí wọ́n sì pọ̀ sí i ní apá Ìbòkun níbi tí wọ́n ti tàn káàkiri ibi tí a mọ̀ sí ilẹ̀ Ìjẹ̀ṣà lónìí. Lára àwọn ìlú tí ó gbajúmọ̀ ní ilẹ̀ Ìjẹ̀ṣà lónìí ni Iléṣà, Òsú, Ẹrin-Ìjẹ̀ṣà, Ìpetu-Ìjẹ̀ṣà, Ìbòkun, Ẹ̀sà-Òkè àti Ìjẹ̀bú-Jẹṣà, bẹ́ẹ̀ ni oyè ọba wọn ni Ọwá.

**Èkìtì:** Ìtàn àtẹnudẹ́tí kan sọ pé ìtumọ̀ orúkọ ẹ̀yà Yorùbá yìí jẹyọ nínú ilé ikán tí a mọ̀ sí òkìtì, èyí tí ó fi bí agbègbè àti irúfẹ́ ilẹ̀ kòtò àti gegele tí wọ́n tẹ̀dó sí ṣe rí.
Àwọn ẹ̀yà Èkìtì yìí ya ara wọn sọ́tọ̀ lára àwọn Ìjẹ̀ṣà pàápàá nípa ìṣèjọba wọn. Wọ́n pín ara wọn sí ẹ̀ka mẹ́rìndínlógún, tí ọba wọn kọ̀ọ̀kan sì ń jẹ oyè Ọwá, bí o tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọba mẹ́rin kan wà gẹ́gẹ́ bí orí fún àwọn yòókù. Àwọn ọba wọ̀nyí ni:

1. Ewí ti Adó
2. Ẹlẹ́kọ̀lé ti Ìkọ́lé
3. Ajerò ti Ìjerò
4. Òwòrẹ́ ti Ọ̀tùn

Àwọn ọba aládé tí ó wà lábẹ́ àwọn mẹ́rin òkè yìí ni:

5. Alára ti Ará
6. Ajanpande ti Àkúrẹ́
7. Alágọ̀tún ti Ọ̀gọ̀tún
8. Gbójudo ti Ìdó
9. Ata ti Ayédé
10. Ọlọ́jà òkè ti Igbó Odò
11. Ọlọ́yẹ́ ti Ọyẹ́
12. Aláàyé ti Ẹfọ̀n-Aláàyè
13. Olómìwó ti Òmùwó
14. Owírè ti Ìrẹ̀
15. Arìnjalẹ̀ ti Iṣẹ̀
16. Onítaji ti Ìtaji

**Ondo:** Ìtàn àtẹnudétí kan sọ nípa àkókò kan tí ó jẹ́ pé ohun tí ó burú jáì ni láti bí ọmọ méjì lẹ́ẹ̀kan náà (ìbejì). Ní àkókò yìí ni a gbọ́ pé ọ̀kan nínú àwọn olorì (ìyàwó) Aláàfin bí ìbejì, bẹ́ẹ̀ ni ẹnikẹ́ni tí ó bá ti bí irú ọmọ abàmì bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò pa sínú igbó orò, àtọmọ àti ìyá abiyamọ náà.
Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé inú Aláàfin Àjàká kò dùn sí irúfẹ́ ìdájọ́ ikú yìí, ó pàṣẹ fún àwọn ẹ̀ṣọ́ rẹ̀ àti àwọn mìíràn tí wọ́n tẹ̀lé wọn pé kí wọ́n gbé wọn lọ sí agbègbè tó jìnnà réré, èyí tí ó jìnnà sí ilẹ̀ rẹ̀, kí wọ́n jù wọ́n sínú aginjù, igbó níbẹ̀, kí wọ́n sì gbà pé wọ́n ti kú síbẹ̀.
Ìtàn yìí sọ pé wọ́n mú ìyá àti àwọn ìbejì ọmọ rẹ̀ yìí lọ sí ibi kan tí a mọ̀ sí Òde Oǹdó lónìí. Àwọn olùgbé ibí yìí tí a mọ̀ sí Ìdoko kò pọ̀ rárá. Àwọn olùgbé agbègbè yìí wòye irú ènìyàn tí ó dé sí àarin wọnyìí jẹ́. Wọ́n ṣe àpọ́nlé wọn bí ẹni ńlá, wọ́n sì gbà pé kí àwọn ènìyàn àjèjì tí ó dé sí àarin wọn náà máa ṣe olórí wọn láti ìgbà náà lọ.
Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a máa ń ka àwọn Oǹdó mọ́ ẹ̀yà Èkìtì nígbà mìíràn, èyí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá nítorí pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n pààlà pẹ̀lú àwọn Àkúrẹ́ wọ́n jẹ́ ìdàpọ̀ àwọn Ọ̀yọ́ àti Ìdoko ṣùgbọ́n wọ́n ń bá wọn ṣe pọ̀.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín kejì yìí ni o ti kà ìdí tí a ṣe ń pe ìran Yorùbá ní ọmọ Odùduwà. A sọ̀rọ̀ nípa iye ọmọ tí Odùduwà bí fúnra rẹ̀ àti bí àwọn ọmọ-ọmọ rẹ̀ nípasẹ̀ Ọ̀kànbí ṣe di akọni, tí wọ́n sì tẹ àwọn ìlú dó, tí wọ́n sì di ẹ̀yà Yorùbá kọ̀ọ̀kan lónìí. A fi àbùdá àwọn ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan yìí hàn àti agbègbè tí wọ́n tẹ̀dó sí.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ àwọn tí a ń pè ní ọmọ Odùduwà.
2. Bá wo ni àwọn ọmọ Odùduwà ṣe tẹ àwọn ìlú dó àti pé àwọn wo ni a le tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí akọni àti aṣaájú ẹ̀yà Yorùbá kọ̀ọ̀kan?
3. Ipò àti ipa wo ni Aláàfin kó nínú ìṣèlú ẹ̀yà Yorùbá láyé àtijọ́
4. Dárúkọ àwọn ẹ̀yà Yorùbá méjì, kí o sì ṣe àlàyé ipò wọn ní àwùjọ Yorùbá láyé àtijọ́

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Johnson, S. 1921. *The History of the Yorùbás from the Earliest Beginning to the Time of the Protectorate,* Lagos.

Biobaku S.O. 1973. *Sources of Yorùbá History.* Oxford, Oxford University Press.

Mabogunjẹ, A.L. 1976. *The Land and Peoples of West Africa, Vol. One,* New York, Longman.

Ọbayẹmi Ade 1976. "The Yorùbá and Edo speaking Peoples and their Neigbours before 1600"
in Ajayi, J.F.A & Crowther M. *History of West Africa,* New York, Longman Group Ltd.

Ọgbọ́ntiba, F.A. 1997. *Glory of the Yorùbá Race, Past, Present and Future.* Ibadan, Global

Books and Publications.

Ademakinwa, J.A n.d *IFE, CRADLE OF THE YORÙBÁ RACE: A Handbook of the History of origin of the Yoruba.* Lagos, Yoruba Research Scheme.

# MÓDÙ KÌNNÍ

## ÌPÍN KẸTA

**Àkóónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Èdè Yorùbá
4.2 Èdè Yorùbá àti àwọn Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Mìíràn
4.3 Ìyàtọ̀ Èdè àti Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Mìíràn
4.4 Kíkọ èdè Yorùbá sílẹ̀
4.5 Òwe nínú Èdè Yorùbá
4.6 Oríkì àti ìwúlò rẹ̀ nínú Ẹ̀dè Yorùbá
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà:

Nínú ìpín yìí ni o ó ti kà pàtàkì ohun tí èdè jẹ́, tí aó tún sọ̀rọ̀ nípa èdè Yorùbá àti ipa tí ń kó ní àwùjọ àwọn ènìyàn yìí.
A mẹ́nuba bí èdè ṣe jẹ́ kòṣeémánìí láwùjọ àgbáyé. Lẹ́yìn èyí, a ṣe àlàyé lórí ìyàtọ̀ láàrin èdè àti àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mìíràn láàrin àwọn Yorùbá. Lẹ́yìn èyí ni a wo òwe Yorùbá àti ìwúlò rẹ̀ nínú èdè Yorùbá. Ní ìparí, a ṣe àlàyé nípa pàtàkì àti ìwúlò oríkì nínú èdè Yorùbá. Nǹkan wọ̀nyí fún wa ni ìdánilójú pé èdè kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn ní àwùjọ ẹ̀dá ènìyàn.

### 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Ní ìparí ìpín yìí, o ó mọ̀:

- ohun tí èdè jẹ́
- nípa ìwúlò èdè
- bí èdè ṣe jẹ́ okùnfà ìbáṣepọ̀ tí ó gúnmọ́
- ìyàtọ̀ láàrin èdè àti ọ̀nà ìbánisọ̀rò yòókù
- ẹ̀ka tí èdè Yorùbá ti súyọ nínú gbogbo ẹ̀ka èdè àgbáyé.

### 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú:

**(1)** Kín ni èdè? Ẹ̀ka èdè mélòó ni a lè rí ní ilẹ̀ Yorùbá?
**(2)** Pa òwe mẹ́ta kí o sì sọ ìtumọ̀ wọn
**(3)** Kín ni iṣẹ́ ti òwe náà máa ń jẹ́?

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Èdè Yorùbá

Ti o bá wo èdè ní gbogbo àgbáyé, o ó rí i pé ara ẹ̀ka àṣà ni ó jẹ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyàtọ̀ wà láti agbègbè kan sí òmíràn. Nínú èdè Yorùbá síso, a máa ń gbọ́

oríṣìíríṣìí èdè àdúgbò tí ó wà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò sí ẹ̀yà Yorùbá tí kò le ka Bíbélì tàbí Àlùkùránì tí a kọ ní èdè Yorùbá. Àwọn ẹ̀ka èdè yìí yàtọ̀¸sí ara wọn díẹ̀díẹ̀ láti agbègbè kan sí ìkejì àti pé bí àwọn ẹ̀yà kan bá ṣe jìnnà sí ara wọn tó ni èdè wọn yóò ṣe yàtọ̀ tó.
Èdè Yorùbá jẹ́ ọkan nínú àwọn èdè tí ó gbajúmọ̀ jù lọ ní gbogbo àgbáyé. Ó kún fún onírúurú ọgbọ́n, ìmọ̀, òye àti ìrírí tí ó fi hàn pé èdè Yorùbá kúrò ní wàsá láàrin èdè àgbáyé.

## 4.2 Èdè Yorùbá àti Àwọn Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Mìíràn:

Èdè ni a lè tọ́kasí bí ìlànà tí àwọn ènìyàn kan ń gbà lo ariwo tí a ń pa tàbí ohun tí a ń sọ jáde lẹ́nu láti fi èrò inú wọn hàn lọ́nà tí yóò gbà yé ẹni tí ó bá gbọ́ èdè náà. Ètò àti ìlànà wà tí a máa ń tẹ̀lé láti to àwọn ariwo náà pọ̀ kí ó tó lè ní ìtumọ̀ sí olùgbọ́. Nítorí náà, a lè sọ pé èrò inú ènìyàn tí a fi ohùn gbé jáde ni 'èdè'. Níbí sísọ lẹ́nu ni èdè ti bẹ̀rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni èyí kò yọ èdè Yorùbá sílẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni kò sí èdè tí a kọ́kọ́ kọ sílẹ̀ láìjẹ́ pé ẹnu ni a kọ́kọ́ fi sọ ọ́. A tilẹ̀ gbọ́ láti inú Bíbélì àti àwọn ìtàn àtẹnudétí kan pé èdè kan náà ni àwùjọ ènìyàn ní gbogbo àgbáyé ń sọ ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀, ṣùgbọ́n nítorí ìdí kan tàbí òmíràn, Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá da èdè aráyé náà rú, ó sì pín sí yẹlẹyẹ̀lẹ.

Àwọn díẹ̀ nínú àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mìíràn tí kì í ṣe èdè ni:

**<u>Gbígbó ajá:</u>** Bí ajá bá ń gbó ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ó sábà máa ń tọ́ka sí i pé nǹkan kan ń ṣẹlẹ̀ ni. Ó lè rí olè tàbí kí ó rí nǹkan abẹ̀mí mìíràn tí ènìyàn kò rí. Èyí kì í ṣe èdè rárá nítorí pé kì í ṣe gbogbo ènìyàn ni ó mọ ìtumọ̀ gbígbó náà.

**<u>Ọ̀rọ̀ ẹyẹ Odídẹrẹ́/Oódẹ/Ayékòótọ́:</u>** Ọ̀rọ̀ ẹnu ẹyẹ odídẹrẹ́ kì í ṣe èdè sísọ nítorí pé àwọn ọ̀rọ̀ tí ó bá gbọ́ lẹ́nu olówó rẹ̀ tàbí tí a ti fi kọ́ ọ ni yóò máa sọ. Ṣókí, ṣókí ni yóò sì máa sọ ọ́. Bí àpẹẹrẹ, ó lè sọ pé. 'Ẹ káàbọ̀'? 'Ẹ kúulé' 'Ebi ń pa mí', àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**<u>Ìfẹ́ Sísú, Ìlú Lílù, Pípa Arokò àti Fífi ẹ̀yà ara bí ọwọ́, ẹsẹ̀, imú, orí, ojú sọ̀rọ̀:</u>**

A níláti kíyèsí i pé àwọn ohun tí a dárúkọ lókè wọ̀nyí kì í ṣe èdè rárá nítorí pé wọ́n ní ààlà, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í sábà yí padà, wọ́n sì lópin. Ààmì lásán ni wọ́n jẹ́, yàtọ̀ sí èdè tí ó máa ń dàgbà lójoojúmọ́, tí kò sì ní òpin ibi tí a le sọ ọ́ mọ. Nítorí náà, a lè sọ pé àbùdá pàtàkì tí ẹ̀dá ènìyàn ní ni èdè.

## 4.3 Ìyàtọ̀ Èdè Yorùbá àti Àwọn Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Mìíràn

Èdè kọ̀ọ̀kan sábà máa ń yàtọ̀ sí ara wọn nítorí pé ohun tí ó dúró fún àmì kan nínú èdè kan le máa ní ìtumọ̀ kan náà nínú èdè mìíràn. A le fi èdè sọ ohun tí a ti ṣe kọjá, ohun ti a ń ṣe lọ́wọ́lọ́wọ́ tàbí ohun tí a ó ṣe lọ́jọ́ iwájú. Bí àpẹẹrẹ,

a. Mo lọ sí ilé ọ̀rẹ́ mi lánàá
b. Mo ń lọ sí ilé ọ̀rẹ́ mi báyìí
d. Èmi yóò lọ sí ilé ọ̀rẹ́ mi

Bí a bá ṣe àkíyèsí, a kò le fi àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ yòókù ṣe bẹ́ẹ̀. Nítorí náà, èdè kò lópin, a le máa sọ ọ́ títí ilẹ̀ yóò fi sú. Ó ní ibi tí ariwo ajá le mọ́ – bí ajá bá rí

àjèji ènìyàn, tàbí ajá ẹgbẹ́ wọn tàbí olè tàbí ẹ̀mí àìrí mìíràn, ó lè máa gbó lásán. Bákan náà ni bí àwọn ajá bá ń gùn. Bí ajá bá sí rí olówó rẹ̀, ó le máa yọ̀rù láti fi kí i káàbọ̀.
Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ènìyàn kan máa ń rán ajá wọn nísẹ́ sí ènìyàn, síbèsíbẹ̀ ó ní ìwọ̀nba ohun tí ajá lè sọ, ṣùgbọ́n èdè tàbi ọ̀rọ̀ tí ènìyàn ń sọ kò láàlà.

## 4.4 Akitiyan Nípa Kíkọ Ẹ̀dè Yorùbá Sílẹ̀

Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ pàápàá àwọn òyìnbó ẹlẹ́sìn Kírístì ṣe akitiyan láti jẹ́ kí èdè Yorùbá di kíkọ sílẹ̀, pàápàá nígbà tí wọ́n fẹ́ fi ìdí ẹ̀sìn wọn múlẹ̀.
Wọ́n rí i pé ẹ̀bùn àti àǹfààní tí ẹ̀dá ènìyàn ní tí ó sì yà wọ́n sọ́tọ̀ kúrò nínú gbogbo àwọn ẹ̀dá yòókù ni èdè jẹ́. Wọ́n mọ rírì pé okùnfà àlàáfíà àti ìgbọ́ra-ẹni-yé ni èdè. Bí àpẹẹrẹ, ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà nísinsinyìí, èdè-àìyedè tí ń sẹlẹ̀ jẹ́ orísun tàbí okùnfà rúdurùdu àti àìdọ́gba láàrin àwọn olùgbé ibẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni bí a kò bá le gbọ́ ara wa yé, ojú kan náà ni a máa wà sigidi bí adágún odò láìsí ìdàgbàsókè kan pàtó.
Bí a bá kíyèsí dáadáa, a ó rí i pé èdè Yorùbá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn èdè ilẹ̀ Adúláwọ̀ tí kò ní àkọsílẹ̀ kí àwọn ẹlẹ́sìn Kírísítì yìí tó wá sí àwùjọ àwọn Yorùbá láti tan ẹ̀sìn wọn kalẹ̀, ṣùgbọ́n wọ́n wòye pé èyí lè nira díẹ̀ bí èdè Yorùbá kò bá di kíkọ sílẹ̀
Nítorí ìdí èyí, àwọn Ìjọ C.M.S (Church Missionary Society) tí Ẹni-ọ̀wọ̀ Henry Venn jẹ́ akọ̀wé àgbà fún wá sí àwùjọ àwọn Yorùbá ní nǹkan bí ọgọ́jọ ọdún sẹ́yìn lábẹ́ olùdarí wọn, Ẹni-ọ̀wọ̀ Henry Townsend tí ó jẹ́ Olùsọ́-àgùntàn Ìjọ yìí ní ilẹ̀ Sàró (Siera-Leone); wọ́n sì mú Ẹni-ọ̀wọ̀ Samuel Àjàyí Crowther, ẹni tí í ṣe Àlùfáà ènìyàn dúdú kìnní ti Ìjọ C.M.S lọ́wọ́. Pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Ọ̀jọ̀gbọ́n Lepsius, wọ́n gbé ìlànà bí èdè Yorùbá yóò ṣe di kíkọ sílẹ̀ kalẹ̀.
Wọ́n rí i pé lábẹ́ ẹ̀ka èdè àgbáyé tí èdè Yorùbá ti súyọ ni wọ́n pè ní Kwa. Wọ́n fi yé wa pé lára àwọn ẹ̀ka èdè tí ó wà lábẹ́ Kwa yìí ni Kru, Banle, Twi, Gáà, Ewe, Fọn, Yorùbá, Ẹdó, Nupe, Igbo, Idoma, Ìjọ́ (Ijaw), Efik àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ẹ̀ka wọ̀nyí sì tàn ká gbogbo ìhà Ìwọ̀-Oòrùn Afíríkà (Bíòbákú, 1973:178) Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a gbọ́ níbí, àwọn èdè yìí fi ara pẹ́ ara, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń jọ ara wọn ní sísọ nígbà mìíràn.

## 4.5 Òwe Nínú Èdè Yorùbá

Òwe ṣe pàtàkì nínú àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní. Òwe máa ń kún fún ẹ̀dọ̀ki àti àdììtú ọ̀rọ̀, èyí tí olùgbọ́ máa ń ronú jinlẹ̀ kí ó tó mọ ìtumọ̀ rẹ̀. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń sọ pé; òwe lẹsin ọ̀rọ̀, bẹ́ẹ̀ ni bí ọ̀rọ̀ bá sọnù, òwe ni a fi máa ń wá a.
Bí ọ̀rọ̀ kan bá ṣókùnkùn, òwe ni a fi máa ń tan ìmọ́lẹ̀ sí i (Ọládàpọ̀, O. 1996). Èyí nìkan kọ́, bí ọ̀rọ̀ bá dójú agbami, òwe ni a fi lè wa ọkọ̀ rẹ̀ dé èbúté ayọ̀. Òwe yìí náà ni a lè pè ní atúdè ọ̀rọ̀ àti pé bí ọ̀rọ̀ bá lọ́jú pọ̀, òwe ni a lè fi yanjú rẹ̀. Nítorí náà, nínú òwe ni a ti máa ń rí ọ̀rọ̀ ọgbọ́n tí a gbé kalẹ̀ lọ́nà tí ó fi ìrírí àti òye Yorùbá hàn nípa àyíká wọn.
Ọmọdé ní í pàlọ́ bẹ́ẹ̀ ni àwọn àgbà ló máa ń sábà pa òwe. A lè fi òwe wé mùdùnmúdùn kan tí ó wà nínú àkámọ̀ ṣùgbọ́n tí a fẹ́ fi ojú rẹ̀ síta. Bí àpẹẹrẹ, àwọn nǹkan kan wà tí domudómú tàbí adùn inú wọn farasin àti pé kí á tó le gbádùn irú nǹkan bẹ́ẹ̀, a niláti fọ́ ọ, kí á sì mú tinú rẹ̀. Àpẹẹrẹ èyí ni ẹ̀pà, èkùrọ́, àgbọn, obì, tí ó jẹ́ pé bí a kò bá fọ́ tàbí pa èèpo ẹ̀yìn wọn, a kò le rí àdídùn inú wọn jẹ. Nítorí náà, ni a ṣe máa ń fi ọ̀rọ̀-ìṣe 'pa' kún àwọn nǹkan yìí. A máa ń

sọ pé a ń pa àgbọn, èkùrọ́, ẹ̀pà, obì, tí a sì máa ń sọ pé a ń pa òwé náà láti le mú ọ̀rọ̀ ìjinlẹ̀ inú rẹ̀ jáde.
Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn òwe tí a máa ń pa wọ̀nyí máa ń ṣúyọ nínú ìrírí àti àkíyèsí àyíká ẹni bí a bá ṣe ń dàgbà ní àwùjọ. Èyí túmọ̀ sí pé ohun tí ojú àgbà ti rí ṣẹ́yìn ni wọ́n máa ń hun pọ̀ di òwe. Bí àpẹẹrẹ:

1. Kí ojú má ríbi, ẹṣẹ̀ ni oògùn rẹ̀
2. Igi gogoro má gún mi lójú, àtòkèèrè la ti í wò ó.
3. Ìrínisí nìṣenilọ́jọ̀
4. Súnmọ́ni làá mọ̀ṣe ẹni, èèyàn gbókèèrè níyì.

A ó rí i pé àkíyèsí àyíká àti ìrírí tí a ní ní ó mú àwọn Òwe òkè yìí wá. Nítorí náà, bí ọ̀dọ́mọdé bá ní láti pa òwe níbi tí àwọn àgbà wà, ó di dandan kí ó tọrọ ìyọ̀nda tàbí gba àṣẹ lọ́wọ́ àwọn àgbà tó wà níbẹ̀.

## 4.6 Ìwúlò Òwe ní Àwùjọ Yorùbá

Àwọn òwe tí a máa ń pa yìí ní iṣẹ́ pàtàkì tí wọ́n máa ń jẹ́ fún àwọn tí a bá pa wọ́n fún. Nígbà mìíràn, a máa ń fi òwe kìlọ̀ ìwà tàbí kí á fi gbani nímọ̀ràn. Yàtọ̀ sí èyí, a sábà máa ń pa òwe nígbà tí ọ̀rọ̀ kan bá takókó, láti tan ìmọ́lẹ̀ sí i. A máa ń fi òwe ṣe àpọ́nlé ènìyàn tàbí kí á fi ta àbùkù rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ;

1. Ìrírí ni baba ọgbọ́n, ó ṣe mí rí ni baba làákàyè
2. Èèyàn tanra rẹ̀ jẹ bíi Tégbè

Òwe wúlò láti fi wá àlàáfíà ní àwùjọ tàbí kí á fi so okùn ìrẹ́pọ̀ le danin-dain. Wàyí o, ṣókí ṣókí ni gbólóhùn òwe, kí í gùn gbọọrọ bí ìgbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ lásán, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òwe máa ń lóyún ọ̀rọ̀ sínú nítorí pé òwe mìíràn lè jẹ mọ́ ìtàn ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ rí. Bí àpẹẹrẹ, 'Ìdúró gbàkòò ni ìdúró gbádẹ, a dífá fún adánilóró gbàgbé ọ̀la'.

## 4.7 Oríkì

Ọ̀kan nínú àwọn ìpèdè àti ọ̀nà tí a fi ń dá ojúlówó ọmọ Yorùbá mọ̀ ni oríkì. Bí a ti ní oríkì àdájẹ́ fún ẹnìkọ̀ọ̀kan, ni a ní oríkì ìnagijẹ èyí tí ó fi ìwà, ìṣe tàbí àbùdá ẹni hàn. A tún máa ń gbọ́ nípa oríkì àmútọ̀runwá àti oríkì orílẹ̀ tàbí ti ìdílé.
Ní àárin àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́,bí wọ́n bá ti ń sọ ọmọ ní orúkọ ní ọjọ́ kẹjọ ni wọn yóò máa fún un ni oríkì àdájẹ́, èyí tí ó bá orúkọ náà mu. Bí àpẹẹrẹ *oríkì àdájẹ́*, èyí tí ó máa ń jẹ́ ṣókí:

1. Àlàdé ni ọmọ tí ó máa ń ní agbára, tí a kò lè kó láyà jẹ
2. Àlàbí ni ọmọkùnrin tí a bí tẹ̀lé àwọn ọmọbìnrin púpọ̀
3. Àwẹ̀ró ni ọmọbìnrin tí a bí tí a sì ró o láṣọ tí ó dára
4. Àṣàbí ni ọmọbìnrin tí a dù láti bí tàbí ẹni tí à ń dù pé kí a bí lọ́mọ

Ṣùgbọ́n àwọn oríkì ìnagijẹ mìíràn wà fún àpọ́nlé tàbí àbùdá. Bí àpẹẹrẹ;

1. Ọkùnrin kọ́rọ́bọ́tọ́ bí ọká
2. Onínú funfun bí ẹmu
3. Orékelẹ́wà amọ́bíọjọ́

4. Oníwà tútù bí àdàbà
5. Ọ̀pẹ́lẹ́ńgẹ́ subú láwo, àwo kò fọ́, ó subú lu odó, odó fàya.

Bí a bá ṣe àkíyèsí àwọn oríkì tí a máa ń fún àwọn ọmọ ní ilẹ̀ Yorùbá, a ó rí i pé ó máa ń fi ìwà ìgboyà tàbí ìwà akíkanjú hàn. Ó tún máa ń fi ipò tí ẹbí tàbí àwùjọ wà hàn nígbà tí a bí ọmọ náà.

Ní ti àwọn ọmọbìnrin, a ó rí i pé àwọn abiyamọ sábà máa ń fẹ́ràn ọmọbìnrin púpọ̀, bẹ́ẹ̀ ni oríkì tí wọ́n máa ń fún wọn le tọ́ka sí ìfẹ́ tí wọ́n ní sí ọmọbìnrin bẹ́ẹ̀. **Oríkì ìnagijẹ** ní ọ̀pọ̀ ìgbà máa ń mú ìjà lọ́wọ́ láti ọ̀dọ̀ ẹni tí a bá ń kì ní oríkì bẹ́ẹ̀ nítorí irúfẹ́ oríkì bẹ́ẹ̀ lè jẹ mọ́ àbùkú tàbí èébú ẹni tí a ń kì náà. Bí àpẹẹrẹ

1. Òróbìnrin dòrí
2. Balógun lẹ́yìn obìnrin
3. Jókòó tàgbà má júpè rán-níṣẹ́
4. Irú lọ̀tùn-ún, ògìrì lósì, a níhun téesin ń jẹ lẹ́nu

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn oríkì mìíràn le jẹ mọ́ aléébù ìwà ẹnìkan, ó ṣe é ṣe kí onítọ̀ún yí ìwà tàbí ìṣe rẹ̀ náà padà. Wàyí o, àwọn ìnagijẹ mìíràn máa ń kọ́ àwọn ènìyàn ní ìwà ọmọlúàbí láwùjọ.

**Orikì Àmútọ̀runwá:**Púpọ̀ nínú orúkọ àmútọ̀runwá bí Ìbejì, Òjó, Àìná, Àjàyí, Dàda, Ìlọ̀rí, Ìge, Olúgbódi àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni ó máa ń ní àwọn oríkì tí ó ń bá wọn wá. Irúfẹ́ àwọn oríkì bẹ́ẹ̀ sábà máa ń gùn díẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni àwọn oríkì wọ̀nyí máa ń fi ìsesí àti ìrí àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀ hàn. Bí àpẹẹrẹ, oríkì ìbejì àti oríkì Ìgè tí ó lọ báyìí:

**Ìbejì:**
Ẹ̀jìrẹ́ òyílà
Wínni-wínni lójú orogún
Èjìwọ̀rọ̀ lójú ìyá rẹ̀
Ọmọ kọ ilé aláṣọ kò lọ
Ẹ̀jìrẹ́ wá salákìísà donígba aṣọ…
Ò bẹ́ jìgà bẹ́ gìjà
Ó fẹsẹ̀ méjèèjì bẹ́ sílé alákìísà
Ó salákìísà daláṣọ

**Ìgè**:
Ìgè Àdùbí Oníbìíyọ̀
Anumọ bí ẹyẹ
Ìgè má nù mí mọ́, ọwọ́ mi tẹ́nu mi
Ẹyẹ ńlá tí í numọ rẹ̀ bí àrà
Ìgè àdùbí tó ní bíyàá lè kú kó kú
Ọlá baba tóun í jẹ…
(Oríkì àpèlé)

Àwọn oríkì mìíràn wà tí ó jẹ́ mọ orúkọ àpèlé tí a mọ̀ mọ̀ wọ́n. Irúfẹ́ àwọn orúkọ àpèlé yìí máa ń sábà dá lé àbùdá ènìyàn. Ó lè jẹ́ mọ́ àbùdá ìrísí, ìhùwàsí tàbí ìwà akíkanjú tí ẹnìkan ti hù tí ó sì mú kí irú ẹni náà di gbajúmọ̀ ní àwùjọ. Èyí sábà máa ń ṣe àpèjúwe ìrú ẹni bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:

1. Sóbọ̀, Aróbíodu
2. Abísóyè, Olóde Òkúta
3. Àjàyí, Ògídí-Olú
4. Babalọlá, Atólúgbokùn
5. Mọrẹ́nikẹ́, Ọmọ Akáába
6. Adéníkẹ̀ẹ́, Aláṣèpa-ìlasa

**Oríkì Orílẹ̀:**Èyí jẹ́ ohun tí ó wọ́pọ̀ láàrin àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ẹ̀yà mìíràn náà wà tí wọ́n ní oríkì tí ó so wọ́n pọ̀. Láàrin àwọn Ọ̀yọ́, a lè tọ́ka sí oríkì orílẹ̀ bí i: Ẹ̀rìnmòjé, Ìrẹ̀sà, Oníkòyí, Olú-Òjé, Olómù, Ọlọ́fà,, Òpómúléró, Olúgbọ́n, Arágberí, Olókùn-ẹsin, Ológbìn-ín àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
Nínú àwọn oríkì orílẹ̀ yìí ni a ti máa ń mọ ibi tí àwọn ènìyàn tàbí ìlú ti sàn dé ibi tí wọ́n wà lónìí yìí.

## 5.0 Ìsọnísókí

Ní ìpín kìnní yìí ni o ti kà nípa èdè Yorùbá àti ibi tí ó ti hù jáde nínú ẹ̀ka èdè àgbáyé. A sọ̀rọ̀ nípa àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mìíràn bí gbígbó ajá, ọ̀rọ̀ ẹnu ayékòótọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A sọ̀rọ̀ nípa akitiyan àwọn ẹlẹ́sìn tí wọ́n gbìyànjú àtikọ́ èdè Yorùbá sílẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni a mẹ́nuba ìsọ̀rí òwe àti oríkì nínú èdè Yorùbá.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Nínú ẹ̀ka èdè àgbáyé wo ni èdè Yorùbá ti ṣúyọ?
2. Sọ̀rọ̀ lórí àwọn ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin èdè àti àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ mìíràn tí kì í ṣe èdè.
3. Kín ni ipa tí òwe ń kó nínú èdè Yorùbá?
5. Ṣàlàyé ohun tí oríkì Yorùbá máa ń dá lé lórí àti ìwúlò wọn.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Ladele, T.A.A et al 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ibadan: Gavima Press Ltd.

Ọladapọ, T. 1996. *Ẹgbẹ̀ta Òwe; Orin Odídẹrẹ́ 9.* Ìbàdàn, Ọmọ Ogungbola Ventures Ltd.

Ojo, T.A. 1966. *Yorùbá Culture.* London, University of London Press.

Fadipe, N.A. 1970. *The Sociology of the Yorùbá.* Ibadan, Ibadan University Press.

# MÓDÙ KÌNNÍ

## ÌPÍN KẸRIN: ÈRÒ YORÙBÁ

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Èrò Yorùbá Nípa Àwọn Ẹ̀mí Àìrí
4.2 Èrò Yorùbá Nípa Owó
4.3 Èrò Yorùbá Nípa ọmọ
4.4 Èrò Yorùbá Nípa Àìkú tàbí Atubọ̀tán Ayé
4.5 Èrò Yorùbá Nípa Ikú àti Ìyè Lẹ́yìn Ikú
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtó.kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Nínú ìpín yìí ni o ó ti kà èrò ìran Yorùbá nípa àwọn ẹ̀mí àìrí àti ibi tí wọ́n ń gbé. A ó tún wo èrò àwọn ènìyàn yìí nípa Àjẹ́ àti àwọn ohun tí ó rọ̀ mọ́ wọn. Èrò àwọn Yorùbá nípa owó, ọmọ àti àìkú tàbí àtubọ̀tán ni a tún gbéyẹ̀wò, bẹ́ẹ̀ ni a kò ní í sàìmọ èrò wọn nípa ìyè lẹ́yìn ikú.

### 2.0 Èròǹgbà/Afojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó mọ:

- èrò Yorùbá nípa àwọn ẹ̀mí àìrí gbogbo
- ohun tí Yorùbá ní lọ́kàn nípa àwọn àjẹ́
- ohun tí wọ́n lérò nípa owó àti ọmọ
- èrò Yorùbá nípa àìkú baálẹ̀ ọrọ̀
- ohun tí Yorùbá ni lọ́kàn nípa ikú àti ìyè lẹ́yìn ikú

### 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú:

1. Ṣàlàyé èrò tìrẹ nípa àwọn ẹ̀mí àidrí
2. Ǹjẹ́ lóòótọ́ ni àwọn àkúdàáyà wà?
3. ‘Owó kò tó ọmọ! Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.

### 4.1 <u>Èrò Yorùbá Nípa Àwọn Ẹ̀mí Àìrí</u>:

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé oríṣìí ẹ̀mí àìrí méjì ni ó wà. Bí rere ṣe wà, bẹ́ẹ̀ ni búburú wà pẹ̀lú. Wọ́n tún ní èrò pé oríṣìí méjì ẹ̀mí àìrí ló wà – àwọn òrìṣà àti àwọn òkú ọ̀run. Àwọn ẹ̀mí àìrí rere wọ̀nyí ló máa ń ṣe àtilẹ́yìn fún ènìyàn lójoojúmọ́ ayé, bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé wọn le bínú sí ẹnikẹ́ni tí ó bá kọ̀ láti ṣe ojúṣe rẹ̀ sí ẹnìkejì rẹ̀ tàbí sí ẹ̀mí àìrí rere mìíràn.
Láti ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà tí ó jẹ́ agbẹnusọ àwọn òrìṣà àti òkú ọ̀run bẹ́ẹ̀ ni níbí yìí ni wọn yóò ti mọ̀ nígbàkígbà tí àwọn ẹ̀mí àìrí wọ̀nyí bá ń bínú. Wọ́n yóò sì mọ ẹbọ tàbí ètùtù tí wọn yóò gbà láti fi tù wọ́n lójú. Ṣùgbọ́n sá o, Yorùbá gbà pé àwọn

òrìṣà àti òkú ọ̀run wọ̀nyí kì í sábà bínú sí ènìyàn, bí kò ṣe pé kí wọ́n dáàbò bo ènìyàn lọ́wọ́ àwọn ẹ̀mí àìrí búburú yòókù.
Oríṣìí méje ni wọ́n gbà pé àwọn ẹ̀mí àìrí búburú náà pín sí. Àwọn ni Ajogun àti àwọn Ẹlẹyẹ tí wọ́n máa ń pè ní àjẹ́. Àwọn wọ̀nyí wá láti ba ire ọmọ ènìyàn jẹ́ ni tàbí láti yẹ kádàrá dáradára tí ọmọ ènìyàn bá yàn. Orúkọ àwọn ajogun náà ni, Ikú, Àrùn, Ẹ̀gbà, Ofò, Èpè, Ẹ̀wọ̀n, àti Ọ̀ràn. Ẹbọ ni a fi máa ń tu àwọn ajogun wọ̀nyí nínú.
Kò sí ibi tí wọn kò ti mọ̀ ní gbogbo ayé ìgbàanì pé kí nǹkan bàjẹ́ ni àwọn àjẹ́ wà fún. Wọ́n ṣetán láti bá ohun tí ó dára jẹ́. Yorùbá gbà pé ẹbọ rírú kò ràn àwọn àjẹ́ àti pé 'orí' ẹni ni ó le dáàbò bò wá lọ́wọ́ wọn.
Ní ti Iwin tàbí Ọ̀rọ̀, àwọn Yorùbá gbà pé ọ̀tá àwọn ènìyàn ni wọ́n, bẹ́ẹ̀ ni òru ni wọ́n sába máa ń jáde. Àwọn Yorùbá gbà pé àwọn iwin wọ̀nyí sábà máa ń rìn lóru ní ìrísí ènìyàn ṣùgbọ́n àwọn mìíràn máa ń ní ojú mẹ́ta tàbí kí wọ́n ní ojú kan soso ní ìpàkọ́. Bí iwin bá pàdé ènìyàn lọ́nà, ìmúra kí ó ṣe wọ́n ní ìjàm̀bá ni ó sábà máa ń mú.

## 4.2 <u>Èrò Yorùbá Nípa Owó</u>:

Ire owó jẹ ìran Yorùbá lógún púpọ̀. Wọ́n gbà pé láìsí owó, ìwàláàyè ènìyàn kò pé. Ìyẹn ni pé owó ni kókó. Àwọn kan tilẹ̀ máa ń jẹ́ orúkọ bí 'Owónikókó', 'Owóṣeéni', Olówóòkéré tàbi 'Olówólayémọ̀. Onírúurú òwe àti àkànlò èdè ni ó wà láti fi pàtàkì owó hàn láwùjọ. Wọ́n lè sọ pé 'Owó tán lọ́wọ́ oníwà, ó di òsónú. Bí a bá wo inú ẹ̀sìn gan-an lóde òní, a ó rí i pé ẹni tí kò lówó lọ́wọ́, kò le ṣe ẹ̀sìn dáadáa nítorí owó ni kẹ̀ẹ̀kẹ̀ ìyìnrere. Ìdí nìyí ti àwọn kan ṣe máa ń sọ pé "torí Ọlọ́run kò dé Mọ́kà".
Bí ènìyàn kò bá lówó lọ́wọ́ tí ebí bá ń pa á, irú ẹni bẹ́ẹ̀ yóò jalè, nítorí pé ebi kì í wọnú, kí ọ̀rọ̀ mìíràn wọ̀ ọ́. Ìdí nìyí tí wọn ṣe máa ń sọ pé 'owó kò sí, ènìyàn kò sunwọ̀n' tàbí pé 'owó ní bí òun kò bá sí nílé, kí ẹnikẹ́ni má dámọ̀ràn kankan lẹ́yìn òun.

## 4.3 Ọmọ:

Yorùbá ka ọmọ sí púpọ̀ ní ìgbésí ayé wọn. Wọ́n gbàgbọ́ pé kò sí bí ènìyàn ti lówó tàbí ní ọrọ̀ tó, tí kò bá bímọ, asán ni. Bí ó tilẹ̀ jé pé láìsí owó, o ṣeéṣe kí á má lè fẹ́ ìyàwó tàbí bímọ, Yorùbá gbàgbọ́ pé ọmọ ni kókó. Ìdí nìyí tí a ṣe máa ń pàtàkì èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ọmọ, nínú orúkọ tí wọ́n máa ń sọmọ wọn. Bí àpẹẹrẹ, Ọmọ́yájowó, Ọmọlará, Ọmọboríowó, Ọmọtọ́ṣọ̀ọ́, Ọmọtárá, Ọmọládùn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4.4 Àìkú tàbí Àtubọ̀tán Ayé:

Yorùbá máa ń sọ pé, ire mẹ́ta là wá ń wá

a. Ire owó
b. Ire ọmọ
d. Ire àìkú baálẹ̀ ọrọ̀ tàbí àtubọ̀tán ayé.

Ohun tí gbogbo àwọn nǹkan mẹ́ta òkè yìí ń tọ́ka sí ni pé kí á lè gbádùn dọjọ́ alẹ́, kí ọjọ́ alẹ́ sì dára fúnni. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, ọmọ ṣe pàtàkì fún àwọn Yorùbá bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìran ènìyàn mìíràn kò ka ọmọ sí. Àwọn mìíràn kì í tilẹ̀ bímọ rárá. Yorùbá gbàgbọ́ pé ọmọ làfẹ̀yìntì tó bá dọjọ́ ogbó. Èyí ni a ń pè ní 'àtubọ̀tán

ayé', èyí ni ọjọ́ alẹ́ tí òbí máa ń jèrè ọmọ. Nítorí náà, Yorùbá máa ń wúre pé kí alẹ́ san òun ju òwúrọ̀ lọ. Ẹni tí kò bá sòfò alẹ́, àtubọ̀tán rẹ̀ dára nìyẹn.

## 4.5 Èrò Yorùbá Nípa Ikú:

Yorùbá gbà pé méjì ni ìsẹ̀dá ènìyàn pín sí – ara àti ẹ̀mí, àti pé bí ẹ̀mí bá ti kúrò lára ni ara di òkú. Yorùbá máa ń ní àkíyèsí nípa bóyá ẹ̀mí sì wà lára tàbí kò sí. Wọn a máa fi òwú lé àwọn aláìsàn láyà làti mọ èyí. Lọ́nà mìíràn, wọ́n máa ń ṣe àkíyèsí pé ihò imú ni ẹ̀mí máa ń gbà jáde nínú ara. Wàyí o, Yorùbá gbàgbọ́ pé àwòrán Olódùmarè tí í ṣe Ẹlẹ́dàá ohun gbogbo ni ẹ̀mí. Nítorí náà, wọ́n gbàgbọ́ pé ẹ̀mí kò le kú. Àwọn ènìyàn yìí gbàgbọ́ pé bí ẹ̀mí bá ti kúrò ni ara, ọ̀nà àgbẹ̀dẹ ni yóò kọ́kọ́ gbà lọ láti lọ bọ́ àgọ́ ara rẹ̀ sílẹ̀. Wọ́n máa ń sọ pé a lè rí òjìji ènìyàn bẹ́ẹ̀ ni èyí ni àwòjìji ẹni náà nígbà tí ó bá kú tán. Àwọn tí ó ti dákú rí àti àwọn tí wọ́n ti ní ìjàm̀bá mọ́tò máa ń jẹ́rìí sí àwọn nǹkan wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí ìrírí wọn.
Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé bí ènìyàn bá kú, wọ́n tún le ri àwòjìji rẹ̀ níbòmíràn. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe gbàgbọ́ nínú àkúdàáyà. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ènìyàn yìí gbàgbọ́ pé bí ẹni tí ó kú náà bá dàgbà kí ó tó fi ayé sílẹ̀, irú wọn máa ń padà wá sínú ẹbí tí ó fi sílẹ̀. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń sọ orúkọ bí Babátúndé, Yétúndé, Ìyábọ̀, Babáwálé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4.6 Èrò Yorùbá Nípa ìyè lẹ́yìn Ikú:

Oríṣìí ikú mẹ́ta ni Yorùbá gbà pé ó wà – ikú ẹlégbẹ́ ọmọ, Emèrè àti àbíkú. Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹlẹ́gbẹ́ ni irúfẹ́ àwọn ọmọ yìí àti pé wọ́n lẹ́gbẹ́ lọ́run àti láyé, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń dá májẹ̀mú ìgbà tí wọn yóò padà lọ́run lọ̀hùn-ún. Wọ́n gbàgbọ́ pé bí irú ọmọ bẹ́ẹ̀ bá ti kú, wọ́n ń padà sọ́dọ̀ àwọn ẹlẹ́gbé rẹ̀ lọ́run ni.
Oríṣìí ikú kejì ni ikú ọ̀dọ́. Eléyìí lè kú nínú ìjàm̀bá mọ́tò, ti iná tàbí omi. Ó sì lè jẹ́ ikú láti ọwọ́ àwọn àjẹ́ tàbí lẹ́bọlóògùn ni. Irú àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí kò fẹ́ lọ ṣùgbọ́n ayé ni ó já wọn ní tànmọ́-ọ̀n tí wọ́n fi ṣe kòńgẹ́ ikú àìtọ́jọ́ yìí. Wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn ẹbí ọ̀run kò retí ẹni bẹ́ẹ̀ lọ́run lọ̀hùn-ún. Nítorí náà, wọ́n máa ń dá irú òkú bẹ́è padà ní bodè ọ̀run wá sí tayé. Bí irú ẹni bẹ́ẹ̀ kò bá lè padà sínú ẹbí tí ó ti kú, irú wọn ni wọ́n máa ń di àkúdàáyà, tí wọn yóò sì di:
Ewúrẹ́ jewéjewé
Àgùntàn jẹmọ̀ jẹmọ̀
Aláàmù tí ń jẹ́ lẹ̀gbẹ̀ẹ́ ògiri
Tí ń bá gbogbo ẹbọra jẹun
A tún máa ń pe irú ẹni bẹ́ẹ̀ ni 'ayọ́runbọ̀' tí ó máa ń pòórá mọ́ àwọn ènìyàn tí wọ́n bá ri wọn lójú.
Oríṣìí ikú kẹta ni ikú àgbà tí ó fọwọ́ rọrí kú. Ikú dáadáa ni èyí nítorí ìgbà yìí ni àwọn ẹbí wọn tọ̀run máa ń mú wọn sọ́dọ̀. Wọ́n gbà pé ọjà ni wọ́n wá ná láyé àti pé ayé lọjà, ọ̀run nilé.

## 5.0 Ìsọnísókí

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú ìpín yìí àwọn ẹ̀mí àìrí pọ̀ nínú afẹ́fẹ́ èyí tí ó jẹ́ pé bí a bá rìn tàbí jáde lóru, ó ṣeéṣe kí á bá wọn pàdé. A rí i pé ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀mí àìrí búburú ni àjẹ́ àti pé wọ́n máa ń ba ohun rere jẹ́ ni.
Bí a ṣe rí àwọn ẹ̀mí àìrí rere náà ni àwọn búburú wà, nígbà tí àwọn ẹ̀mí aìrí rere wà láti máa dáàbò bo ènìyàn.

Níbí ni a ti ṣe àlàyé bí owó àti ọmọ ṣe ṣe pàtàkì tó nínú èrò Yorùbá. Wọ́n tún gbà pé àìkúléwe náà jẹ́ ohun tí Yorùbá máa ń tọrọ. Yorùbá gbà pé ikú kì í ṣe òpin ẹ̀dá àti pé a máa pa ipò dà lọ sí ọ̀run tàbí kí á máa gbé ìgbé-ayé níbòmìíràn.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ipa wo ni àwọn ẹ̀mí àìrí máa ń kó nínú ìgbésí ayé ẹ̀dá gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣúyọ nínú èrò àwọn Yorùbá?
2. Kín ni ìdí tí àwọn Yorùbá fi ka owó, ọmọ àti àìkúléwe sí nǹkan bàbàrà?
3. Ṣàlàyé lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ èrò àwọn ẹ̀sìn àbáláyé àti ti ìgbàlódé nípa ìyè lẹ́yìn ikú

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Abraham, C. 1958, *Dictionary of the Yorùbá Language,* London, Lowe & Brydone Press.

Adeoye, C.L. 1979. *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá.* Ibadan, Oxford University Press (Nig) Ltd.

Fádípẹ̀, N.A. 1976. *The Sociology of the Yorùbá.* Ibadan, Ibadan University Press.

Ilesanmi, T. M. ed. 1989. *Iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé*, Ilé-Ifẹ̀, Ọbafemi Awolowọ University Press Ltd.

**MÓDÙ KÌNNÍ**

**ÌPÍN KARÙN-ÚN: ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ**

Àkóónú

**1.0** Ìfáàrà
**2.0** Èròǹgbà/Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìsaájú
**4.0** Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Olódùmarè
4.2 Ìgbàgbọ́ Nípa ìṣẹ̀dá Ayé àti Ọ̀run
4.3 Ìgbàgbọ́ Nípa Awo àti Ìmùlẹ̀
4.4 Ìgbàgbọ́ Nípa Orí àti Àyànmọ́
4.5 Ìgbàgbọ́ Nípa Àwọn Aláṣekù tàbí Ìbọ
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí

**1.0 Ìfáàrà:**

Gẹ́gẹ́ bí àwọn àwùjọ yòókù ní àgbáyé, Yorùbá gbàgbọ́ pé Ẹlẹ́dàá kan ni ó dá ayé àti ọ̀run àti pé Òun ni ó ṣẹ̀dá àwọn ènìyàn inú ayé. Nítorí náà, nínú ìpín yìí, o ó kà ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Olódùmare, èyí ni orúkọ tí wọ́n ń pè Ẹlẹ́dàá náà ní èdè tiwọn.
A wo bí Olódùmarè yìí ṣe ṣẹ̀dá ayé àti ọ̀run, a sì mẹ́nubà ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa àwọn ẹgbẹ́ awo àti ìmùlẹ̀ tí Yorùbá gbàgbọ́ pé wọ́n mọ àṣírí ìkọ̀kọ̀ ohun gbogbo tí ń bẹ nínú ayé àti òde ọ̀run.
Lẹ́yìn èyí ni a wo ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn yìí nípa'Orí' tàbí 'Àyànmọ́' tí a sì wo ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ lórí àwọn Aláṣekù tàbí Ìbọ.

**2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn:**

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó:

- Ní òye lórí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Ẹlẹ́dàá ayé àti ọ̀run
- mọ bí Ẹlẹ́dàá náa ṣe dá ayé àti ohun gbogbo tí ń gbé inú rẹ̀
- ní ìmọ̀ kíkún lórí àwọn ẹgbẹ́ Awo àti Ìmùlẹ̀ tí wọ́n máa ń wà ní àwùjọ Yorùbá.
- ní òye lórí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa 'Orí' tàbí 'Àyànmọ́'

**3.0 Ìbéèrè Ìsaájú**

1. Sọ̀rọ̀. Kíkún lórí ohun tí o mọ̀ nípa Olódùmarè.
2. Dárúkọ àwọn álásekù ní ilẹ̀ Yorùbá
3. Kínni o mọ̀ nípa àyànmọ́?

## 4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Olódùmarè

Nígbà tí ẹ̀dá ènìyàn dé sínú ayé ni ó ti wòye, tí ó sì fura pé òun kò le ṣàdédé wà láìjẹ́ pé ẹnìkan tí ó tóbi ju òun lọ ni ó fa sábàbí bí òun ṣe wà lókè eèpẹ̀. Lẹ́yìn èyí, ni ó ronú pé ẹni ti ó sẹ̀dá òun gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹnìkan tí òun yóò máa bọ̀wọ̀ fún, kí

òun sì máa forí balẹ̀ fún un. Nítorí náà, ẹ̀dá ènìyàn ronú títí lórí irúfẹ́ orúkọ tí òun yóò máa pe ẹni ńlá náà, èyí tí ó le fi ipò ńlá rẹ̀ hàn yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀dá títóbi mìíràn tí ó yí wọn ká. Èyí ni ó fa orúkọ tí ẹ̀dá ènìyàn fún Ẹlẹ́dàá náà ni agbègbè kọ̀ọ̀kan. Àwọn Lárúbáwá pé É ní Allah, bẹ́ẹ̀ ni àwọn Júù tàbí Hébérù pè É ní Yahweh nígbà tí àwọn Yorùbá pè É ní Olódùmarè.

Ní ti àwọn Yorùbá, wọ́n gbàgbọ́ pe Olódùmarè yìí ni ó dá ayé àti ohun gbogbo tí ń bẹ nínú rẹ̀. Wọ́n gbàgbọ́ pé Olódùmarè yìí ni ó dá àwọn òrìṣà pàápàá. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé àti òrìṣà, ẹranko àti ènìyàn, kò sí ẹnikẹ́ni tí ó tóbi tó Olódùmarè bóyá ní ti agbára, ọgbọ́n tàbí ipò. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé bí Yorùbá bá tilẹ̀ ń ya àwòrán àwọn ẹ̀dá àti òrìṣà gbogbo, kò tí i sí ẹni tí ó gbìyànjú láti ya àwòrán Olódùmarè yìí rí.

Yorùbá gbàgbọ́ pé àwámárídìí ni iṣẹ́ Olódùmare, èyí tí ó túmọ̀ sí pé Olódùmarè kọjá ẹni tí a lè máa tọpinpin rẹ̀. Láti fi ìdí èyí múlẹ̀, wọ́n máa ń pe Olódùmarè yìí ni àwọn orúkọ àdàpè bí i Ọgá-Ògo, Àwámárídìí, Aṣèkanmákù, Apọjọ́-ikú-dà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nítorí náà, ó hàn nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá pé Olódùmarè tóbi ju gbogbo ẹ̀dá ayé àti ti ọ̀run lọ.

## 4.2 Igbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ìṣẹ̀dá Ayé àti Ọ̀run:

Ìtàn àtẹnudẹ́tí kan sọ fún wa pé ọ̀run tàbí àwọ̀sánmọ̀ súnmọ́ ilé ayé ní ìgbà ìwásẹ̀, ṣùgbọ́n fún àwọn ìdí kan tàbí òmíràn, Olódùmarè bínú, ó sì fa àwọ̀sánmọ̀ ga sókè bí ó ṣe wà lónìí yìí.

Lára àwọn ìdí tí Olódùmarè fi jìnnà sí ilé ayé ni pé nígbà kan, obìnrin kan ṣe nǹkan oṣù rẹ̀ tán, ó sì fi nu ojú sánmọ̀ tí wọ́n gbà gẹ́gẹ́ bí ojú Ọlọ́run nígbà náà. Èyí bí Ọlọ́run nínu¸Ó sì ká sánmọ̀ jìnnà sókè.

Ìtàn atẹnudétí mìíràn sọ pé ńṣe ni àwọn ènìyàn máa ń fi odó lu ojú ọ̀run (sánmọ̀) nígbà tí wọ́n bá ń gúnyán, bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìíràn máa ń fi ọwọ́ nu àwọ̀sánmọ̀ lẹ́yìn tí wọ́n bá jẹun tán, èyí tí ó bí Olódùmarè nínú, tí ó sì fa sánmọ̀ sókè. Ìtàn àtẹnudétí/ìgbà mìíràn sọ fún wa pé ọba ìsáláyé(ilé ayé) àti ọba ìsàlú ọ̀run máa ń ṣe àṣepọ̀ ní ìgbà ìwásẹ̀ ṣùgbọ́n a fi yé wa pé ọba ìsálú ọ̀run tóbi, Ó sì ga ju ọba ayé lọ. Bí àpẹẹrẹ, nínú Odù Ifá Ọ̀sẹ́ méjì, a fi yé wa pé ọba ìsàlú ọ̀run àti ọba ìsálayé jùmọ̀ dẹgbẹ́ lọ ní ọjọ́ kan. Wọ́n pa eku ẹmọ́ kan tí ó dá ìjà sílẹ̀ láàrin wọn. Báyìí ni ọba ìsàlú ọ̀rún bínú padà sí ọ̀run tí nǹkan kò sì rọgbọ nínú ayé mọ́. Èyí fi hàn pé Yorùbá gbàgbọ́ nínú títóbi Ọlọ́run àti pé Ó tóbi ju ọba ayé lọ.

## 4.3 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Awo àti Ìmùlẹ̀:

Àwọn Ẹgbẹ́ awo pọ̀ díẹ̀ láàrin àwọn Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní pàápàá. Bí a bá fi ojú léréfèé wo ohun tí a ń pè ní awo, a ó rí i pé gbogbo ohun tí a kò bá fẹ́ fi àṣírí rẹ̀ síta ni awo. Nítorí náà, bí awo ṣe wà ní Lìkì, bẹ́ẹ̀ ló wà ní Gbàǹja. Awo àti ìmùlẹ̀ máa ń wà nínú ẹ̀sìn. Bí a ṣe ń rí awo Ifá, orò, Egúngún, Ògbóni, Ọ̀ṣùgbó, Emèrè, Àbíkú, Agẹmọ bẹ́ẹ̀ ni a ń rí awo nínú iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá gbogbo. Èyí ń wáyé nítorí kò sí adìẹ tí ó fẹ́ fi ibi kòkòrò han ọmọ rẹ̀. Kódà, nínú iṣẹ́ Ifá dídá, babaláwo ni a máa ń pe àwọn tí ń dáfá. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe gbọ́, tí a sì kà nínú àkọsílẹ̀ àwọn òǹkọ̀wé nípa àṣà Yorùbá (Ladele, et al, 2006:81), àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá jẹ́ awo nítorí pé a kò fẹ́ kí ẹni tí kò kọ́ irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ mọ bí a ti ń ṣe é.

## 4.4 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Orí:

Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa 'Orí' tàbí 'Àyànmọ́', oríṣìíríṣìí àríyànjiyàn ni ó máa ń wáyé. Ṣùgbọ́n a lè sọ pàtó pé ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn òrìṣà tí àwọn Yorùbá máa ń bọ ni Orí jẹ́. Orí yìí náà ni a máa ń pè ní àyànmọ́ tàbí ìpín. Òun yìí kan náà ni wọ́n máa ń pè ní àkúnlẹ̀yàn.
Àwọn Yorùbá gba Orí gẹ́gẹ́ bí ẹlẹ́dàá wọn. Wọ́n gbàgbọ́ pé orí méjì ni ó wà. Èkínní ni orí inú bẹ́ẹ̀ ni èkejì ni orí ìta tí à ń gbé kiri yìí. Wọ́n gbà pé orí ni alákòó gbogbo ara àti pé orí ni gbogbo oríkèéríkèé ara so mọ́. Àwọn oníṣègùn òyìnbó gan-an gbà pé bí ìjàm̀bá bá tilẹ̀ ṣe gbogbo ẹ̀yà ara yòókù, tí nǹkan kan kò bá bá orí, ènìyàn kò tí ì le kú. Ṣùgbọ́n nígbà tí ìdágìrì bá ti bá orí, gbogbo ẹ̀yà ara yòókù kò wúlò mọ́.
Yorùbá gbàgbọ́ pé oríṣìí orí inú méjì ló wà – orí rere àti orí burúkú àti pé yíyàn ni olúkálukú yan orí tirẹ̀ láti òde ọ̀run. Wọ́n gbà pé bí ènìyàn yóò ṣe jẹ́ láyé àti ohun tí yóò dà wà lọ́wọ́ orí tí ó bá yàn láti ọ̀run ni. Nígbà tí àwọn ẹlòmíràn yan owó rẹpẹtẹ àti àlàáfíà, òsì ni ẹlòmíràn yàn ní tirẹ̀. Bí ẹnìkan bá lówó lójijì tàbí tí ẹnìkan sàdédé fò sánlẹ̀, tí ó sì kú ní rèwerèwe, wọn yóò sọ pé àyànmọ́ rẹ̀ ni. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń sọ pé,
A ti kúnlẹ̀, a ti yànpín
A délé ayé tán lojú ń kán wa.
Odù Ifá Ogbègùndá ni ó sọ fún wa pé láti ọ̀run ni oníkálukú ti yan orí rẹ̀ wá sí ayé, bóyá orí rere ni, tàbí búburú. Ṣùgbọ́n ohun tí ó yanilẹ́nu ni pé ní kété tí ẹ̀dá ènìyàn bá ti kúrò ní ìsàlú ọ̀run tán ni yóò ti gbàgbé irúfẹ́ orí tí ó yàn. Wàyí ó, bí a bá fẹ́ irú orí tí a yàn lọ́run, lọ́dọ̀ Ifá ni a ó lọ nítorí òun ni 'Ẹlẹ́rìí-Ìpín', tí ó wà níbẹ̀ nígbà tí ọmọ ènìyàn ń yan orí lọ́run lọ́hùn-ún.

## 4.5 Ìgbàgbọ́ Nípa Àwọn Aláṣekù tàbí Ìbọ:

Àwọn tí a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí Aláṣekù ni àwọn baba àti àwọn ìyá wa ti wọ́n ti fi ilẹ̀ bora. Àwọn wọ̀nyí ni àwọn tí wọ́n ti dògbó tàbí di arúgbọ́ kùjọ́kùjọ́ kí wọ́n to ta téru nípàá.
Àwọn Yorùbá máa ń ṣe ètùtù fún àwọn àgbà báyìí tí wọ́n ti kúrò láàrin wọn. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé àwọn aláṣekù wọ̀nyí sì máa ń bójútó àlàáfíà àti ìgbáyégbádùn àwọn ọmọ tí wọ́n fi sílẹ̀ sí ayé lọ, pàápàá àwọn ọmọ tí ó bá ń ṣe ohun dáradára tí wọ́n fẹ́.
Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹnìkọ̀ọ̀kan àti ìdílé ní láti máa ṣe ìrántí àwọn aláṣekù wọ̀nyí, kí wọ́n sì máa bọ wọ́n lóòrèkóòrè. Ìdí nìyí tí a fi máa ń tọ́ka sí àwọn aláṣekù wọ̀nyí bí Ìbọ. Ẹnikẹ́ni tí ó bá tàpá sí ìfẹ́-inú àwọn aláṣekù yìí máa ń rí funfun ojú wọn. Èyí ni pé wọ́n máa ń bínú sí irú ènìyàn bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, nínú Odù Ifá Ogbègùndá, a rí ìtàn ọkùnrin kan, ẹni tí ń jẹ́ Oyèpolú, tí ó fi àìmọ̀kànmọ̀kàn tàpá sí àwọn Ìbọ, tí ó sì rí ìbínú wọn (Abimbọla, W. 19….). Nítorí ìdí èyí, àwọn baba àti ìyá àwọn ì tí ó ti kú máa ń ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ìdílé tàbí ẹbí tí wọ́n ti jáde kúrò.

## 5.0 Ìsọnísókí

Nínú ìpín karùn-ún, módùlù kìnní yìí ni o ti kà nípa èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá irú ẹni tí Olódùmarè jẹ́. A mẹ́nuba bí Olódùmarè yìí ti sẹ̀dá ayé àti ọ̀run ni ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ nígbà tí a tún wo àwọn Ẹgbẹ́ Awo àti Ìmùlẹ̀ ṣíṣe, èyí tí ó wọ́pọ̀ láàrin

Yorùbá láti ìgbàanì títí di òní olónìí. A fi ìṣe pàtàkì ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Orí hàn, bẹ́ẹ̀ ni a kò sàìṣe àlàyé ìgbàgbọ́ wọn nípa àwọn Aláṣekù.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Ẹlẹ́dàá àti àwọn ẹ̀dá Rẹ̀
2. "Ayé lọjà, Ọ̀run nilé". Dá sí ọ̀rọ̀ yìí
3. Sọ ohun tí o mọ̀ nípa ẹgbẹ́ awo kan ní ilẹ̀ Yorùbá
4. Báwo ni àwọn Aláṣekù ṣe máa ń ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹbí àti ìdílé wọn tó ń bẹ láyé?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Ladele, T.A.A. et. Al 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ibadan, Gavima Press Ltd.

Ojo, G.A 1966. *Yorùbá Culture.* London, University of London Press.

Ọlajubu, O. 1975. *Ìwé Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn, Longman.

Daramọla, O. & Jẹjẹ, A. 1968. *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ibadan, Oníbọn-Òjé Press &

Book Industries (Nig) Ltd.

# MÓDÙ KEJÌ: ÀṢÀ ÀTI ỌDÚN ÌBÍLẸ̀ YORÙBÁ

**Ìfáàrà:**

Níbí yìí ni o ó ti kà àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá, tí a ó sì ṣe àlàyé bí àwọn ẹ̀ka àṣà náà ti rí nínú ìdàgbàsókè àti mú àlàáfíà bá àwọn àwùjọ yìí. Bákan náà, a ó wo èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá, èyí tí àyíká wọn máa ń tọ́ka sí ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, bẹ́ẹ̀ ni a ṣe àfihàn bí èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá ṣe ṣúyọ nínú ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn.
Nípa báyìí, a mọ̀ nípa bí àṣà àti ẹ̀sìn àwọn ènìyàn yìí ṣe mú ìgbéga àti ìdàgbàsókè bá àwùjọ Yorùbá àti pé a tọ́ka sí àwọn kùdìẹ̀kudiẹ tí ó ṣúyọ.

## ÌPÍN KÌNNÍ: ÀWỌN Ẹ̀KA ÀṢÀ YORÙBÁ 1

1.0 **Ìfáàrà**:

Àṣà Yorùbá gbòòrò púpọ̀. Bí a ṣe ní àwọn ẹ̀ka àṣà tí ó kéré ni a ní àwọn ẹ̀ka ńláńlá. Bí a bá tilẹ̀ ní kí á sọ ìtumọ̀ àṣà, a ó rí i pé ìtumọ̀ yìí pín sí oríṣìíríṣìí. Bí a ti ri àṣà aṣọ wíwọ̀ bẹ́ẹ̀ ni a rí àṣà oge ṣíṣe láàrin àwọn Yorùbá. Àwọn ẹ̀ka àṣà yìí pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí a kò le mẹ́nubà gbogbo wọn lẹ́ẹ̀kan náà. Ṣùgbọ́n nínú ìpín yìí ni a ti ṣe àlàyé nípa ohun tí àṣà jẹ́ tí a sì wo àwọn àṣà Yorùbá kan bí àṣà ìkíni, ìwọṣọ, oge ṣíṣe àti ilà kíkọ.

2.0 **Èròǹgbà/Àfojúsùn**

Nínú ìpín yìí ni o ó ti:

- mọ̀ pé àṣà gbòòrò púpọ̀
- mọ ẹ̀ka pàtàkì kan nínú àwùjọ Yorùbá
- Ṣàlàyé irúfẹ́ àwọn ìtumọ̀ tí a ń fún àṣà
- mọ àṣà ìkíni àti pàtàkì rẹ̀ láàrin àwùjọ Yorùbá
- ní òye nípa àṣà ìwọṣọ, oge ṣíṣe àti àṣà ilà kíkọ ní àwùjọ Yorùbá.

3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Kín ni àǹfààní àti àléébù tí ó wà nípa kíkọ ilà ojú?
2. Dárúkọ àwọn ọ̀nà tí tọkùnrin tobìnrin ń gbà ṣoge lóde òní.

**4.0 Ìbéèrè Ìsaájú**

**4.1 <u>Kín ni Àṣà</u>?**

A lè sọ pé nígbà tí Ẹlẹ́dàá tàbí Olódùmarè dá ẹ̀dá ènìyàn ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, ó dá àwọn kan sínú igbó, ó dá àwọn mìíràn sílẹ̀ ọ̀dàn, Ó dá àwọn kan sínú aṣálẹ̀, Ó dá àwọn kan sí etí odò ńlá àti òkun, bẹ́ẹ̀ ni Ó dá àwọn kan sí agbègbè tí kò sí igbó tàbí ọ̀dàn rárá.

Nígbà tí àwon ẹdá ènìyàn wo àyíká wọn, wọ́n ṣe àkíyèsí àwọn nǹkan tí ó lè ṣe àwọn ní àǹfààní, tí yóò sì wúlò fún ìwàláàyè wọn. Yàtọ̀ sí èyí, wọ́n ṣe àkíyèsí pé àwọn nǹkan kan wà tí ó léwu fún wọn láti mú lò tí kò sì ṣe é súnmọ́. Nítorí náà, ẹ̀dá ènìyàn, nínú ìrírí rẹ̀, bẹ̀rẹ̀ sí i sa àwọn nǹkan tí ó lè wúlò fún un fún ìmúlò rẹ̀. Èyí ni ó di àṣà fún un, tí ó sì ń mú lò. Ìdí nìyí tí àṣà fi yàtọ̀ láti agbègbè

kan sí èkejì. Nítorí náà, àṣà ni a lè pè ní ọgbọ́n, ìmọ̀, ìrírí àti òye àwọn ènìyàn àwùjọ kan, èyí tí wọ́n máa ń mú lò fún ìwàláàyè àti ìdàgbàsókè àwùjọ ẹ̀dá ènìyàn.

## 4.2 Àṣà Ìkíni:

Àṣà yìí ṣe pàtàkì láàrin àwùjọ Yorùbá láyé àtijọ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àṣà náà kò fìdí múlẹ̀ mọ́ ní òde òní nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́ ìgbà yìí ni kò mọ bí a ṣe ń kínni mọ́.
Gẹ́gẹ́ bí àwọn òǹkọ̀wé àṣà Yorùbá kan (Ladele, et al 1986:89) ṣe sọ, Yorùbá gbádùn ènìyàn kíkí, bẹ́ẹ̀ wọ́n gbà pé ẹnikẹ́ni tàbí ọmọkọ́mọ tí kò bá mọ̀ bí ati máaa ń kí ènìyàn jẹ́ ẹni tí kò ní ẹ̀kọ́ ilé. Gẹ́gẹ́ bí àwọn òǹkọ̀wé yìí ṣe sọ, nígbà tí àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun dé sí àwùjọ Yorùbá, àṣà ìkíni yìí wù wọ́n púpọ̀ nítorí pé wọ́n mọ̀ pé ohun tí ó wuyì ni ìrẹ̀lẹ̀, ọ̀wọ̀ àti ìtẹríba.
Kò sí ohun tí àwọn Yorùbá kò ní ìkíni fún. Bí a bá jí láàárọ̀, àwọn ọmọdékùnrin yóò dọ̀bálẹ̀ kí àwọn bàbá àti ìyá wọn àti gbogbo àwọn tí ó bá dàgbà jù wọ́n lọ. Bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin yóò kúnlẹ̀ kí àwọn baba àti ìyá pẹ̀lú àwọn àgbà àwùjọ mìíràn. Ṣùgbọ́n ó tini lójú jọjọ pé àṣà yìí kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ mọ́ nítorí ọ̀làjú ilẹ̀ òkèèrè tí ó dé sí àwùjọ wa.

## 4.3 Àṣà Ìwọṣọ:

Àṣà ìwọṣọ jẹ́ ẹ̀kọ́ àṣà pàtàkì mìíràn tí a fi máa ń dá àwọn Yorùbá mọ̀. Oríṣìíríìṣìí aṣọ tí ó jẹ mọ́ ilẹ̀ olóoru ni wọ́n máa ń wọ̀. Àwọn ọkùnrin wọn máa ń wọ ẹ̀wù agbádá, bùbá, Dáńsíkí, sùlíá, dàńdógó, Ọ̀yàlà, Gbárìyẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin máa ń ró ìró àti bùbá.
Àwọn ọkùnrin Yorùbá máa ń dé oríṣìíríṣìí fìlà sí aṣọ wọn. Wọ́n kò gbà pé ọmọlúàbí ni ènìyàn bí kò bá tí ì dé fìlà sí orí aṣọ tí ó bá wọ̀
Àwọn obìnrin máa ń lo Tòbí tàbí Ìlábùrù, Aṣọ ìró àti bùbá, pẹ̀lú ìborùn. Nígbà tí àwọn obìnrin bá múra tán báyìí, wọ́n máa ń fi ẹ̀gbà sí ọwọ́, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń fi òrùka sí ìka ọwọ́ wọn.

## 4.4 Àṣà Oge Ṣíṣe:

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "kò síbi tí a kò í tí kádìẹ alẹ́" ni ọ̀rọ̀ oge ṣíṣe jẹ́ láàrin àwùjọ àgbáyé. Bi ó ṣe wà ní Lìkì, bẹ́ẹ̀ náà ló wà ní Gbàǹja ni ọ̀rọ̀ oge ṣíṣe jẹ́. Bí ó sì ti wà ní àtètèkọ́ṣe, bẹ́ẹ̀ ni ó wà nísinsinyìí, ó dájú pé bẹ́ẹ̀ ni yóò máa wà títí ayérayé. Oge ṣíṣe yìí bẹ̀rẹ̀ láti orí, bẹ́ẹ̀ ni ṣíṣe orí lóge ṣe pàtàkì jù lọ bí a bá wo àgọ́ ara wa yòókù. Ṣíṣe orí lọ́ṣọ̀ọ́ ṣe pàtàkì jù láàrin àwọn obìnrin bóyá nítorí ìṣẹ̀dá tàbí rọ́wọ́ráyè wọn ló fa èyí (Mustafa, B., 1975). Gẹ́gẹ́ bí Mustafa (1975) ṣe sọ, àwọn obìnrin ni ó máa ń ṣe oge jù, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọkùnrin mìíràn wà tí wọ́n gbọ́ fáàrí púpọ̀. Ṣùgbọ́n sá o, oge ṣíṣe bẹ̀rẹ̀ láti irun orí, títí dé èékánná ẹsẹ̀.
Àwọn obìnrin máà ń di irun orí wọn, èyí tí ó ní oríṣìíríṣìí orúkọ bíi, ṣùkú, onídodo, kòlésẹ̀, ìpàkọ́ ẹlẹ́dẹ̀, kojúsọ́kọ,kọ̀ǹkọ̀sọ̀ àti alágògo. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọkùnrin kì í di irun wọn bí i tí àwọn obìnrin, àwọn ọkùnrin náà máa ń fá irun orí wọn bí ó bá ti kún díẹ̀, tí orí wọn yóò sì máa dán kooroko.
Oríṣìí ọ̀nà mẹ́tà ni àwọn obìnrin máa ń fi irun dídì dá gẹ́gẹ́ bí a ti dárúkọ àwọn irun tí wọ́n máa ń dì bí i Ṣùkú, Pàtẹ́wọ́, Kòlẹ́sẹ̀, Ọkọ-ń-lọ ọkọ-ń-bọ̀, Maforíbalẹ̀ fọ́kọ, Òjò Má petí, Ìpàkọ́ Ẹlẹ́dẹ̀, Korobá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn obìnrin ni wọ́n máa ń di irun orí wọn, àwọn ọkùnrin tí wọ́n máa ń di irun orí

wọn ni àwọn oníṣàngó, ọ́dẹ àti àwọn olòrìṣà, mìíràn ní ilẹ̀ Yorùbá. Lóde òní, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pe àṣà irun dídì láàrin àwọn obìnrin kò wọ́pọ̀ mọ́, àwọn àgbà obìnrin ni àṣà yìí tún kù sí lọ́wọ́. Àwọn ọ̀dọ́mọ̀bìnrin àti àwọn ọ̀sọ́ọ́rọ́ abilẹ́kọ ti bẹ̀rẹ̀ sí i gba àṣà àjèjì nípa jíjó irun níná tàbí kí wọ́n máa lo wíìgì, kí wọ́n le dà bí àwọn aláwọ̀ funfun.
Àwọn obìnrin tún máa ń lu etí wọn láti fi yẹrí etí ṣe ara lọ́sọ̀ọ́, ṣùgbọ́n àwọn obìnrin kan kò fi yẹrí sí etí wọn mọ́ nípa ẹ̀sìn àjòjì tí wọ́n gbà.

## 4.5 Àṣà Ilà Kíkọ:

Oríṣìíríṣìí ìdí ni àwọn Yorùbá fi máa ń kọ ilà ojú àti ti ara láyé àtijọ́. Lọ́nà kìn-ínní, àwọn baba-ńlá wa máa ń kọ ilà fún ọmọ wọn, ìbáà jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin nítorí ogun tí ó wọ́pọ̀ ní ayé ìgbàanì. Lákòókò náà, ọmọ máa ń sọnù láìròtẹ́lẹ̀ nítorí pé àwọn alágbára máa ń kó àwọn ọmọ ẹni tí kò lágbára bíi tiwọn tà bí ẹrú fún àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun. Nítorí náà, wọ́n máa ń kọ ilà fún àwọn ọmọdé láti fi ṣe àmì èyí tí wọn yóò fi le dá ẹni tiwọn mọ̀ bí wọ́n bá rìnnà pàdé wọn níbì kan.
Lọ́nà kejì, àwọn baba-ńlá Yorùbá gbà pé ilà wọ̀nyí máa bùkún ẹwà ara wọn. Bí a bá wo ẹlòmíràn tí wọ́n kọlà fún báyìí, ilà sábà máa ń buyì kún ẹwà wọn. Wàyí o, àwọn ẹ̀yà Yorùbá kọ̀ọ̀kan ni irúfẹ́ ilà tí a fi máa ń dá wọn mọ̀. Àwọn Ọ̀yọ́ ni wọ́n máa ń kọ ilà bíi Àbàjà, Pélé, Túre, Kẹ́kẹ́, Gọ̀ǹbọ̀. Láàrin àwọn Ẹ̀gbá ni a ti máa ń rí ilà mẹ́ta mẹ́ta tí kì í gùn púpọ̀ bẹ́ẹ̀ ni àwọn Ìjẹ̀sà náà máa ń kọ ilà mẹ́fà. Àwọn Òǹdó máa ń fa ilà kọ̀ọ̀kan wálẹ̀ ojú wọn.
Àṣà ilà kíkọ yìí kò wọ́pọ̀ láàrin àwọn Yorùbá lóde òní, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìdílé mìíràn máa ń kọ àwọn àkọbí ọmọ wọn ní ilà ìdílé wọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí:

Àṣà jẹ́ ohun tí ó gbòòrò púpọ̀. Ó jẹ mọ́, ìrírí, ìmọ̀, ọgbọ́n àti òye àwọn ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣúyọ ní àyíká wọn. Nínú ìpín yìí ni a ti ṣe àlàyé ohun tí àṣà túmọ̀sí àti bí ó ti ṣe pàtàkì sí ní àwùjọ Yorùbá.
A wo àṣà ìkíni ní àwùjọ Yorùbá àti bí ẹ̀ka àṣà yìí ti ṣe pàtàkì tó àti bí àwọn èwe òde-òní kò ti ṣe mú àṣà yìí lò mọ́ nítorí àṣà ìwé kíkọ àti ọ̀làjú tí ó dé àwùjọ. Bákan náà, àṣà ìwọṣọ àtijọ́ ti ń káṣẹ̀ nílẹ̀ nítorí pé àwọn ọmọdé ìwòyí kò gba ti aṣọ bíi gbárìyẹ̀, ọ̀yàlà, dánsíkí àti dàńdógó mọ́.
Dípò èyí, aṣọ àwọn òyìnbó bíi kóòtù àti ṣẹ́ẹ̀tì ni ó wọ́pọ̀ láàrin wọn. Àṣà oge ṣíṣe lọ́nà ti ìṣẹ̀nbáyé kò tilẹ̀ wuyì láàrin èwe àti ọ̀dọ́ ìwòyí mọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n ń ṣe oge lọ́nà tí ọ̀làjú mú wá. Dípò irun dídì, àwọn ọ̀dọ́bìnrin ìwòyí máa ń lo wíìgì òyìnbó láti fi mú wọn dàbí ìran òyìnbó bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àbùdá àti ìrísí wọn kò fi wọ́n hàn bí ìran òyìnbó.
Ní ìparí ìpín yìí ni a ti wo àṣà ilà kíkọ àti ìdí tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń kọlà láyé àtijọ́. A ṣe àlàyé onírúurú ilà tí Yorùbá máa ń kọ àti pé àṣà yìí kò tilẹ̀ wọ́pọ̀ mọ́ ní àwùjọ Yorùbá.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe:

1. Kínní o lè sọ nípa ìtumọ̀ àṣà àti bí èyí ṣe ṣúyọ nínú àwọn ẹ̀ka àṣà Yorùbá?
2. Ṣàlàyé kíkún tí ó dé bá àṣà ìkíni láàrin àwọn Yorùbá lóde òní. Ọ̀nà wo ni a lè gbà ṣe àtúnṣe?
3. Àwọn Ọ̀nà wo ni Yorùbá máa ń gbà ṣoge láyé àtijọ́ àti lóde òní?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Oladele, T.A.A. et al 1986. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn, Gavima Press Ltd.

Ológundudu, D. 2008. *The Cradle of Yorùbá Culture.* U.S.A Center for spoken words/Institute of Yorùbá culture.

Ojo, J.A 1966. *Yorùbá Culture.* London, University of London Press.

Mustafa, B. 1995. "Óge Síṣe Ní Ilẹ̀ Yorùbá" in Ọlajubu, O. (ed). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ibadan, Longman.

**MÓDÙ KEJÌ**

**ÌPÍN KEJÌ: ÀWỌN ẸKA ÀṢÀ ÌBÍLẸ̀ YORÙBÁ 2**

Àkóónú:

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
1.1 Àṣà Ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́
1.2 Ogún Pípín
1.3 Ìsìnkú àti Òkú Ṣíṣe
1.4 Ìgbéyàwó
1.5 Ìsọmọlórúkọ
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà:

Nínú ìpín kejì yìí ni o ó ti tẹ̀síwájú láti wo àwọn ẹ̀ka àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá mìíràn bí àṣà ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́, Ogún pípín, ìsìnkú àti òkú ṣíṣe, ìgbéyàwó àti ìsọmọlórúkọ. A rí i pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìyípadà ni ó ti wà nínú àṣà yìí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a wo ìṣẹ̀dálẹ̀ wọn àti àwọn nǹkan tí ọ̀làjú òde òní ti mú bá àwọn ẹ̀ka àṣà bẹ́ẹ̀. Àlàyé wà lórí àtúbọ̀tán àwọn ẹ̀ka àṣà yìí nítorí àṣà kò dúró ní ojúkan, yíyí ló ń yí padà.

## 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Èròǹgbà àti àfojúsùn inú ìpín yìí ni láti jẹ́ kí o:

- Mọ̀ bí àwọn Yorùbá ṣe máa ń ran ara wọn lọ́wọ́ láyé àtijọ́
- Ṣàlàyé bí àwọn Yorùbá ṣe máa ń pín ogún wọn láyé àtijọ́
- Mọ àwọn ìyípadà tí ó dé bá àwọn ẹ̀ka àṣà yìí lóde òní
- Fi pàtàkì àṣà ìgbéyàwó hàn àti àwọn àṣáwọ̀ tí ó dé bá a lónìí
- Mọ àṣà ìsọmọlórúkọ àti àwọn ìyípadà tí ó ti rọ̀ mọ́ ọn lóde-òní

## 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Àwọn ọ̀nà wo ni wọ́n fi ń ran ara-ẹni lọ́wọ́ ní agbègbè rẹ̀?
2. Ọ̀nà wo ni a ń gbà sìnkú ní agbègbè rẹ?
3. Sọ àwọn ọ̀nà tí a ń gbà pín ogún lóde òní.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́:

### 4.1 Àṣà Ìran-ara-ẹni-lọ́wọ́:

Àṣà yìí ṣe pàtàkì ní àarìn àwọn Yorùbá láyé àtijọ́, bẹ́ẹ̀ ni bí ó ṣe wà ní àtètèkọ́ṣe, bẹ́ẹ̀ ni ó ń rí nísinsinyìí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn àyípadà díẹ̀díẹ̀ kan ti wọnú àṣà yìí. Ọ̀kan nínú ara àṣà ìranra-ẹni-lọ́wọ́ ní àtijọ́ ni ààró. Èyí ni ìgbà tí ẹni méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ bá ń bá ara wọn ṣiṣẹ́ ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀le nínú oko ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn.

Lóòótọ́ ni ọ̀wẹ̀ náà jẹ mọ́ ṣe-fún-mi-nṣe-fún-ọ ṣùgbọ́n kì í ṣe lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ bí i ti àáró. Yàtọ̀ sí àáró yìí, ọ̀nà mìíràn tí àwọn Yorùbá máa ń gbà ni ọ̀wẹ̀. Ọ̀wẹ̀ máa ń ní oúnjẹ rẹpẹtẹ nínú, bẹ́ẹ̀ ni ènìyàn sábà máa ń pọ̀ níbi ọ̀wẹ̀ ju ibi àáró lọ. A lè bẹ ọ̀wẹ̀ kọ́ ilé, a le bẹ ọ̀wẹ̀ ká kòkó tàbí kí á bẹ ọ̀wẹ̀ sán oko, bẹ́ẹ̀ ni a le bẹ ọ̀wẹ̀ kọ ebè oko. Àwọn ọdẹ máa ń bẹ ara wọn lọ́wẹ̀ láti pa ẹran, yálà fún ọdún ọba tàbí kí ẹnìkan nínú wọn fẹ́ ṣe nǹkankan. Ọ̀wẹ̀ bíbẹ̀ kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ mọ́ ní òde-òní.
**Àjọ**: Àwọn Yorùbá tún máa ń ran ara wọn lọ́wọ́ nípa dídá àjọ láàrin ara wọn. Nípa báyìí, wọ́n yóò kó ara wọn jọ, wọn yóò sì fi ẹnìkan ṣe olórí, bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò máa fi owó pamọ́ díẹ̀díẹ̀ tàbí kí wọ́n máa dá owó jọ, kí wọ́n sì máa kó o fún ẹni tí ó bá kàn tí yóò kó o. A rí i pé àjọ dídá sí tún wà lóde òní, pàápàá jù lọ láàrin àwọn oníwóróbo tàbí àwọn onísòwò.
Ọ̀nà mìíràn tí a tún lè mẹ́nubà ni Èsúsú tàbí Èésú, èyí tí ó fara pẹ́ àjọ, ṣùgbọ́n oko kì í jẹ́ ti baba tọmọ kó má ní ààlà. A lè fi èsúsú wé ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù tí wọ́n ń ṣe nísinsinyí.

## 4.2 <u>Ogún Pípín:</u>

Ogún Jíjẹ ṣe pàtàkì láàrin àwọn Yorùbá. Bí òkú bá ti kú tán, ojọ́ díẹ̀ lẹ́yìn ikú olóògbé ni àwọn ẹbí rẹ̀ yóò pín ogún ìní rẹ̀ fún àwọn tí ogún náà bá tọ́ sí. Wọ́n yóò pín gbogbo dúkìá-ohun èlò, ohun ọ̀sìn, oko, ilẹ̀, ilé, títí kan àwọn ìyàwó olóògbé náà pẹ̀lú. Lóde òní, ọ̀nà tí wọ́n ń gbà pín ogún ti yàtọ̀ díẹ̀ níwọ̀n bí ọ̀làjú ti dorí àṣà yìí kodò.

## 4.3 <u>Ìsìnkú àti Òkú Ṣíṣe</u>:

Òkú sísin jẹ́ àṣà ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀rọ̀ ikú máa ń mú ẹkún òun ọ̀ṣe lọ́wọ́, Yorùbá máa ń sin òkú àgbàlagbà pẹ̀lú ìlù, orin àti ijó nítorí wọ́n gbàgbọ́ pé sísin òkú yìí pẹ̀lú àríyá tí ó yẹ ni yóò mú kí òkú náà tètè dé ọ̀dọ̀ àwọn baba rẹ̀ lọ́run lọ́hùn-ún àti pé láìṣe ayẹyẹ yìí, àwọn oníbodè ọ̀run kò ní i gba òkú bẹ́ẹ̀ láàyè láti kọjá lọ simi lọ́run, bẹ́ẹ̀ ni kò ní í lè padà wá sí ayé mọ́ ní àwọ̀ ènìyàn. Lóde òní, ayẹyẹ fún ìsìnkú sì máa ń lárinrin ní ọ̀pọ̀ ìgbà nítorí wọ́n gbàgbọ́ pé ọ̀wọ̀ àti ìrántí ìkẹyìn tí wọ́n yóò fún ẹni náà nìyí.

## 4.4 <u>Ìgbéyàwó:</u>

Àṣà ìgbéyàwó jẹ́ ohun ayọ̀ ní ìdílé ọkọ àti ti ìyàwó ní ilẹ̀ Yorùbá. Ire mẹ́ta ni ó jẹ́ Yorùbá lógún nílé ayé – ìre owó, ire ọmọ àti ire àìkú-parí-ìwà. Yorùbá gbàgbọ́ pé nípasẹ̀ ọmọ, àìkú lè wáyé. Ìyẹn ni pé ẹni tí ó bá bímọ, kò le kú láéláé. Ṣùgbọ́n bí kò bá sí ìyàwó, ọmọ kò le wáyé. Nítorí náà, oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni Yorùbá ń gbà fẹ́ obìnrin (ìyàwó).
Lọ́nà kínní, wọ́n le fẹ́ oyún inú fún oyun inú, lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, wọ́n le fẹ́ oyún inú fún ọmọ ọwọ́. Ní ọ̀nà kẹta, àwọn ọmọbìnrin àti ọmọkùnrin lè rí ara wọn láti ìta, kí wọ́n sì gbà láti fẹ́ ara wọn. Lọ́nà mìíràn, wọ́n lè bá ọmọkùnrin rí ọmọbìnrin, kí wọ́n sì bá a sọ̀rọ̀ rẹ̀. Ẹni tí ó máa ń wà láàrin wọn ni a ń pè ní alárenà. Ní ìlànà karùn-ún, ọkùnrin lè gba ìyàwó ti ọmọkùnrin mìíràn ń fẹ́ lọ́wọ́ ṣùgbọ́n tí kò tí ì dé ilé rẹ̀. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, wọ́n lè gba obìnrin tí ó ti bímọ sílé ọkọ. Ní ìparí, a lè fẹ́ ìyàwó nípasẹ̀ opó sísú. Bí baba bá kú, àkọ́bí baba tí ó bá ti bàlágà lè ṣúpò ìyàwó kékeré. Bí kò bá sí ọmọkùnrin tí ó bàlágà, àbúrò baba lè jogún ìyàwó náà. Nígbà ìwáṣẹ̀, ó pọn dandan kí ọkùnrin gbé ìyàwó, kí obìnrin sì lọ sí ilé ọkọ. Nítorí náà, ọkùnrin tàbí obìnrin tí ó bá ti bàlágà tí kò tí ì ni ìyàwó tàbí ọkọ

àfẹsọ̀nà ni wọn yóò máa bi léèrè pé, bá wo ló ṣe jẹ́. Ọkùnrin ni ó máa ń kọnu sí obìnrin láti fẹ́, bóyá nítorí pé àwọn ọkùnrin máa ń pọ̀ jù obìnrin lọ nígbà náà yàtọ̀ sí òde-òní tí àwọn obìnrin pọ̀ jáǹtírẹrẹ ju ọkùnrin lọ.
Kí àwọn Yorùbá tó fẹ́ obìnrin tàbí ọkùnrin láyé ìgbàanì, wọn yóò kọ́kọ́ bèèrè lọ́wọ́ Ifá, bẹ́ẹ̀ ni alárenà yóò bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ni pẹrẹu. Ọkọ àfẹ́sọ̀ná yóò sanwó ìsíhùn owó ìjọ́hẹn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ìdílé ọkọ yóò lọ dána ni ìdílé ìyàwó; bẹ́ẹ̀ ni lẹ́yìn ìdáná yìí ni ìalẹmọ́ ọjọ́ ayẹyẹ ìgbéyàwó yóò bẹ̀rẹ̀.
Bí ọkùnrin ṣe n palẹ̀mọ́, bẹ́ẹ̀ náà ni ìyàwó rẹ̀ yóò máa palẹ̀mọ́ fún ọjọ́ ayẹyẹ náà. Bí ó bá wá di ọjọ́ ayẹyẹ ìgbéyàwó, àwọn obìnrin ilé ọkọ yóò lọ sí ilé ìyàwó láti lọ gba ìyàwó wọn, bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin ilé ìyàwó ni yóò sin ìyàwó náà lọ sí ilé ọkọ rẹ̀ ní ọwọ́ ìrọ̀lẹ́.

## 4.5 <u>Ìsọmọlórúkọ:</u>

Kí á tó bí ọmọ ni bàbá rẹ̀ àgbà yóò ti máa rò irú orúkọ tí yóò sọ ọmọ náà, ìbáà ṣe ọkùnrin tàbí obìnrin ni ọmọ náà. Orúkọ tí a sábà máa ń sọ irú ọmọ bẹ́ẹ̀ yóò jẹ mọ́ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ nínú ẹbí tàbí ìdílé ní àkókò nítorí pé ilé là á wò kí a tó sọ ọmọ lórúkọ.
Ọjọ́ kẹfà ni Yorùbá sábà máa ń sọ ọmọ lórúkọ láyé àtijọ́, bó ṣe ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin. Ṣùgbọ́n ní agbègbè mìíràn, ọjọ́ kẹsàn-án ni wọ́n máa ń sọ ọmọkùnrin lórúkọ, tí wọn yóò sì fún ọmọbìnrin ni orúkọ ní ọjọ́ kẹfà. Bí ó bá ṣe ìbejì ni, ọjọ́ kẹjọ ni wọn yóò fún wọn lórúkọ. Àwọn ìyàtọ̀ ti bá ọjọ́ yìí nítorí pé ọjọ́ kẹjọ ni wọ́n sábà máa ń sọ ọmọ lórúkọ lóde òní.

## 5.0 <u>Ìsọníṣókí:</u>

Àṣà Yorùbá wuni jọjọ, ó sì fi pàtàkì ìran yìí hàn káàkiri àgbáyé. Ó ń tọ́ka sí àwọn ìmọ̀, òye àti ọgbọ́n Yorùbá lẹ́lẹ́ka-ǹka. Ní ìbẹ̀rẹ̀ ni àwọn Yorùbá ti ṣètò ọ̀nà ìran-ra-ẹni-lọ́wọ́ ní àwùjọ wọn. Èyí máa ń mú ìfẹ́ àti àjọṣepọ̀ tí ó gúnmọ́ wà láàrin wọn. Ìlànà àti ètò ogún pípín wọn máa dáńgájíá, kì í sì í mú rògbòdìyàn lọ́wọ́. Nípa ìsìnkú àti òkú ṣíṣe wọn, àwọn Yorùbá ní ìlànà tí ó wùnilórí, bẹ́ẹ̀ ni àṣà ìgbéyàwó wọn ní ètò tí ṣe é jowú rẹ̀. Nídìí èyí, a lè fún àwọn àṣà yìí ni oríyìn tí ó yẹ wọ́n.

## 6.0 <u>Iṣẹ́ Ṣíṣe</u>:

1. Àwọn ọ̀nà wo ni Yorùbá ń gbà ran ara wọn lọ́wọ́ láyé àtijọ́ àti pé ìyípadà wo ni a lè tọ́kasí ní àkókò yìí?
2. Wo àwọn ọ̀nà tí a ń gbà fẹ́ ìyàwó láyé àtijọ́, kí o sì sọ àwọn ohun tí ó yà á sọ́tọ̀ sí tòde òní.
3. "Orúkọ ọmọ ní í ro ọmọ" Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.

## 7.0 <u>Ìwé Ìtọ́kasí:</u>

Fadipe, N.A. 1970. *The Sociology of the Yorùbá.* Ibadan, I.U.P
Ladele, T.A.A et. Al 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwàdìí ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ibadan, Gavima Press Ltd.
Ologundudu D. 2008. *The Cradle of Yorùbá Culture.* U.S.A Center for spoken words/Institute of Yorùbá culture.

Ojo, J.A. 1966. *Yorùbá culture: a Geographical Analysis.* U.K., University of London Press.

# MÓDÙ KEJÌ

## ÌPÍN KẸTA: ÀWỌN ÒRÌṢÀ ILẸ̀ YORÙBÁ

**Àkóónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Òrìṣàálá tàbí Ọbàtálá
4.2 Òrúnmìlà
4.3 Èṣù
4.4 Ṣàngó
4.5 Ògún
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 Ìfáàrà

Àwọn Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá pọ̀ díẹ̀. Ìtàn àtẹnudétí kan tilẹ̀ sọ pé ọ̀kànlénírínwó (401) ni iye wọn. A tún gbọ́ pé rírọ̀ ni àwọn irúnmọlẹ̀ wọ̀nyí rọ̀ láti òde ọ̀run wá sí ayé ní ìgbà ìwáṣẹ̀. Ifá ni ó fi èyí hàn gedegbe nínú àwọn odù rẹ̀. A mẹ́nuba àwọn òrìṣà pàtàkì kan tí a gbọ́ pé wọn rọ̀ sórí ilé ayé nígbà náà. Lára àwọn wọ̀nyí tí a mẹ́nubà ní ìpín yìí ni. Ọbàtálá tí a tún ń pè ní Òrìṣàálá, Ọ̀rúnmìlà, Èṣù, Ṣàngó, Ṣànpọ̀nná àti Ògún.
Àwọn Yorùbá gba pé àwọn òrìṣà wọ̀nyí ní iṣẹ́ ti Olódùmarè gbé lé ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn lọ́wọ́ láti máa ṣe fún ìdàgbàsókè ayé àti ìwàláàyè àwọn ẹ̀dá ènìyàn.

## 2.0 <u>Èròǹgbà/Àfojúsùn</u>

Nnínú ìpín yìí ni o ó ti:

- mọ àwọn òrìṣà Yorùbá àti iṣẹ́ wọn
- mọ àbùdá àwọn òrìṣà kọ̀ọ̀kan yìí àti ipa tí wọ́n kó nínú ìṣẹ̀dá ayé ní ìgbà ìwáṣẹ̀.
- mọ ipò tí àwọn òrìṣà wọ̀nyí tún wà ní àkókò tí ọlàjú dé yìí
- Mọ ọ̀nà tí a ń gbà sìn wọ́n ní àwùjọ Yorùbá.

## 3.0 <u>Ìbéèrè Ìsaájú</u>

1. Dárúkọ àwọn òrìṣà tí wọn ń bọ ní agbègbè rẹ
2. Kí ni iddí tí àwọn Yorùbá kì í fi í fẹ́ fi ògún búra?

## 4.0 <u>Ìdánilẹ́kọ̀ọ́:</u>

**4.1 Òrìṣàálá tàbí Ọbàtálá:** Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Òrìṣàálá àti àwọn irúnmọlẹ̀ atẹ̀wọ̀nrọ̀ yòókù ti wà pẹ̀lú Olódùmarè ní ìsàlú ọ̀run láti ìgbà ìwásẹ̀ àti pé òrìṣà yìí ni Ọlọ́run fún ní àṣẹ láti lọ tẹ Ifẹ̀-Oòdáyé dó, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Odùduwà ni ó parí iṣẹ́ náà lẹ́yìn-ọ-rẹyìn. A gbọ́ nínú ìtàn ìgbà ìwásẹ̀ kan pé Òrìṣàálá ni Ọlọ́run pàṣẹ fún láti fi amọ̀ mọ ènìyàn bí wọ́n ti rí lónìí àti pé lẹ́yìn èyí ni

Olódùmarè fi èémí sínú amọ̀ náà tí ó fi di alàààyè ọkàn. Ìdí nìyí tí a ṣe máa ń gbọ́ pé,
"Ẹni ṣojú, tí ó ṣemú, òrìṣà ni n ó máa sìn". A tún fi yé wa pé Òrìṣà-ńlá yìí ni ó dá àwọn abirùn gbogbo, pàápàá àwọn àfín, tí a sì máa ń tọ́ka sí àwọn àfin gẹ́gẹ́ bí ẹni òrìṣà tàbí ọmọ òrìṣà títí di òní olónìí. Ìtàn yìí sọ fún wa pé ẹmu tí Ọbàtálá mu yó, tí kò fi le parí iṣẹ́ ìsẹ̀dá ni ó fà á tí àwọn kan fi wà gẹ́gẹ́ bí abirùn. Ìdí sì nìyí tí àwọn abọrẹ Ọbàtálá kò fi gbọdọ̀ mu ẹmu ọ̀pẹ.

## 4.2 **Ọ̀rúnmìlà:**

Ọ̀rúnmìlà ni Yorùbá gbà pé ó jẹ́ ìríjú Olódùmarè tí ó sì wà pẹ̀lú Ọlọ́run ní ìgbà ìwásẹ̀. A sọ fún wa pé Ọ̀rúnmìlà mọ ìtàn ìṣẹ̀dá ọ̀run àti ayé, bẹ́ẹ̀ ni oun kan náà yìí wà níbẹ̀ nígbà tí Olódùmarè ń ṣẹ̀dá ènìyàn. Ìdí nìyí ti a fi máa ń tọ́ka sí Ọ̀rúnmìlà gẹ́gẹ́ bí ,
Ẹlẹ́rìí ìpín
Akéréfinúṣọgbọ́n
Akọ́nilọ́ràn bí ìyekan ẹni
Òpìtàn Ilẹ̀ẹfẹ̀
Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀ Yorùbá máa ń tọ́ka sí Ọ̀rúnmìlà gẹ́gẹ́ bí 'Ifá', bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìíràn rò pé Ọ̀rúnmìlà àti 'Ifá' jẹ́ ẹ̀dá ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá nítorí pé Yorùbá gbàgbọ́ pé Ọ̀rúnmìlà ni ọ̀kan nínú àwọn irúnmọlẹ̀ atẹwọ̀nrọ̀ tí ó rọ̀ sí ilé-Ifẹ̀ ni ìgbà ìwásẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ohun èlò Ọ̀rúnmìlà ni a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí Ifá.

**4.3 Èṣù**: Lára àwọn irúnmọlẹ̀ ọ̀kànlénírinwó tí ó rọ̀ láti ìsàlú ọ̀run wá sí ayé ni Èṣù íṣe. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ẹlòmíràn máa ń rò pé òrìṣà tí ó burú ni Èṣù jẹ́, èyí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá fún Ọ̀rúnmìlà ni Èṣù àti pé òun ni ó máa ń parí aáwọ̀ láàrin àwọn ènìyàn àti àwọn òrìṣà pẹ̀lú. Òrìṣà yìí (Èṣù) náà ni àwọn olùsìn tirẹ̀ máa ń bọ lóòrèkóòrè bẹ́ẹ̀ ni ó máa ń dáhùn ìbéèrè wọn. Èṣù yìí máa ń fún àwọn olùsìn rẹ̀ ní owó, ọmọ àti àwọn ohun mìíràn tí wọ́n bá bèèrè lọ́wọ́ rẹ̀.

**4.4 Ṣàngó:** Ṣàngó ni àwọn Yorùbá gbà pé ó jẹ́ òrìṣà tí ó máa ń fi agbára rẹ̀ hàn nípa àárá, àmọ̀mọ̀ àti ètímọ́. Wọ́n gbàgbọ́ pé bí Ṣàngó bá ń sọ̀rọ̀, iná máa ń jáde ní ẹnu àti imú rẹ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ni wọ́n bẹ̀rù Ṣàngó nítorí pé wọ́n gbàgbọ́ pé ẹnikẹ́ni tí ó bá búra èké, Ṣàngó yóò bá ẹni náa jà.
Nínú àwọn ọba aládé Yorùbá ni a tún ti máa ń gbọ́ orúkọ èyí tí ó ń jẹ́ Ṣàngó. Ìtàn sọ fún wa pé ọbạ Ṣàngó yìí ni Aláàfin kẹrin tí ó jẹ ní ìlú Ọ̀yọ́ láyé àtijọ́, tí ó sì wọlẹ̀ níbìkan tí wọ́n ń pè ni 'Kòso'. Ojúbọ ọba yìí wà ní Ọ̀yọ́ títí di òní olónìí. Àwọn àmì tí a fi máa ń dá Ṣàngó mọ̀ ni Oṣé Ṣàngó, Igbá Ṣàngó àti ìlù bàtá tí Ṣàngó máa ń jó.

**4.5 Ògún**: Ògún náà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọ̀kanlénírinwó irúnmalẹ̀ tí wọ́n rọ̀ sí òde ayé ní ìgbà ìwásẹ̀. Ògún ni òrìṣà tí àwọn ọdẹ àti àwọn tí ń lo irin máa ń bọ. Ìtàn sọ pé Ògún jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn irúnmọlẹ̀ àkọ́kọ́ tí wọ́n rọ̀ láti ọ̀run wá sí ayé ní ìgbà ìwásẹ̀ àti pé òun ni ó fi adá irin rẹ̀ yẹ ọ̀nà fún àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù láti le dé Ifẹ̀-Oòdáyé nígbà náà.
Àwọn Yorùbá bẹ̀rù Ògún púpọ̀ bẹ́ẹ̀ ni ẹnikẹ́ni tí ó bá fi àwọn irin-iṣẹ́ Ògún búra yóò rí ìjà rẹ̀. Ìdí nìyí tí a fi máa ń rí àwọn ènìyàn tí wọn kì í fẹ́ fi irin tàbí ohun tí ó bá jẹ mọ́ Ògún búra. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn kóòtù òde-òní, lẹ́yìn Bíbélì àti Kùráánì, irin Ògún ni wọ́n tún máa ń lò láti fi ṣe ìbúra, pàápàá fún àwọn ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀.

## 5.0 Ìsọnísókí

Nínú ìpín yìí ni a ti wo àwọn òrìṣà pàtàkì kan ti wọ́n gbajúmọ̀ ní àwọn Yorùbá, a sì rí i pé àwọn òrìṣà yìí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú àwùjọ yìí.
A rí i pé àwọn òrìṣà àtẹ̀wọ̀nrọ̀ wọ̀nyí kó ipa pàtàkì nínú ìbágbé àti àjọṣepọ̀ àwọn ènìyàn Yorùbá. Wọ́n ń ṣètò àwọn ọ̀nà tí àlàáfíà àti ìdàgbàsókè yóò fi bá àwùjọ Yorùbá nípa iṣẹ́ pàtàkì tí Olódùmarè gbé lé ẹnikọ̀ọ̀kan wọn lọ́wọ́.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe:

1. Dárúkọ àwọn òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀ márùn-ún kí o sì ṣàlàyé nípa àbùdá wọn.
2. Ṣàlàyé irú òrìṣà tí Òrìṣà-ńlá íṣe àti ipò rẹ̀ láàrin àwọn irúnmọlẹ̀ yòókù
3. Ǹjẹ̀ a lè sọ pé òrìṣà tí ó burú ni Èṣù íṣe. Fi àpẹẹrẹ gbe ìdáhùn rẹ lẹ́sẹ̀.
4. Ipa wo ni àwọn òrìṣà wọ̀nyí kó nínú iṣẹ́ ìsẹ̀dá ayé:
(a) Ọbàtálá
(b) Ògún

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adeoye, C.L. 1979 *Àṣà àti Òrìṣà Yorùbá.* Ibadan, Oxford University Press (Nig) Ltd.

Ladele, T.A.A. et al. 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwà Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ibadan, Gavima Press Ltd.

Ọlajubu, O. 1975. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* Ibadan, Longman.

Ológundúdú, D. 2008. *The Cradle of Yorùbá Culture.* U.S.A Centre for spoken words/Institute of Yorùbá studies.

## MÓDÙ KEJÌ
## ÌPÍN KẸRIN: ỌDÚN ÌBÍLẸ̀ YORÙBÁ

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ọdún Egúngún
4.2 Ọdún Agẹmọ
4.3 Ọdún Ifá
4.4 Ọdún Òkèbàdàn
4.5 Ọdún Òrìṣà-Oko
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà:

Nínú ìpín yìí ni a ó ti sọ̀rọ̀ nípa àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá. Àwọn ọdún yìí pín sí oríṣìí méjì. Àwọn kan jẹ mọ́ ọdun òrìṣà bíi ọdún Ifá, ọdún Ṣàngó, ọdún Òrìṣà-Oko, bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìíràn dá lórí ìsẹ̀ṣe. Àwọn ọdún yìí ni àkókò tí àwọn Yorùbá máa ń rántí àwọn irúnmọlẹ̀ tàbí kí wọ́n rántí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mọ́nigbàgbé èyí tí ó ṣẹlẹ̀ sí wọn ní àwọn àkókò kan sẹ́yìn.
Bí àpẹẹrẹ, àkókò ọdún egúngún jẹ́ àkókò tí àwọn Yorùbá máa ń rántí àwọn baba-ńlá wọn tí ó ti di olóògbé ṣùgbọ́n tí wọ́n gbàgbọ́ pé ó yẹ kí wọ́n máa rántí wọn. Bákan náà ni ọdún àwọn òrìṣà tí wọ́n ti padà sí ìsálú ọ̀run ṣùgbọ́n tí wọn ń kópa nínú ìgbáyégbádùn ẹ̀dá ènìyàn.
Níbí yìí ni a ti wo díẹ̀ lára àwọn ọdún tí Yorùbá máa ń ṣe láti rántí àwọn Ìbọ.

### 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Èròǹgbà wa nínú ìpín yìí ni láti jẹ́ kí o:
- mọ̀ nípa àwọn ọdún tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe lóòrèkóòrè.
- ní ìmọ̀ lórí èrò àwọn Yorùbá nípa ọjọ́ ọ̀la
- mọ̀ ìdí tí a fi ń ṣe àwọn ọdún yìí.
- ipa àti ìwúlò ọdún wọ̀nyí láàrin àwọn Yorùbá láyé àtijọ́ àti lóde òní.

### 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Dárúkọ àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá tí o mọ̀ àti bí wọ́n ti ń ṣe wọ́n.
2. Ṣàlàyé nípa ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá kan tí ó gbajú gbajà ní agbègbè abínibí rẹ.

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́:

**4.1 Ọdún Egúngún:** Egúngún ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé wọ́n wá láti ọ̀run láti wá bẹ àwọn ọmọ àti ẹbí tí wọ́n fi sáyé wò. Èyí ń tọ́ka sí pé àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ pé àwọn aláṣekù wọ̀nyí lọ simi ní ọ̀run ni, wọ́n sì máa ń wá fún ìbẹ̀wò

àwọn ẹbí tí wọ́n fi sílẹ̀ lọ. Ìdí nìyí tí wọn ṣe máa ń pe àwọn egúngún yìí ní ará ọ̀run kìn-inkin.
Ní àkókò tí wọ́n bá ń ṣe ọdún yìí, ìbẹ̀rù máa ń wà ní ọkàn àwọn ènìyàn nítorí pé ìrísí àti ìwọṣọ àwọn egúngún mìíràn máa ń banilẹ́rù ṣùgbọ́n a rí i pé àwọn egúngún wọ̀nyí máa ń jó yí ìlú ká, wọn yóò sì máa ṣe àdúrà fún àwọn ènìyàn wọn tí wọ́n bá pàdé. Àwọn ènìyàn náà yóò máa ta wọ́n lọ́rẹ owó, obì àti àwọn ohun mìíràn tí ó bá yẹ kí wọ́n fi ṣe àlejò ará ọ̀run wọ̀nyí.
Láyé àtijọ́, kì í sábà sí rògbòdìyàn tàbí jàgídíjàgan ní àsìkò tí a bá ń ṣe ọdún egúngún ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé láyé òde òní, ọ̀pọ̀ ní ìgbà tí àwọn ọmọlẹ́yìn egúngún máa ń dá ìjà sílẹ̀, tí àwọn ènìyàn tí ó tẹ̀lé wọn sì máa ń fara pa. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, ọdún egúngún lókìkí, ó sì máa ń gbayì ní gbogbo ìlú ní ilẹ̀ Yorùbá.

**4.2 Ọdún Agẹmọ**: Ọdún ìbílẹ̀ ẹ̀yà Ìjẹ̀bú ni ọdún Agẹmọ yìí, bẹ́ẹ̀ ni ọdún tí ó ṣe pàtàkì púpọ̀ ni láàrin wọn. Tọmọdé tàgbà ló máa ń ní ayọ̀ ni àkókò ọdún yìí nítorí ó sábà máa ń kó àwọn ènìyàn yìí papọ̀ fún ìbáṣepọ̀ tí ó péye.
Àwọn ènìyàn, pàápàá àwọn ọmọ ìbílẹ̀ Ìjẹ̀bú ni a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí 'ọmọ alágẹmọ mẹ́rìndínlógún'. Agẹmọ yìí máa fi ara pẹ́ egúngún ṣùgbọ́n wọn kì í jẹ́ kí obìnrin rí agẹmọ. Ìlú kan tí ń jẹ Imọsàn nítòsí Ìjẹ̀bú-Òde ni àwọn agẹmọ yí ti máa ń péjọ ní àkọ́kò ọdún yìí, bẹ́ẹ̀ ni oríṣìíríṣìí idán ni àwọn àwòrò Agẹmọ máa ń pa láti fi àgbà han ara wọn.

**4.3 Ọdún Ifá:** Ní ọdọọdún ni ayẹyẹ ọdún Ifá máa ń wáyé. Nígbà yìí ni àwọn babaláwo àti ìyánífá yóò péjọ sí ilé olórí wọn, tí wọn yóò máa sun ìyẹ́rẹ́ Ifá ní alẹ́ àìsún ọdún yìí. Ní òru ọjọ́ tí wọ́n bá ń ṣe ọdún Ifá, onírúurú àwọn olóyè awo ni yóò máa péjọ láti dá Ifá ọdún níbi tí Ifá yóò ti máa sọ onírúurú àsọtẹ́lẹ̀ ohun tí ń bọ̀ wá ṣẹlẹ̀ sí ìlú àti sí ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn.
Ní alẹ́ ọjọ́ yìí ni àwọn babaláwo yóò wọ igbó odù lọ, tí wọn yóò sì ṣe ìwádìí ìjìnlẹ̀ lórí irúfẹ́ ètùtù tí wọ́n yóò ṣe láti mú kí ìlú wà ní àlàáfíà àti ìsọ̀kan. Bí ó bá ti di ọjọ́ kejì ni àwọn babaláwo, ìyánífá àti àwọn ará ìlú yóò máa jó, tí wọn yóò sì máa yọ̀ pé àwọn tún rí àyájọ́ ọdún mìíràn lóde ayé.
Oríṣìíríṣìí oúnjẹ ni wọ́n máa ń pèsè ní ọjọ́ yìí, tí wọ́n yóò sì máa lu ìlù Ifá bíi àràn, agogo, ìpèsè, pẹ̀lú ọ̀pá àwọn ìlù náà tí yóò máa ró lákọlákọ. Onírúurú orin Ifá àti ìyẹ̀rẹ̀ Ifá, èyí tí ó fi àwọn ohun tí ó ti ṣẹlẹ̀ àti àwọn ohun tí yóò ṣẹlẹ̀ hàn fún ará ìlú. Ní ìparí, oníkálukú ènìyàn tí wọ́n bá fẹ́ ṣe ìwádìí ni yóò lo àǹfààní àkókò ọdún yìí láti ṣe bẹ́ẹ̀.

**4.5 Ọdún Òkèbàdàn ní Ìlú Ìbàdàn:** Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, àwọn ọdún kọ̀ọ̀kan wà tí kì í ṣe ọdún fún àwọn òrìṣà àtẹ̀wọnrọ̀ ṣùgbọ́n tí wọ́n wà fún ìrántí àwọn nǹkan mánigbàgbé tí ó ti ṣẹlẹ̀ ní ìpìlẹ̀ ayé àwọn ènìyàn náà lápapọ̀. Àwọn ìlú kọ̀ọ̀kan tí àwọn ọmọ Odùduwà tẹ̀dó ni ó máa ń ṣe ìrántí ọdún yìí kí àwọn ọmọ àti ọmọ-ọmọ wọn lè ni ìmọ̀ kíkún nípa ìṣẹ̀dálẹ̀ ìlú kọ̀ọ̀kan yìí.
Òkèbàdàn jẹ́ ọdún kan tí àwọn ọmọ bíbí ìlú Ìbàdàn máa ń ṣe fún ìrántí ìṣẹ̀lẹ̀ mánigbàgbé èyí tí ó wáyé ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ tí Lágelú tẹ ìlú náà dó. Gẹ́gẹ́ bí ìtàn àtẹnudétí àti àwọn àkọsílẹ̀ kan ti sọ, ìtàn yìí dá lórí bí àwọn ènìyàn yìí ṣe sá gun orí òkè Àwọ́tán tí ó wà ní Ẹlẹ́yẹlé lọ nígbà tí àwọn ẹ̀yà Yorùbá yòókù gbógun tì wọ́n bí wọ́n ṣe fi ẹ̀sùn kan wọ́n pé wọ́n dorí àṣà kodò.
Ọdún Òkèbàdàn yìí máa ń wáyé lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n ti gun òkè Àwọ́tán yìí, tí wọ́n sì ní àǹfààní láti máa rí oúnjẹ bíi òro, ìgbín, àgbàdo àti àwọn irè igbó mìíràn jẹ. Lẹ́yìn tí wọ́n bọ́ nínú ogun yìí ni Ifá sọ fún wọn pé kí wọ́n máa ṣe ìrántí àkókò yìí ní ọdọọdún.

Ní àsìkò ọdún Òkèbàdàn yìí, abọrẹ̀ Òkè yìí tí wọn ń pè ni Abọ̀kè yóò di irun rẹ̀ bí i ti obìnrin, yóò sì ṣe ètùtù tí ó bá yẹ pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Ọba ìlú àti àwọn ìjòyè rẹ̀.
Lọ́jọ́ ayẹyẹ ọdún yìí, ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ dáná, bẹ́ẹ̀ ni èéfín kò gbọdọ̀ rú títí ayẹyẹ ọdún yìí yóò fi parí. Bákan náà, àwọn ọmọlẹ́yìn àwòrò yìí yóò jáde láti máa lọ kí ọba àti àwọn ìjòyè ìlú pẹ̀lú ìwúre láti ẹnu Abọ̀kè. Bí wọ́n bá ti ń lọ ni ààrin ìlú, wọn yóò máa kọrin Òkèbàdàn, èyí tí àwọn mìíràn máa ń gbà gẹ́gẹ́ bí ìsọkúsọ ṣùgbọ́n tí ó fi ìtumọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àtijọ́ hàn.
Irúfẹ́ ọdún báyìí máa ń wáyé láti ìlú ńlá kan dé èkejì. Bí àpẹẹrẹ, ọdún Olúmọ ní ìlú Abẹ́òkúta, ọdún àsabàrí ni ìlú Ṣakí, ọdún Ìyámọ̀pó ní ìlú Ìgbẹ́tì, ọdún Agẹmọ ní ilẹ̀ Ìjẹ̀bú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

4.5 **Ọdún Òrìṣà-Oko:** Ọdún Òrìṣà-Oko yìí ni wọ́n máa ń ṣe ní ìlú Ìràwọ̀ tí ó wà létí Ṣakí. Ibí yìí ni wọ́n ti máa ń ṣe ayẹyẹ ọdún yìí lọ́dọọdún. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé akọni ènìyàn ni òrìṣà yìí í ṣe ní ìgbà láéláé ṣùgbọ́n àwọn ènìyàn rẹ̀ sọ ọ́ di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ lẹ́yìn ikú rẹ̀. Irúfẹ́ àwọn ẹ̀dá ènìyàn tí a sọ di òrìṣà báyìí pọ̀ láàrin àwọn Yorùbá. Ọ̀pọ̀ nínú wọn ló di òrìṣà tí a ń bọ yálà nípa iṣẹ́ rere tàbí búburú tí wọ́n ti ṣe láàrin àwọn ènìyàn wọn, èyí tí ó fà á kí wọ́n di ẹni-ọ̀wọ̀ tàbí ẹni ìbẹ̀rù lẹ́yìn ìpapòdà wọn. Yorùbá gbà pé lẹ́yìn tí akíkanjú ọkùnrin tàbí obìnrin bá gbésẹ̀ ni a sábà máa ń mọ ìrírí wọn. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń sọ pé 'Ọjọ́ tí a kú làá dère, ènìyàn kò sunwọ̀n láàyè.
Ìtàn àtẹnudẹ́tí kan sọ fún wa pé ògbójú ọdẹ ni òrìṣà yìí ní ìgbà ayé rẹ̀. Yàtọ̀ sí pé ọdẹ tí ó gbóná ni, ó fi hàn pé kò sí ohun tí ó lè sọ tí kò ní í ṣẹ bẹ́ẹ̀. Yàtọ̀ sí èyí, ó tún pada di babaláwo tó gbọ́fá yanranyanran, ó sì lókìkí bí ìsáná ẹ́ẹ́ta.
Wàyí o, ọkùnrin alágbára yìí lo agbára rẹ̀ fún àlàáfíà àwọn ènìyàn ìlú, ó sì tẹ àwọn oṣó, àjẹ́ àti àwọn oníṣẹ́ òkùnkùn mìíràn lórí ba.
Nígbà ti ọkùnrin yìí máa papòdà, ìtàn sọ fún wa pé níṣe ni ó di igi ràpàtà kan sí agbègbè tí wọn ń pè ní Ìpóló níbi tí wọ́n máa ń mú ẹnikẹ́ni tí wọ́n bá fura sí pé ó ní àjẹ́ tàbí oṣó lọ.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín yìí ni a ti wo àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá kan àti ìdí tí wọ́n fi ń wáyé ní ọdọọdún. A ṣe àlàyé nípa àwọn ọdún òrìṣà atẹ̀wọ̀nrọ̀ bíi Ifá àti Egúngún, bẹ́ẹ̀ ni a sọ nípa àwọn òrìṣà tí a ń bọ láti ṣe ìrántí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mọ́nigbàgbé kan. Bí àpẹẹrẹ, Òkèbàdàn, Òrìṣà-Oko àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A rí i pé àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí máa ń fa ìṣọ̀kan, wọ́n sì máa ń mú kí àlàáfíà jọba ní ìlú àti àwọn agbègbè wọ̀nyí.

## 6.0 <u>Iṣẹ́ Ṣíṣe:</u>

1. Ṣàlàyé àwọn ohun tí àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí dúró fún.
2. Nínú èrò tìre, ǹ jẹ́ o gbà pé àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí yóò máa tẹ̀síwájú lojú àwọn ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá tí ó gbòde kan?
3. Ṣàlàyé nípa ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá kan tí ó gbajú gbajà ní agbègbè abínibí rẹ.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí:

Adeoye, C.L. 1985. *Ìgbàgbọ́ àti Ẹ̀sìn Yorùbá.* Ibadan, Evans Brothers Ltd.

Ologundudu, D. 2008. *The Craddle of Yorùbá Culture.* U.S.A. center for spoken Words, Institute of Yorùbá Culture.

Ladele, T.A. et. Al 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ibadan, Gavina Press Ltd.

## MÓDÙ KEJÌ: ÀṢÀ ILẸ̀ NÍNÍ ÀTI LÍLÒ LÁÀRIN ÀWỌN YORÙBÁ

## ÌPÍN KARÙN-ÚN:

**Àkóónú**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ilẹ̀ níní Láwùjọ Àwọn Yorùbá
4.2 Ilẹ̀ Lílò Láàrin Àwọn Yorùbá
4.3 Ọfọ̀ Ilẹ̀ Láàrin Àwọn Yorùbá
4.4 Ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá
4.5 Rògbòdìyàn ilẹ̀ láyé Àtijọ́ àti Lóde Òní
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


### 1.0 Ìfáàrà

Ọ̀rọ̀ ilẹ̀ níní láàrin àwọn Yorùbá ṣe pàtàkì púpọ̀. Ilẹ̀ níní jẹ́ ohun ẹlẹgẹ́ èyí tí ó máa ń banilẹ́rù láti dá sí. Títí di òní yìí, ọ̀pọ̀ ọmọ Yorùbá ni kì í ní ìfẹ́ sí dídá sí ọ̀rọ̀ ilẹ̀ nítorí pé rògbòdìyàn sábà máa ń sẹlẹ̀ lórí ilẹ̀ níní. Nítorí náà bí àwọn ọmọdé bá fẹ́ sọ̀rọ̀ àgbà tàbí pa òwe, wọn yóò júbà àgbà, bẹ́ẹ̀ ni bí àwọn àgbà bá fẹ́ ṣe èyí, ilẹ̀ ni wọn yóò fi ìbà fún.
Bí awuyẹwuyẹ bá wáyé lóri ọ̀rọ ilẹ̀, àwọn Yorùbá máa ń sọ́ra nígbà tí ọfọ̀ ilẹ̀ bá wáyé nítorí wọ́n gbà pé ilẹ̀ kì í ṣe ìní ẹnìkan bí kò ṣe pé Olódùmarè ni ó dá ilẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀, kì í sì í ṣe ohun tí ẹ̀dá ènìyàn le má ṣe awúrúju lórí rẹ̀.
Ilẹ̀ níní jẹ́ ohun àjogúnbá ní ilẹ̀ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni Yorùbá kì í ta ilẹ̀ ní ayé ìgbàanì. Wọ́n máa ń lo ilẹ̀ fún oko dídá, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń lò ó láti sìnkú àwọn ènìyàn wọn. Ṣùgbọ́n lóde òní, ilẹ̀ títà ti wọ́pọ̀ láàrin àwọn ènìyàn. Kódà ròdòdìyàn ilẹ̀ ni ó gba ìlú kan, tí ọ̀pọ̀ ẹ̀mí si máa ń ṣòfò lórí èyí.

### 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Nínú ìpín yìí ni o ó ti kà nípa:

- Ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun ìní àjogúnbá
- Bí ilẹ̀ ṣe jẹ́ ohun ẹlẹgẹ́ ní àwùjọ Yorùbá
- Àwọn àríyànjiyàn tí ó máa ń ṣúyọ lórí ilẹ̀ níní
- Ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn Ìbọ.
- Ipò tí ilẹ̀ níní wà lóde òní.

### 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Kín ni pàtàkì ilẹ̀ níní láàrin
2. Sọ pàtàkì iṣẹ́ àgbẹ̀ láàrin àwọn Yorùbá

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

**4.1 Ilẹ̀ Níní:** Ilẹ̀ níní ṣe pàtàkì láàrin àwọn Yorùbá ní ayé àtijọ́ nítorí pé ilẹ̀ jẹ́ irin-iṣẹ́ pàtàkì tí àwọn àgbẹ̀ nílò. A ó rántí pé iṣẹ́ àgbẹ̀ ni iṣẹ́ tí ó gbajúmọ̀, tí ó sì lókìkí jù láàrin àwọn Yorùbá láyé àtijọ́. Bí Yorùbá bá tilẹ̀ ní iṣẹ́ ìdílé mìíràn, iṣẹ́ àgbẹ̀ yìí gbọ́dọ̀ kún iṣẹ́ wọn. Kódà nígbà tí àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun mú ẹ̀kọ́ ìwé dé, tí àwọn mìíràn sì ń ṣe iṣẹ́ ọba, Yorùbá gbà pé wọ́n gbọdọ̀ fi iṣẹ́ àgbẹ̀ kún iṣẹ́ wọn. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń kọ ọ́ lórin pé,
Ìwé kíkọ́,
Láìsí ọkọ́,
Àti Àdá,
Kò í pé o o,
Kò í pé ò ò,
Iṣẹ́ àgbẹ̀ niṣẹ́ ilẹ̀ wa
Ẹni kò ṣiṣẹ́, á má jalè.
Nítorí ìdí èyí, ilẹ̀ níní nípa jíjogún lọ́dọ̀ àwọn baba-ńlá wọn ṣe pàtàkì láti ṣe iṣẹ́ àgbẹ̀ yìí. Ìdí ni pé bí kò bá sí àgbẹ̀ kò ní í si oúnjẹ fún ìlú, bẹ́ẹ̀ ni Yorùbá máa ń pa á lówe pé'ebi kì í wọnú kí ọ̀rọ̀ mìíràn wọ̀ ọ́'. Bóyá láyé àtijọ́ tàbí lóde òní, ilẹ̀ níní ṣe pàtàkì fún iṣẹ́ àgbẹ̀ ṣíṣe.

**4.2 Ilẹ̀ Lílò:** Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlàyé síwájú, pàtàkì jùlọ nínú ohun tí àwọn Yorùbá máa ń lo ilẹ̀ fún ni iṣẹ́ àgbẹ̀ nítorí bí ko bá sí àgbẹ̀, ebi yóo máa pa ará ìlú. Bí ebí bá sì dé, wàhálà púpọ̀ ni ó máa ń tẹ̀ lé èyí. Ìyàn tàbí ọ̀wọ́n oúnjẹ ni èyí máa ń mú wá, èyí tí ó lè fa àìrójú bá ènìyàn ìlú.
Yàtọ̀ sí ilẹ̀ lílò fún ìṣẹ́ àgbẹ̀. Yorùbá tún máa ń lo ilẹ̀ fún ilé kíkọ́. Ní ìgbésí ayé ẹ̀dá ènìyàn, a rí i pé ó ṣe pàtàkì láti ní ibùgbé tí a ó máa fi orí tì sí. Nítorí náà, àwọn Yorùbá máa ń kọ́lé nínú ìlú àti ní ẹgàn níbi tí wọn yóò máa fi orí pamọ́ sí nígbà òjò àti oòrùn bá dé. A tún máa ń lo ilẹ̀ fún ọjà dídá, èyí tí wọn yóò máa ná ní ọrọọrún tàbí ni ìta. Lẹ́yìn nǹkan tí a dárúkọ lókè yìí a tún rí i pé Yorùbá máa ń lo ilẹ̀ láti sínkú àwọn ẹni wọn tí ó bá pa ipò dà. Wọn yóò gbẹ́ ilẹ̀ yálà nínú ilé tàbí ní ìta láti sin eni náà sí, bẹ́ẹ̀ ní èyí ni wọ́n máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí 'ojú orórì'. Nítorí náà, ilẹ̀ lílò ṣe pàtàkì ní ìgbésí ayé àwọn Yorùbá.

## 4.3 Ọfọ̀ Ilẹ̀:

Ohun tí a sábà máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ọfọ̀ ilẹ̀ láàrin àwọn Yorùbá ni pe àwọn rògbòdìyàn àti àríyànjiyàn kan máa ń ṣúyọ nígbà mìíràn lórí ilẹ̀ níní. Ó lè jẹ́ láàrin ẹbí kan sí ẹbí kejì tàbí ẹni kan nínú ẹbí sí ẹnìkejì rẹ̀. Èdè-àìyedè yìí lè fẹjú dé góńgó tí ó sìle fa ìjà tí yóò mú ẹ̀mí lọ.
Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Yorùbá kì í fẹ́ kí ìjà ilẹ̀ wáyé nítorí wọn gbà pé Ọlọ́run ló ni ilẹ̀ àti pé, àwa ẹ̀dá inú ayé bá ilẹ̀ níbẹ̀ ni. Bíbí tí a bí ènìyàn, tí ó sì fi orí kan ilẹ̀ lọ́jọ́ ìbí náà ni a fi ní àǹfààní láti máa lo ilẹ̀ náà.
Nítorí náà, Yorùbá kì í jà lórí ilẹ̀ láyé ìgbàanì. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, bí irú ìjà tàbí gbọ́nmi-sí-i-omi-òtóo bẹ́ẹ̀ bá wáyé, ó ṣe é ṣe kí ẹ̀mí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn bá ìṣẹ̀lẹ̀ náà rìn. Ṣùgbọ́n sá o, ilẹ̀ máa ń dájọ́ fún ẹni tí ó jà lórí òun lọ́nà àìtọ́.

## 4.4 Ilẹ̀ Gẹ́gẹ́ bí Òrìṣà Àkúnlẹ̀bọ:

Bí a bá wo ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun tí Olódùmarè ti dá sínú ayé kí ènìyàn tó dé ibẹ̀, a ó rí i pé ilẹ̀ ní agbára tí ó máa ń lò lórí ẹ̀dá alààyè tí ó bá tasẹ̀ àgẹ̀rẹ̀ sí i.
Nítorí náà, àwọn Yorùbá gbà pé òrìṣà àkúnlẹ̀bọ ni ilẹ̀ jẹ́ níbikíbi tí ó bá wà. A ó ṣe àkíyèsí pé níbi tí ilẹ̀ kò bá sí gẹ́gẹ́ bí orí omi, àwọn Yorùbá máa ń bọ àwọn òrìṣà omi bẹ́ẹ̀.
Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni àwọn Yorùbá máa ń lo ilẹ̀ láti fi búra bí ìgbà tí a bá ń fi òrìṣà ògún tàbí àwọn òrìṣà mìíràn búra. Èyí jẹ́rìí sí i pé òrìṣà pàtàkì ni ilẹ̀ náà láàrin àwọn Yorùbá.
Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, Yorùbá máa ń tọ́ka sí i pé ènìyàn kò gbọdọ̀ dalẹ̀ ẹbí tàbí ilẹ̀ ọ̀rẹ́ àti pé ẹni tí ó bá dalẹ̀ yóò bá ilẹ̀ lọ.
Èyí nìkan kọ́, àwọn Yorùbá tún máa ń lo ilẹ̀ láti fi dá awo tàbí pa nǹkan àṣírí mọ́. Nígbà yìí ni a máa ń sọ pé wọ́n mulẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n lè bu ilẹ̀ díẹ̀, kí wọ́n sì dà á sínú omi fún àwọn tí wọ́n bá fi àṣírí kan pámọ́ lọ́dọ̀ ara wọn mu. Wọ́n gbà pé ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣèké yóò bá ilẹ̀ lọ lójijì.

## 4.5 Rògbòdìyàn Ilẹ̀ Ní Ayé Àtijọ́ àti Lóde Òní:

Nígbà mìíràn, àwọn Yorùbá máa ń yá ilẹ̀ lò lọ́wọ́ ara wọn fún ìgbà díẹ̀. Nínú irú ilẹ̀ àyálò bẹ́ẹ̀, ẹni tí ó yá a lò kò gbọdọ̀ gbin àwọn ohun ọ̀gbìn pípẹ́ bíi kòkó, obì, ọ̀pẹ, àgbọn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ sínú oko náà. Ṣùgbọ́n sá o, o le gbin iṣu, àgbàdo, erèé, awújẹ àti àwọn nǹkan mìíràn bẹ́ẹ̀.
Ilẹ̀ títà bẹ̀rẹ̀ nígbà tí àwọn àtọ̀húnrìnwá dé sí ààrin Yorùbá. Ìtàn àtẹnudétí sọ fún wa pé ilẹ̀ àwọn Ẹ̀gbá ni àṣà àǹta-ilẹ̀ ti bẹ̀rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ pé ọ̀dọ̀ wọn ni àwọn Sàró tí wọ́n kọ́kọ́ mú ẹ̀sìn Ọmọlẹ́yìn Krístì gbà wọlé sí Nàìjíríà.
Nígbà yìí, àwọn àjèjì wọ̀nyí náà fẹ́ kọ́ ilé ìwé, ilé ìjọsìn wọn, àwọn ilé okòwò àti àwọn ilégbèé tiwọn náà. Kò pẹ́, kò jìnnà ni àṣà ilẹ̀ títà àti yíyálò yìí tàn káàkiri ilẹ̀ Yorùbá tí ó sì máa ń mú rògbòdìyàn lọ́wọ́.
Lóde òní, ilẹ̀ títà ti mú ọ̀pọ̀lọpọ̀ wàhálà lọ́wọ́ nítorí pé ọ̀pọ̀ àwọn jẹgúdúragúdú ni wọ́n ń ta ilẹ̀ kan fún ènìyàn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ èyí tí ó sì máa ń fa aáwọ̀ láàrin àwùjọ. Nísinsinyìí, àwọn aláṣẹ ìjọba ìgbàlódé tilẹ̀ máa ń já ilẹ̀ gbà lọ́wọ́ oní-nǹkan nítorí wọ́n ti ṣòfin pé 'ọba ló ni ilẹ̀'. Ẹnikẹ́ni tí ó bá tilẹ̀ fẹ́ kọ́lé sórí ilẹ̀ baba rẹ̀ gbọ́dọ̀ gba àṣẹ Ìjọba kí ó tó ṣe bẹ́ẹ̀.
Ó tilẹ̀ ṣeni láàánú pé ní àkókò tí a wà yìí, ọ̀pọ̀ ìletò àti abúlé ni àwọn ọmọdé ìgbà yìí ti tà fún àwọn àjèjì tán, tí wọ́n sì ń fi ọwọ́ òsì júwe ilé baba wọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí:

Nínú ìpín yìí ni a ti ṣe àlàyé ní sókí àwọn ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà ní ilẹ̀ láyé àtijọ́. A sọ fún wa bí ilẹ̀ ṣe jẹ́ ti Ọlọ́run àti pé àwọn baba-ńlá wa ni wọ́n máa ń jogún ilẹ̀ nígbà tí wọn dé apá ibi tí wọ́n tẹ̀dó sí yìí.
A mẹ́nuba ìwúlò ilẹ̀ àti àwọn ohun tí a ń lò ó fún gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àgbẹ̀ ṣíṣe, ilé kíkọ́ ọjà, dídá àti òkú sísin. A tẹ̀ síwájú sí i láti ṣe àlàyé pé ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ìjà máa ń wáyé lórí ilẹ̀ pàápàá nígbà tí àwọn àjèjì wọnú àwùjọ Yorùbá. Ní ìparí, a ṣe àlàyé lórí àwọn ìyípadà tí ọ̀làjú mú bá ọ̀rọ̀ ilẹ̀ ní àwùjọ Yorùbá.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Àwọn ọ̀nà wo ni ilẹ̀ wúlò fún ní àwùjọ Yorùbá?
2. Kín ni ó máa ń fa yánpọnyánrin lórí ilẹ̀ ní ayé àtijọ́ àti lóde òní?
3. Gẹ́gẹ́ bí èrò tìrẹ, àwọn ọ̀nà wo ni a lè gbà dẹ́kun rògbòdìyàn lórí ilẹ̀ níní, lílò àti títà?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Ladele, T.A.A et. Al 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn, Gavina Press Ltd.

Daramola, O. S. 1968. *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ibadan, Onibon-Oje Press & Book Industries (Nig) Ltd.

Adeoye, C.L. 1985. *Ìgbàgbọ́ àti ẹ̀sìn Yorùbá.* Ibadan, Evans Borthers Ltd.

Ọlajubu, O 1975. *Ìwé Ìbílẹ̀ Yorùbá.* Ibadan, Longman.

Bíobaku, S.O. (ed) 1973. *Sources of Yorùbá History.* Oxford, Oxford University Press.

## MÓDÙ KẸTA

## ÌPÍN KÌNNÍ: ÈTÒ ÌJỌBA ÌBÍLẸ̀ YORÙBÁ LÁYÉ ÀTIJỌ́

**Àkóónú**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ètò ìdílé Nínú Ìṣèjọba Ìbílẹ̀ Yorùbá Láyé Àtijọ́
4.2 Fífi Ọba àti Ìjòyè jẹ ní Ilẹ̀ Yorùbá Láyé Àtijọ́
4.3 Fífa ọmọ Oyè sílẹ̀
4.4 Ìwádìí Lọ́wọ́ Ifá
4.5 Ètùtù fún ọmọ oyè tí Ifá bá mú
4.6 Ìfinijoyè ìdílé tàbí Oyè Ìlú
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.O Ìfáàrà

Nínú ìpín kínní yìí ni a ti ṣe àlàyé ètò ìjọba ìbílẹ̀ Yorùbá ní ayé àtijọ́ tí a ṣe wo àwọn ìdílé Yorùbá àti ipò tí wọ́n kó nínú ètò yìí. A ṣe àgbéyẹ̀wò bí a ṣe ń fi ọba jẹ àti àwọn ìlànà tí wọn ń tẹ̀lé ní ìgbàanì. A rí i pé àwọn ìjòyè kan náà máa ń wà pẹ̀lú ọba láti bá a jíròrò nípa ààtò ìlú.
Ìpín yìí yóò fi ìyàtọ̀ ipò ọba láyé àtijọ́ àti lóde òní hàn. A sì mọ ìyàtọ̀ tàbí ìyípadà tí ó ti bá ètò yìí lóde òní.

## 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó kà nípa:

- ìpìlẹ̀ ìfinijọba láti ìbẹ̀rẹ̀
- ipò ìdílé nínú fífi ọba jẹ láyé àtijọ́
- ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìmọ̀ nípa bí ipò ọba ṣe ṣe pàtàkì tó láyé ọ-jọ́un
- ṣíṣe àgbéyèwò bí a ṣe máa ń bá Ifá sọ̀rọ̀ ní àkókò náà àti ìyípadà tí ó dé bá ìlànà yìí ni òde òní.
- ipa tí ìlú máa ń kó ní àsìkò ìfinijọba tàbí ìfinijoyè bẹ́ẹ̀

## 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Sọ̀rọ̀ lórí ìbílẹ̀ agbègbè rẹ láyé àtijọ́ àti lóde òní
2. Ṣe àfiwé ipò ọba láyé àtijọ́ àti lóde òní

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ètò ìdílé Nínú Ìṣèjọba Ìbílẹ̀ láyé Àtijọ́

Kí àwọn Òyìnbó amúnisìn tó dé, kò dabí alárà pé àwọn Yorùbá ní olórí kan gbòógì nínú ètò ìṣèlú wọn. A kò tilẹ̀ le sọ pé wọ́n ní orúkọ kan tí ó pa gbogbo wọn pọ̀. Nítorí náà, kí àwọn Òyìnbó yìí tó bẹ̀rẹ̀ sí i jẹ gàba lórí ètò ìṣèlú Yorùbá, àti pẹ̀lú pé kí ètò ìsèlú òde-òní tó wáyé, àwọn ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan ní ó ń ṣe ìjọba àti ààtò ìlú tàbí agbègbè wọn (Bíòbákú, 1973).

Ètò ìdílé ṣe pàtàkì nínú ètò ìjọba ìbílẹ̀ Yorùbá ní ayé àtijọ́. A kò sàìmọ̀ pé bí kò bá sí àjọgbépọ̀ àti àjọṣepọ̀, kì bá ti sí ètò ìjọba ìbílẹ̀ tí ó gúnmọ́. Ìdí ni pé bí ó bá jẹ́ pé ìdílé ni ó wà tí wọ́n sì ń gbé ibìkan náà, ibi tí ètò ìjọba náà yóò ti mọ nìyẹn. Bí ìletò kan bá kéré, ó yẹ kí á rí ìdílé bí i mẹ́ta tàbí mẹ́rin níbẹ̀. Èyí ni a lè pè ní àkójọpọ̀ (local group) tí a sì le pè ní ìlú. Ìlú le kéré bí ìlú Ẹrùnmu tàbí kí ó tóbi bí ìlú Ìbàdàn. Èyí ni pé bí ìdílé púpọ̀ bá ti kó ara wọn pọ̀ sí ojú kan, wọ́n ti di ìlú nìyẹn.
Àwọn àkójọpọ̀ wọ̀nyí kì í sábà bá ara wọn tan, nítorí náà, wọ́n lè fẹ́ ara wọn ní ìyàwó. Bí wọ́n bá tilẹ̀ bá ara wọn tan, ó le fẹ́ ìbátan tí ó wà láti inú ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá ni.

Nítorí náà, irú àkójọpọ̀ yìí gbọ́dọ̀ ní olórí. Bí ó bá jẹ́ èyí tí ó tóbi ni, ọba ni a ń pe olórí wọn. Bí ó bá kéré díẹ̀, wọn yóò maáa jẹ́ Baálẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, Baálẹ̀ ni ìlú Ìbadan máa ń ní tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n nísinsinyìí, ó ti di Ọba aládé. Nítorí náà, bí ìlú bá ṣe tóbi tó ni à ṣe ń mọ orúkọ oyè olórí ìlú bẹ́ẹ̀.
Gbogbo Ọba ni ó máa ń ní ìtẹ́ tí à ń pè ní ojúpo lórí èyí tí wọ́n máa ń gúnwà sí. Gbogbo ọba ni ó ní adé, wọ́n máa ń wọ pẹ̀lú oríṣìíríṣìí ìlẹ̀kẹ̀ (àkún) tí wọ́n máa ń gbé sọ́rùn. Èyí nìkan kọ́ ọba máa ń ní ìrùkẹ̀rẹ̀ àti agboòrùn tí ó tóbi. Àwọn ìlù wà tí ó jẹ́ pé ọba nìkan ni wọ́n máa ń lù wọ́n fún. Bí àpẹẹrẹ, ìgbín ní agbègbè Ọ̀yọ́ pẹ̀lú fèrè tí a mọ̀ sí kàkàkí.

Ní ayé àtijọ́, Aláàfin ni olórí gbogbo àwọn ọba ṣùgbọ́n kì í ṣe oyè baba sí ọmọ tàbí àjogúnbá. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé àrẹmọ ni ó máa jẹ ọba ní Ọ̀yọ́ láyé àtijọ́, èyí yí padà nígbà kan, èyí tí ó fa ìjà ní Ọ̀yọ́-Ilé nígbà náà.

### 4.2 Ètò Ìjọba Ìbílẹ̀ ní Ilé-Ifẹ̀:

Gẹ́gẹ́ bí a ti kà sẹ́yìn, ìtàn sọ pé ni Ilé-Ifẹ̀ ni àwọn ẹ̀yà Yorùbá kọ́kọ́ kó ara wọn jọ sí ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni Ọ̀ọ̀ni ni olórí wọn nígbà náà. Ọ̀ọ̀ni kàn jẹ́ olórí láàfin ni, kì í ṣe pé òun ní ń ṣe àwọn ètò ìlú. Ó ní àwọn olùrànlọ́wọ́ tàbí olùbáṣiṣẹ́pọ̀ tí wọ́n jẹ́ ìjòyè ìlú. Àwọn wọ̀nyí ni a mọ̀ sí Àgbà-Ifẹ̀ tàbí Ìlàrẹ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn mìíràn máa ń pè wọ́n ní Ìwàrẹ̀fà.
Àwọn olóyè ìlú náà ni:

- Ọbalúfẹ̀/Ọ̀rúntọ́ tí ó ń gbé ní Ìrẹ̀mọ
- Ọbajió ni tirẹ̀ ń gbé ní Mọ̀rẹ̀
- Ọbalọràn tí ń gbé ní Ìlódè
- Ọwájagun-ọṣìn ló ń ṣàkóso Ẹnuwá

- Waasin ló ń mójútó Ìlàrẹ̀
- Ọnalaàyè ni tirẹ̀ wà ní Ìránjé
- Ejesi ni ó ń ṣàkóso Ọ̀gbọ́ndo bẹ́ẹ̀ ni
- Akọgun ni ó ń mójútó Òkèrèwé

## 4.3 Ìjọba Ìbílẹ̀ Ìlú Ọ̀yọ́:

Alààfin ni baba gbogbo wọn nítorí òun ni olórí. Wọn kò gbọdọ̀ dárúkọ rẹ̀ lásán ní ayé àtijọ́. Ẹnikẹ́ni tí ó bá dán an wò, yóò dán an tán. Àtirandéran ni oyè aláàfin ní ayé àtijọ́ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kì í ṣe oyè baba sí ọmọ. Àrèmọ ló máa ń jẹ oyè tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n èyí ti yí padà nítorí èyí fa ìjà ní Ọ̀yọ́ nígbà náà. Níwọ̀n ìgbà tí àrẹ̀mọ kò le jẹ ọba mọ́, èyí fa ayé ìjẹkújẹ fún àwọn àrẹ̀mọ ọba.

Aláàfin ní àwọn alákòóso ìlú tí a mọ̀ sí Ọ̀yọ́mèsì ti orúkọ oyè wọn ń jẹ́

- Ọsọ̀run/Baṣọ̀run
- Sàmù
- Àgbà-akin
- Alápinni (ó wà fún òrìṣà eégúngún)
- Lagunnà (ó wà fún òrìṣà-oko)
- Aṣípa
- Akínikú

Oyè ìdílé ni ti àwọn olóyè wọ̀nyí náà ṣùgbọ́n kì í ṣe oyè tí ọmọ le jẹ́ lẹ́yìn ikú baba rẹ̀. Àwọn wọ̀nyí ni wọ́n máa ń sọ ọ̀rọ̀ ti ìlú bá fẹ́ sọ. Àwọn Ẹ̀sọ́ tún ṣe pàtàkì láyé àtijọ́, bẹ́ẹ̀ ni olórí wọn ni a ń pè ní Aarẹ-Ọ̀nà-Kakaǹfò.
Ní ayé àtijọ́, ìlú Ọ̀yọ́ ní àwọn ìlú àmọ̀nà tí wọ́n wà lábẹ́ Aláàfin. Èyí ni àwọn ìlú ìgbèríko, Baálẹ̀ ni ó sì máa ń sàkóso wọn. Àpẹẹrẹ àwọn ìlú bẹ́ẹ̀ àti Baalé wọn níwọ̀nyí?

| | | |
|---|---|---|
| 1. | Ìbàdàn - | Olúbàdàn |
| 2. | Ìsẹ́yìn - | Aṣẹ́yìn |
| 3. | Ìkòyí - | Oníkòyí |
| 4. | Òwu - | Olówu |
| 5. | Ìwo - | Olúwòó |

## 4.4 Ètò Ìjọba Ìbílẹ̀ Ẹ̀gbá

Ẹ̀gbá ní ìlú tí ó pọ̀ ṣùgbọ́n ọba ìlú kọ̀ọ̀kan dá dúró ní tirẹ̀ nígbà náà. Àwọn ọba wọ̀nyí kàn wà lórí ìtẹ́ ni, wọn kì í ṣe nínú ètò ìjọba tàbí ìṣèlú. Àwọn tí ń ṣe ìlú gan-an ni àwọn Ògbóni.
Àwọn tí ó jẹ́ ọlọ́lá àti abẹnugan, ti ẹnu wọn tólẹ̀ ni wọ́n máa ń wà nínú ẹgbẹ́ Ògbóni, bẹ́ẹ̀ ni àwọn àgbà ọkùnrin àti obìnrin ni wọ́n máa ń wà nínú ẹgbẹ́ náà.
Àwọn Ògbóni ni ó máa ń yan ọba sí orí oyè, bí ìwà ọba kan kò bá tẹ́ ìlú lọ́rùn mọ́, àwọn ẹgbẹ́ Ògbóni ni yóò dájọ́ fún un pé kí ó lọ sùn. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú, àwọn ìlú tí ó pọ̀ ni wọ́n kó ara wọn jọ sí Abẹ́òkúta, bẹ́ẹ̀ ni ogun Fúlàní tí ó tú Ọ̀yọ́ wá sí ìsàlẹ̀ ni ó fa ìkórajọ yìí. Níbí ni a ti rí Ẹ̀gbá Aláké tí ìlú wọn wà ní Aké. Àwọn wọ̀nyí ló parapọ̀ tí Aláké sì jẹ́ olórí wọn, ṣùgbọ́n àwọn Òwu àti

Gbágùrá ní ọba tiwọn. Àwọn Gbágùrá yìí kò jìnnà sí Ọ̀yọ́ tẹ́lẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni Ìdó tí í ṣe olú-ìlú wọn tẹ́lẹ̀ kò jìnnà sí Ìbàdàn. Àwọn ìlú Ẹ̀gbá mìíràn tí wọ́n tún darapọ̀ mọ́ Aké lónìí ni Ẹ̀gbá Òkè-Ọnà tí ọba wọn ń jẹ́ Òsilẹ̀ àti Ẹ̀gbá Ìgbẹ̀yìn tí Olú-ìlú wọ́n wà ní Òkò.
Àwọn Ẹ̀gbá Òwu ló dé Abẹ́òkúta ni ọdún 1831 lẹ́yìn ìjà tí ó ṣẹ̀lẹ̀ láàrin àwọn àti Apòmù. Èyí ní ó sì mú kí Apòmù jó ilé àwọn Òwu ráúráú. Àwọn Ògbóni ni ó ń ṣèlú ní Abẹ́òkútà bẹ́ẹ̀ ni orò ni wọ́n fi máa ń gbé ẹni tí kò bá ṣe tiwọn tí wọ́n sì fẹ́ pa á.
Nígbà tí àwọn Ẹ̀gbá wọ̀nyí parapọ̀ sí Abẹ́òkúta tán, tí ó sì di dandan fún wọn láti máa ṣèlú papọ̀, ń ṣe ni wọ́n ń yan olóyè ní àdúgbò kọ̀ọ̀kan. Bí àpẹẹrẹ:

1. Aláké ni wọ́n máa ń yàn ní Aké
2. Ìgbórè máa ń yan Pàràkòyí
3. Ìjẹmọ máa ń yan Olúwo-Ifá
4. Ìjẹmọ máa ń yan Babalórò (Ológbò-Ìjeùn)

## 4.5 Ìjọba Ìbílẹ̀ Láàrin Àwọn Ìjẹ̀ṣà:

Ọwá ni ọba àwọn Ìjẹ̀ṣà ń jẹ́. Ó ní àwọn Ìwàrẹ̀fà mẹ́fà, èyí tí mẹ́tà nínú wọn wà ní ìgboro Iléṣà. Àwọn ìwàrẹ̀fà tí ó wà ní ìgboro Iléṣà yìí ni Ọbańlá, Ògbóni Iléṣà àti Ọba Odò. Àwọn mẹ́ta tí ó wà ní agbègbè Iléṣà ni Ògbóni ti Ìjẹ̀bú-Jẹ̀sà, Ògbóni ti Ìbòkun àti Ògbóni ti Ìpolé.
Àwọn olóyè mìíràn ni Ọ̀dọlé, Rísáwẹ̀, Lórò àti Arápatẹ́ bẹ́ẹ̀ ni àwọn olóyè ìsọ̀rí kẹta ni Lọ́jọka, Lẹ́jòfi, Lọ́ọ̀kiràn àti Risinkin. Lẹ́yìn àwọn wọ̀nyí ni Ọlọ́jà méje ti Òkèbode. Àwọn Ẹmẹṣẹ̀ náà jẹ́ ìránṣẹ́ fún Ọwá. Wọ́n lè mú nínú àwọn ọmọ olóyè ìlú láti fi ṣe Ẹmọṣẹ̀ kí wọ́n lè mọ bí wọ́n ṣe ń ṣèlú lọ́jọ́ iwájú.

## 4.6 Ìjọba Ìbílẹ̀ Èkìtì àti Ìjẹ̀bú:

Ọba mẹ́rìndínlógún ni àwọn Èkìtì wọ́n ní láyé àtijọ́. Nínú wọn ni:

- Òrè ti Ọ̀tùn
- Ewí ti Adó
- Ògògà ti Ìkẹ́rẹ́
- Ẹlẹ́kọ̀lé ti Ìkọ́lé
- Ọlọ́yẹ́ Ọyẹ́
- Ọ̀gọ̀tún ti Ọ̀gọ̀tún
- Ajerò ti Ìjerò
- Ọwá ti Òbó
- Alárá ti Arámọkọ
- Alàáyè ti Ẹfọ̀n Alàáyè
- Ọlọ́tùn ti Ọ̀tùn
- Olójùdó ti Ìdó
- Onítají ti Ìtaji
- Ọwá ti Okèèmẹ̀sí
- Onísan ti Ìsán
- Arìnjalẹ̀ ti Ìṣẹ̀

Ní orílẹ̀ Ìjẹ̀bú, Awùjalẹ̀ ni ilẹ̀ Ìjẹ̀bú-Òde. Àwọn Agunrin ni wọ́n máa ń fún ọba ní ìmọ̀ràn. Àwọn Ògbóni (Oṣùgbó) náà jẹ́ olùdámọ̀ràn fún ọba. Àwọn Ògbóni Pampa (Olópéère) náà wà, bẹ́ẹ̀ ni àwọn Lámurén náà máa ń gba ọba ni ìmọ̀ràn. Àwọn Lámurén yìí tilẹ̀ súnmọ́ ọba ju àwọn yòókù lọ.
Yàtọ̀ sí èyí tí a mẹ́nubà nípa àwọn Ìjẹ̀bú lókè yìí, a kò ní í sàì mẹ́nubà á pé àwọn Ẹgbẹ́ awo kan náà wà ní ilẹ̀ Yorùbá tí wọ́n ń kó ipa pàtàkì nínú ìṣèlú Yorùbá láyé àtijọ́. Bí àpẹẹrẹ, ẹgbẹ́ Ọdẹ ni ó máa ń jagun fún ìlú, bẹ́ẹ̀ ni àwọn náà ni wọ́n máa ń lò láti ṣe amí tàbí láti ṣe ìwádìí ohun tí ó bá sẹlẹ̀.
Àwọn Ẹgbẹ́ mìíràn ni Ẹgbẹ́ Ògbóni. Àwọn Ẹgbẹ́ yìí ń kópa pàtàkì nínú òṣèlú ìbílẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́. Ní ìlú mìíràn, àwọn Ògbóni ni wọ́n máa ń yan ọba bẹ́ẹ̀ ni àwọn ni wọ́n máa ń dín agbára ọba kù. Yàtọ̀ sí àwọn Ògbóni, a le lo Egúngún bí a bá fẹ́ ṣe ìdájọ́ pàtàkì tàbí kí wọ́n lò wọ́n láti fi dá sẹ̀ríà fún àwọn ọ̀daràn. Ẹgbẹ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ náà máa ń kópa nínú ìdájọ́ fún àwọn ọ̀daràn nílùú. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n le lo Ṣàngó láti fi ìyà jẹ ẹlẹ́sẹ̀. Bákan náà, Òrìṣà-Oko máa ń fi ìyà jẹ àwọn tó ṣe búburú ní àwùjọ.

## 5.0 Ìsọnisókí

Nínú ìpín yìí ni o ti rí ìṣepàtàkì ìdílé nínú ètò àti ìlànà ìjọba ìbílẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́. A kọ́ ẹ̀kọ́ lára àwọn ẹ̀yà Yorùbá kọ̀ọ̀kan tí a kọ́ nípa wọn pé wọ́n máa ń ṣe ètò òṣèlú wọn lọ́nà tí ó ń mú àlàáfíà àti ìsọ̀kan bá àwùjọ Yorùbá. A fihàn nínú ìpín yìí pé etò ìdílé ṣe pàtàkì nínú àtimú kí àlàáfíà jọba ní àwùjọ. Àkójọpọ̀ ìdílé ló ń parapọ̀ di ìletò, tí ìletò bẹ́ẹ̀ sì ń ní olórí. Ní ayé àtijọ́, a rí i pé àwọn ẹ̀yà Yorùbá máa ń yan olórí wọn ní pẹ̀lẹ́pùtù láìsí gbọ́n-síi-omi-ò-tóo. Èyí sì máa ń mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ.
Àwọn Ẹgbẹ́ Awo tàbí ìmùlẹ̀ bí ẹgbẹ́ Ògbóni, ẹgbẹ́ Ọdẹ, àwọn Eléégún náà máa ń kópa pàtàkì nínú ìṣejọba ìbílẹ̀ ní àtijọ́, èyí tí kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́ lónìí. A tún ní ìmọ̀ nípa Ìṣèjọba àwọn ìlú mélòó kan ní ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́, a sì tan ìmọ́lẹ̀ sí onírúurú oyè ọba ni ìlú kọ̀ọ̀kan.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe:

1. Ṣàlàyé pàtàkì ìdílé nínú ètò òṣèlú ìjọba ìbílẹ̀ ní ayé àti lóde òní.
2. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ojú ká bí ọ́-òsí ni a máa fi ń wo ọba láyé àtijọ́, ǹjẹ́ gbólóhùn yìí rí bẹ́ẹ̀ lóòótọ́?
3. Ǹjẹ́ o rò pé àṣà ọba sì ń múlẹ̀ lóde òní bí i ti àtijọ́ mọ́?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adeoye, C.L. *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá.* Ibadan, Oxford University Press (Nig) Ltd.
Bíòbákú, S.O. 1973. *Sources of Yorùbá History.* Oxford, Oxford University Press.
Johnson,S. 1921. *History of the Yorùbás.* Lagos, C.M.S.
Ládélé, T.A.A. et al. *Àkọ́jọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ibadan, Gavima Press Ltd.
Ojo, J.A. 1966 *Yorùbá Culture.*
Daramọlá, O & Jẹjẹ, A. 1968. *Àwọn Àsà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.*. Ibadan, Onibọn-Òjé Press &
Book industries, (Nig) Ltd.

## MÓDÙ KẸTA

## ÌPÍN KEJÌ: IṢẸ́ ÌSẸ̀ŃBÁYÉ YORÙBÁ

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Iṣẹ́ Àgbẹ̀
4.2 Iṣẹ́ Ọdẹ
4.3 Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ Ògún
4.4 Aṣọ Híhun
4.5 Iṣẹ́ Epo Fífọ̀
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Yorùbá bọ̀, wọ́n ni iṣẹ́ lòògùn ìṣẹ́. Ẹnikẹ́ni tí ó bá jẹ́ ẹ̀dá alààyè gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́ kan tàbí òmíràn. A ó wo iṣẹ́ àgbẹ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí ó ṣe pàtàkì jù lọ, bẹ́ẹ̀ ni a ó mẹ́nubà iṣẹ́ epo fífọ̀, iṣẹ́ aró dídá àti iṣẹ́ aṣọ híhun. Èyí nìkan kọ́, a ó ṣe àlàyé lórí iṣẹ́ àrọ̀ èyí tí ó jẹ́ iṣẹ́ alágbára tí ó sì ní wàhálà nínú díẹ̀, bẹ́ẹ̀ a ó wo iṣẹ́ ọdẹ lóríṣìíríṣìí ní ayé àtijọ́. A ó ṣe àlàyé bí ìyípadà dé bá àwọn iṣẹ́ ìṣèǹbáyé wọ̀nyí lóde òní, a ó tún mẹ́nuba ìwúlò wọn àti ọ̀nà tí a lè gbà mú kí wọ́n dára sí i.

### 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Èròǹgbà pàtàkì lórí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni kẹ́ kí o:

- Ní óye nípa àwọn iṣẹ́ ìsẹ̀ǹbáyé Yorùbá
- Mọ̀ nípa ìyípadà tí ó ń dé bá ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí
- Rí iṣẹ́ àgbẹ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí ẹnìkọ̀ọ̀kan gbọ́dọ̀ nífẹ̀ẹ́ sí láti ṣe
- Le wòye ọ̀nà láti mú ìdàgbàsókè bá ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí.

### 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Ṣàlàyé lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ pàtàkì àti ìwúlò iṣẹ́ àgbẹ̀ ní gbogbo àgbáyé
2. Kín ni o mọ̀ nípa iṣẹ́ aṣọ híhun àti pé kín ni ìdí tí wọ́n fi ń pe aṣọ àfi ní aṣọ òkè?

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Iṣẹ́ Àgbẹ̀:

Àwọn iṣẹ́ ìṣẹ̀nbáyé àwọn Yorùbá pọ̀ bí yanrìn etì òkun ni, ṣùgbọ́n àwọn iṣẹ́ pàtàkì kan wà tí ìwàláàyè ẹ̀dá ènìyàn rọ̀ mọ́ típẹ́típẹ́. Ọ̀kan lára àwọn iṣẹ́ yìí ni

iṣẹ́ àgbẹ̀. Bí kò bá sí àgbẹ̀, ìwàláàyè ẹ̀dá ènìyàn yóò fi orí sánpọ́n ni. Láìsí iṣẹ́ àgbẹ̀, kò sí oúnjẹ tí ará ìlú yóò jẹ. Nítorí náà, iṣẹ́ àgbẹ̀ yìí ni a le sọ pé ó ṣe pàtàkì jù lọ nínú iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé pàápàá láàrin àwùjọ Yorùbá.
Apá ibi tí ènìyàn gbé ni yóò ni yóò sọ irúfẹ́ iṣẹ́ àgbẹ̀ tí yóò ṣe nítorí pé oríṣìíríṣìí ilẹ̀ ni ó wà. Bí ilẹ̀ igbó ṣe wà bẹ́ẹ̀ ni ilẹ̀ pápá wà pẹ̀lú. Nínú ilẹ̀ igbó, níbi tí àwọn Yorùbá pọ̀ sí, wọ́n máa ń gbin oríṣìíríṣìí nǹkan ọ̀gbìn bíi kòkó, obì, ọ̀gẹ̀dẹ̀, iṣu, ẹ̀wà ní onírúurú. Ní ẹsẹ̀ odò, a máa ń rí àwọn àgbẹ̀ apẹja níbẹ̀.
Ní ilẹ̀ Yorùbá, iṣẹ́ àgbẹ̀ ni ó gbòòrò jù lọ nínú gbogbo àwọn iṣẹ́ yòókù. Iṣẹ́ yìí ni ó ń so ẹ̀mí ró, bẹ́ẹ̀ ni iṣẹ́ yìí kò rẹ̀yìn láàrin gbogbo iṣẹ́ yòókù títí di òní olónìí. Bí àwọn àgbẹ̀ yìí ṣe ń dá oko ẹgàn, èyí ni oko tí ẹnikẹ́ni kò tí ì dá rí, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń dá oko etílé. Nínú oko yìí ni wọ́n ti máa ń gbin ohun ọ̀gbìn bí i kòkó, obì, àgbọn, èyí tí ó máa ń wà fún ọjọ́ pípẹ́. Yàtọ̀ sí oko etílé, oko ẹgàn máa ń jìnnà sí ilé púpọ̀. Nítorí náà, bí àgbẹ̀ bá lọ ní òwúrọ̀, alẹ́ ni wọ́n máa ń padà sílé. Ní ayé àtijọ́, àwọn àgbẹ̀ kì í fi iṣẹ́ wọn jáfara nítorí pé oko ni ẹ̀mí àgbẹ̀.

## 4.2 Iṣẹ́ Ọdẹ

Ọdẹ ṣíṣe jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́ pàtàkì nínú iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá. Ìtàn àtẹnudétí kan sọ pé Ògún ni ó dá iṣẹ́ ọdẹ sílẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀. Ọlájubù (1975:125) jẹ́ kí á mọ̀ pé kì í ṣe iṣẹ́ ọdẹ yìí nìkan ni ògún máa ń ṣe nígbà ayé rẹ̀. A sọ fún wa pé ó máa ń ṣe iṣẹ́ àgbẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni ó máa ń jagun pẹ̀lú.
Ní ayé àtijọ́ àwọn ọdẹ àtijọ́, ni wọ́n máa ń sọ́ ìlú láti dáàbò bo àwọn ènìyàn lọ́wọ́ ọ̀tá àti àwọn ọ̀daràn gbogbo. Lára àwọn ohun tí àwọn ọdẹ sábà máa ń lò ní ìbọn, ọfà, irin kùmọ̀ àti òkúta. Àwọn ọdẹ tí ó gbójú máa ń lo oògùn tí ó dájú bíi egbé, àjàbò, àfẹ́ẹ̀rí, àfọ̀ṣẹ àti ìdíwọ́ ẹranko tí wọ́n máa ń lò láti ki èékánná ẹranko abìjà bí ẹkùn, àmọ̀tẹ́kùn àti kinnìún wọlé. Ọdẹ tí kò bá ní irú àwọn nǹkan aájò báyìí yóò rí ìbínú ẹranko abìjà bẹ́ẹ̀.
Àwọn ọdẹ kéékèèkéé kan wà tí wọ́n máa ń sọdẹ àwọn ẹranko àti ẹyẹ kéékèèké kiri nínú oko etílé. Irú àwọn wọ̀nyí ni wọ́n máa ń dẹ ẹ̀bìtì, irín, pàkúte, gbóró, ìgógó, àtẹ̀, ajá àti ògi láti fi pa ẹran, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kì í ṣe gbogbo ẹranko ni wọ́n le pa.
Wàyí o, àyípadà tí ń dé bá iṣẹ́ ọdẹ ṣíṣe ní àkókò ti wa yìí. Àwọn ọdẹ yìí tún máa ń lo ọfà àti àkàtàǹpó láti ta mọ́ ẹranko tí ó bá jìnnà sí wọn díẹ̀. Àwọn ọdẹ ìwòyí kò dàbí ọdẹ àtijọ́, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò pọ̀ tó àwọn ọdẹ ìgbàanì nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ igbó ló ti di aṣálẹ̀.
Ìṣòro pọ̀ nínú iṣẹ́ ọdẹ, bẹ́ẹ̀ ni onírúurú ìyà ni ọdẹ máa ń jẹ nínú igbó. Yàtọ̀ sí ebi pípa, àwọn kòkòrò olóró mìíràn tún máa ń gé ọdẹ jẹ, èyí tí ó le fa títa ríro fún un. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé "ọdẹ ìbá ròṣẹ́, ròyà, bí ó bá pẹran, ìbá tí fẹ́nìkankan jẹ.

## 4.3 Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ Ògún

Iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ jẹ́ iṣẹ́ tí àwọn oníṣẹ́ yìí máa ń rọ irin, ọkọ́, àdá, ìbọn ọ̀kọ̀ àti àwọn ohun èlò irin mìíràn yálà fún lílò àwọn àgbẹ̀ tàbí àwọn ọdẹ. Ó jẹ́ irúfẹ́ iṣẹ́ ọnà tí ó jẹ mọ́ Ògún.
Ọ̀rọ̀ yìí jẹ yọ nínú ọ̀rọ̀ méjì yìí – àgbẹ̀ àti ọdẹ.
Nígbà tí a fẹ́ pa ọ̀rọ̀ kejì yìí (ọdẹ) jẹ́, tí a sì sún àgbẹ̀ mọ́ ọn papọ̀, tí ó sì di àgbẹ̀dẹ. Èyí ni pé àwọn ọ̀rọ̀ méjì tí a súnpọ̀ yìí 'àgbẹ̀+ọdẹ' ni ó di àgbẹ̀dẹ nípa ìlànà ìpajẹ àti ìsúnkì.

Àwọn alágbẹ̀dẹ ni ó máa ń rọ àwọn ohun èlò tí àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ máa ń lò fún iṣẹ́ wọn. Nítorí náà, bí kò bá sí alágbẹ̀dẹ, àwọn àgbẹ̀ àti àwọn ọdẹ kì bá ní ìṣòro nípa ohun èlò wọn.

## 4.4 Iṣẹ́ Aṣọ Híhun

Gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé Akínyẹmí (1989:38) ti sọ, kò sí àwọn ẹ̀yà ènìyàn kan ní àgbáyé tí wọn kì í lo aṣọ fún ìdáàbò bo ara wọn. Ṣùgbọ́n, àwọn aṣọ tí a fi ń dáàbò bo ara ẹni wọ̀nyí máa ń yàtọ̀ láti agbègbè kan sí òmíràn.
Láàrin àwọn Yorùbá, wọ́n máa ń hun aṣọ ìbílẹ̀ kan tí wọ́n ń pè ní òfì tàbí aṣọ òkè. Ìdí tí wọ́n fi ń pè é ni aṣọ òkè ni pé ní apá Òkè-ògùn ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ ni wọ́n ti máa ń hun aṣọ yìí, bẹ́ẹ̀ ni aṣọ òkè yìí gbajúmọ̀ bí ìsáná ẹlẹ́ẹ́ta ní gbogbo tìbú tòòró ilẹ̀ Yorùbá. Ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú àwọn aṣọ òkè wọ̀nyí ni ó ní orúkọ tí a fi máa ń dá wọn mọ̀. Lára àwọn aṣọ òkè tàbí òfì tí ó lórúkọ ní àwùjọ Yorùbá ni Sányán, Etù, Àlàárí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
Ìlú Ìṣẹ́yìn ni a mọ̀ bí ìlú tí a ti ń hun aṣọ òfì, bẹ́ẹ̀ ìlú Ìṣẹ́yìn yìí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìlú olókìkí ní apá Òkè-ògùn tí ó wà ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ báyìí. Yàtọ̀ sí iṣẹ́ àgbẹ̀ tí ó jẹ́ àbọ̀ṣẹ́ fún wọn, iṣẹ́ aṣọ híhun yìí ni tọmọdé tàgbà nínú ìlú yìí yàn láàyò. Láyé àtijọ́, ẹnikẹ́ni tí kò bá ní aṣọ òfì kò tí ì wà ní ààrin àwọn gbajúmọ̀, nítorí pé kò sí aṣọ tí ó lè bá aṣọ òfì ta kàn-ǹgbọ̀n ní àwùjọ aṣọ. Àwọn Yorùbá sábà máa ń lo aṣọ òfì ní àsìkò ìgbéyàwó, níbi ìsìnkú àgbà, níbi ìfinijoyè àti àwọn ayẹyẹ pàtàkì mìíràn.
Lóde òní, aṣọ òfì sì níyì láwùjọ aṣọ Yorùbá bẹ́ẹ̀ ni kì í ṣe Ìṣẹ́yìn nìkan ni wọ́n ti ń hun aṣọ òfì lónìí. Híhun rẹ̀ ti gbalé gboko. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ Ìṣẹ́yìn tilẹ̀ ti lọ sí àwọn ìlú ńlá-ńlá tí ó yi wọn po láti máa hun aṣọ yìí, kí ó le rọrùn láti tètè tà á. Oríṣìíríṣìí àrà ni àwọn aránṣọ (tẹ́lọ̀) ń fi aṣọ òfì yìí rán lónìí. Yàtọ̀ sí gbárìyẹ̀ tàbí dàńdógó, wọ́n tún fi ń rán aṣọ Òyìnbó bíi kóòtù (Coat), ṣẹ́ẹ̀tì àti sòkòtò (shirt & trouser).

## 4.5 Iṣẹ́ Epo Fífọ̀

Iṣẹ́ tí àwọn obìnrin máa ń ṣe ni iṣẹ́ epo fífọ̀ jẹ́. A ó rántí pe lára igi ọ̀pẹ ni a ti máa ń ri epo pupa, tí a fi máa ń ṣe oríṣìíríṣìí nǹkan, pàápàá jù lọ ọbẹ̀ tí a ń jẹ. Oríṣìí ọ̀pẹ méjì ni ó wà – ọ̀pẹ Ifá àti ọ̀pẹ epo ìsebẹ̀. Ọ̀pẹ Ifá ni ọ̀pẹ tí àwọn babaláwo máa ń lò fún ikín Ifá. Ẹyìn ọ̀pẹ yìí kò dára fún epo jíjẹ nítorí pé ó máa ń ru nínú ọbẹ̀ ni. Ọ̀pẹ kejì ni ọ̀pẹ tí a máa fi ń ṣe epo jíjẹ àti àwọn ọsẹ lónírúurú. Ìran Arẹsà tí ó jẹ ọ̀kan lára ìran Yorùbá ni a máa ń tọ́ka sí pé àwọn ni wọ́n máa ń ṣiṣẹ́ epo fífọ̀. Ó jẹyọ nínú oríkì orílẹ̀ wọn pé iṣẹ́ epo fífọ̀ kì í sábàá jẹ́ kí ọmọbìnrin Ìrẹ̀sà gbé ilé ọkọ.
Ní òde òní, iṣẹ́ epo fífọ̀ kò rẹ̀yìn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pẹ kò wọ́pọ̀ nínú igbó mọ́. Wọn kò gbin ọ̀pẹ mìíràn pààrọ̀ mọ́ bẹ́ẹ̀ àwọn adẹ́mu tún ń gé èyí tí ìbá wúlò fún epo pupa. Ṣùgbọ́n sá o, epo lílò fún ọbẹ̀ ṣe pàtàkì lónìí bẹ́ẹ̀ ni àwọn obìnrin tí ń ṣiṣẹ́ epo fífọ̀ sì ń bá iṣẹ́ wọn lọ.

## 5.0 Ìsọnísókí

Nínú ìpín yìí ni a ti ṣe àlàyé nípa pàtàkì iṣẹ́ àgbẹ̀ láàrin àwọn ènìyàn àgbáyé àti pàápàá jù lọ láàrin àwọn Yorùbá. A ṣe àlàyé pé iṣẹ́ àgbẹ̀ jẹ́ iṣẹ́ tí ó kọ́kọ́ ti wà ní ìpilẹ̀ṣẹ̀ ayé àti pé iṣẹ́ yìí ni ó ń pèsè oúnjẹ fún ẹ̀dá ènìyàn. Yàtọ̀ sí iṣẹ́ àgbẹ̀ yìí, a

mẹ́nuba iṣẹ́ ọdẹ èyí tí ó ń pèsè ẹran jíjẹ fún àwọn ènìyàn, bẹ́ẹ̀ ni àlàyé wá lórí bí iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ ṣe jẹ́ iṣẹ́ tí ó pa àwọn àgbẹ̀ àti ọdẹ pọ̀ àti àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin wọn. Lẹ́yìn èyí, a wo iṣẹ́ aṣọ híhun bí ó ṣe máa ń dáàbò bo àṣírí ara ènìyàn, bẹ́ẹ̀ ni a wo pàtàkì iṣẹ́ epo fífọ̀ láyé àtijọ́ àti lóde òní.

A ṣe àlàyé nípa iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ tí ó kó iṣẹ́ méjì àkọ́kọ́ yìí pọ̀ àti bí iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ ṣe ṣúyọ nínú ìbáṣepọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ àti ọdẹ tí á súnkì di àgbẹ̀dẹ. Iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ yìí sì ń tẹ̀síwájú lóde òní bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé kò fi bẹ́ẹ̀ fẹjú tó ti àtijọ́.

Ní ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti mẹ́nuba iṣẹ́ aṣọ híhun àti iṣẹ́ epo fífọ̀ èyí tí wọ́n ń fẹjú sí i lóde òní, tí wọ́n sì ń tàn kálẹ̀ orílẹ̀-èdè àgbáyé.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe:

1. Dárúkọ àwọn ohun mẹ́rin tí àwọn àgbẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá máa ń gbìn àti agbègbè tí wọ́n ti ń gbìn wọ́n.
2. Ṣe àlàyé lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́ nípa iṣẹ́ ọdẹ àti ipa tí àwọn ọdẹ ní ìlú ní ayé àtijọ́ àti lóde òní
3. Ìbátan àti ìbáṣepọ̀ wo ni ó wà láàrin iṣẹ́ àgbẹ̀, iṣẹ́ ọdẹ àti iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ ní ayé àtijọ́. Ìyípadà wo ni ó dé bá wọn lóde òní?
4. Ǹjẹ́ ìpèsè epo pupa sí wúlò ní ayé tiwa yìí níwọ̀n ìgbà tí epo àti òróró ti gbòde kan?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Ilesanmi, T.M. 1989. *Iṣẹ́ Ìṣẹ̀ǹbáyé.* Ilé_Ifẹ̀, University of Ifẹ Press Ltd.

Daramọla, O. & Jẹjẹ, A. 1968. *Àwọn Àṣà àti òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá.* Ibadan, Onibọn-Òjé Press & Book Industries (Nig) Ltd.

Ladele, T.A.A. et al 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ibadan, Gavima Press Ltd.

Olajubu, O. 1975. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* Ibadan, Longman.

# MÓDÙ KẸTA

## ÌPÍN KẸTA: IṢẸ́ ÌBÍLẸ̀ YORÙBÁ 2

### Àkóónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Iṣẹ́ Ohùn Pípè
4.2 Iṣẹ́ Ìsẹ̀gùn
4.3 Iṣẹ́ Arọ́
4.4 Iṣẹ́ ìkòkò Mímọ
4.5 Iṣẹ́ ọṣẹ Dúdú
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Gẹ́gẹ́ bí a ti ń bá a bọ̀ nínú ìpín kejì, módù kẹta yìí, a rí i pe iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá pọ̀ jáǹtirẹrẹ, ṣùgbọ́n ìwọ̀nba díẹ̀ ni a le mẹ́nubà nínú módù yìí.
Lẹ́yìn àwọn iṣẹ́ àgbẹ̀, iṣẹ́ ọdẹ àti iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ-Ògún tí a ti mẹ́nubà nínú ìpín kejì, a ó tún ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn iṣẹ́ bíi iṣẹ́ ohùn pípè, iṣẹ́ ìṣègùn, iṣẹ́ arọ́, iṣẹ́ ìkòkò mímọ àti iṣẹ́ ọsẹ dúdú. Lẹ́yìn tí a bá sọ̀rọ̀ lórí iṣẹ́ ohùn pípè tán, a ṣe àlàyé díẹ̀ lórí iṣẹ́ ìṣègùn ní ààrin àwọn Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni a mẹ́nuba iṣẹ́ irin rírọ àti wíwà tí a mọ̀ sí iṣẹ́ arọ́. Lẹ́yìn náà ni a wò ó bí a ṣe ń mọ ìkòkò amọ̀ tí a fi máa ń ṣe kete omi, ìsáàsùn ọbẹ, àmù tí a ń pọn omi sí. Ní ìparí ni a sọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ ọsẹ dúdú tí a fi ń wẹ̀ àti àdí tí a fi ń para.

### 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Èròǹgbà wa lórí ìpín yìí ni láti jẹ́ kí o:

- Ní ìmọ̀ kíkún lórí bí Yorùbá ṣe ń fi ohùn pípè ṣe iṣẹ́ òòjọ́ wọn láyé àtijọ́.
- Mọ̀ bí Yorùbá ṣe ń mójútó ìlera ara wọn kí àwọn Òyìnbó tó dé
- Mọ àwọn ọ̀nà tí àwọn baba-ńlá wa ń gbà wa irin láyé àtijọ́
- Ní òye bí àwọn Yorùbá ṣe ń mọ ìkòkò àti ìwúlò rẹ̀ nígbàanì.
- Lè mọ̀ bí a ṣe ń tọ́jú àwọ̀ ara wa pèlú ọsẹ àbùwẹ̀ dúdú ai ìpara àdí.

### 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. ‘Ìlera lọrọ̀’ nítòótó. Dá sí ọ̀rọ̀ yìí nípa sísọ ìwúlò àti pàtàkì ìsègùn ìbílẹ̀ Yorùbá.
2. Ǹjẹ́ ọkọ́ àti àdá wúlò fún iṣẹ́ àgbẹ̀ mọ́ lóde òní?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Iṣẹ́ Ohùn Pípè

Ohùn pípè gẹ́gẹ́ bi iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé ṣe pàtàkì púpọ̀ láàrin àwọn Yorùbá. A ó ṣe àkíyèsí pé ọ̀rọ̀ sísọ ní àwọn ìlànà kan tí lè gbà sọ ọ́ tí yóò wu àwọn olùgbọ́ lórí, bẹ́ẹ̀ ni kì í ṣe gbogbo ènìyàn ni ó le sọ̀rọ̀ tí ń tanilára. Kì í ṣe gbogbo ènìyàn ló le sọ̀rọ̀ kí ẹnu wọ́n dá sáká láwùjọ òǹpèdè.
Bí a bá ṣe àkíyèsì dáadáa, àkọsínú ni àwọn baba-ńlá wà mọ̀, wọn kò mọ àkọsílẹ̀. A ó rí i pé ọ̀tọ̀ ni ọ̀rọ̀ ẹnu àwọn ọlọgbọ́n àti olóye, bẹ́ẹ̀ ni gbólóhùn òmùgọ̀ máa ń fa ẹ̀tẹ́ láàrin àwùjọ ni. nítorí náà, ẹni tí yóò pèdè láàrin àwọn Yorùbá ní láti kọ́ ẹ̀kọ́ bí a ti í sọ̀rọ̀ tí yóò rú àwọn ènìyàn sókè ni àwùjọ àwọn pèdèpèdè. Níwọ̀n ìgbà tí kò ti sí àkọsílẹ̀ gbóógì kí àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun tó dé, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye ni a fi pamọ́ sínú ohùn pípè. Èyí máa ń jẹyọ nínú ìrírí àyíká ẹni fún ọjọ́ pípẹ́ nítorí pé àwọn Yorùbá máa ń sábà kíyèsí ìhùwàsí àti ìsesí àwọn ẹ̀dá alààyè tó yí wọn ká. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n mọ ìwúlò àti ìhùwàsí ewé, èèpo, egbò àti ẹ̀so igi, bẹ́ẹ̀ ni ti àwọn ẹranko lóríṣìíríṣìí bí ejò, ẹyẹ, wọ́n si máa ń kíyèsí ìbáṣepọ̀ tó máa ń wà láàrin àwọn ẹ̀dá yòókù.
A máa ń rí ọgbọ́n òye àwọn akéwì nínú ìgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ wọn nínú ewì, ìsàré àti orin. Àwọn wọ̀nyí máa ń fi ewì, ìsàré tàbí orin dárà nígbà tí wọ́n bá ń pèdè tó jẹmọ́ ìrírí àyíká wọn. Àwọn wọ̀nyí lè fi èdè dárà bí ó ṣe wù wọ́n yàtọ̀ sí bí àwọn òǹsọ̀rọ̀ lásán yóò ṣe gbé ọ̀rọ̀ wọn kalẹ̀.
A máa ń bá àwọn tí ń fi ohùn pípè pàdé nínú ìjàlá aré Ògún, oríkì, orin kíkọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Yàtọ̀ fún àjogúnbá, àwọn tí wọ́n ń fi ohùn pípè ṣe iṣẹ́ máa ń kọ́ ọ láti kékeré ni. Bí a tilẹ̀ rí nínú wọn tí ó jogún ìmọ̀ yìí, wọ́n sábà máa ń tẹ̀síwájú nínú ẹ̀kọ́ ohùn pípè lọ́dọ̀ àwọn tí ó tún ní ẹ̀bùn yìí jù wọn lọ. Èyí lè jẹ mọ́ ìsàré tí a ń lò fún Ṣàngó-pípè, Ọya-pípè, ẹkún-ìyàwó láàrin àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́ tàbí ègè àti àrùngbè láàrin àwọn Ẹ̀gbá. Àwọn Ìjẹ̀ṣà ló ni olele, bẹ́ẹ̀ ni àwọn Èkìtì ló ni alámọ̀, àsàmọ̀, orin obitun àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

### 4.2 Iṣẹ́ Ìṣègùn:

Lára àwọn iṣẹ́ ìṣèǹbáyé pàtàkì àwọn Yorùbá láyé àtijọ́ ni iṣẹ́ ìṣègùn wà. Iṣẹ́ yìí ṣe pàtàkì nítorí pé àwọn oníṣègùn yìí ló máa ń tọ́jú àwọn aláìlera àwùjọ wọn. Lára àwọn iṣẹ́ ìwòsàn tí wọ́n máa ń ṣe ni ìtọ́jú àwọn aboyún, àwọn tí ń wojú Ọlọ́run fún ọmọbíbí, ẹni tí ejò tàbí àkeekè bù jẹ, ẹni tí ó jábọ́ lórí ọ̀pẹ tàbí igi tí ó sì fi ara pa, tàbí rún léegun. Bí a bá mú ìṣepàtàkì iṣẹ́ àgbẹ̀ tán, iṣẹ́ ìṣègùn ní a lè sọ pé ó tún tèlé e. ìdí ni pé àwọn Yorùbá gbà pé 'ìlera ni oògùn ọrọ̀' àti pé 'ẹni tó ní àlàáfíà, ohun gbogbo ló ní'.
Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàlàyé lókè yìí, iṣẹ́ ìṣègùn ni ó tún sìkejì nínú iṣẹ́ ìṣèǹbáyé Yorùbá. Kí á má parọ́, iṣẹ́ yìí gbajúmọ̀ bí ìsáná ẹlẹ́ẹta láàrin àwùjọ Yorùbá; kódà, àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá náà ń fagagbága pẹ̀lú àwọn oníṣègùn Òyìnbó òde òní ni. Gẹ́gẹ́ bí a ti máa ń gbọ, ìmọ̀ tí ó gùn, tí kò lópìn ni a ń pè ní oògùn.
Oríṣìí ìlànà márùn-ún ni ó wà tí a ń gbà tọ́jú àìsàn. Bí àpẹẹrẹ, ọfọ̀ tàbí àyájọ́ pípè, àgbo wíwẹ̀ tàbí mímu, àgúmu jíjẹ, gbẹ́rẹ́ sísín àti ẹ̀pa títọ́lá tàbí fífi para, kò sì sí irúfẹ́ àìsàn tí àwọn ìlànà wọ̀nytí kò kápá nítorí pé, 'tí oògùn kò bá jé, ewé rẹ̀ ló kù ọ̀kan.

Ní àkọ́tán, a le pín àwọn àìsàn tí ó máa ń yọ ènìyàn lẹ́nu sí ìsọ̀rí méjì – èyí ni àwọn àìsàn tí ó jẹ mọ́ inú ara. Bí àpẹẹrẹ, àtọ̀sí àti ikọ́ èyí tí a lè fi àtọ́lá wò sàn pátápátá. Èkejì ni àwọn àìsàn tí ó jẹ mọ́ inú ẹ̀jẹ̀ bí ibà, nárun, oró ejò, oró àkeekèé, oró agbọ́n àti ìpá, èyí tí a lè fi agúnmu jíjẹ, àtọ́lá, ìpara, gbẹ́rẹ́ sísín, àgbo wíwẹ̀ àti mímú ṣe ìwòsàn rẹ̀.
Àwọn oníṣègùn tún máa ń tọ́jú obìnrin kí ó lè rí oyún ni, kí oyún lè dúró lára obìnrin tàbí tí èkejì ọmọ (obì) kò bá tètè bọ́ sílẹ̀. Wọ́n máa ń tọ́jú ọmọdé tí ó bá ní gìrì, jẹ̀díjẹ̀dí, joríjorí, ilẹ̀ tútù, eyín híhù àti ọ̀kà orí ọmọdé.
Ṣùgbọ́n sá o, oògùn ìbílẹ̀ ń bá oògùn Òyìnbó fi orí gbárí ní àwùjọ wa ni títí di òní olónìí.

## 4.3 Iṣẹ́ Arọ́

Gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé Akínyẹmí ti sọ, 'iṣẹ́ arọ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú iṣe àárọ̀ àwọn Yorùbá" (Akínyẹmí, 1989). Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣaájú, iṣẹ́ arọ́ náà ni a máa ń tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí àgbẹ̀dẹ ṣùgbọ́n àgbẹ̀dẹ Ògùn yàtọ̀ díẹ̀ sí àgbẹ̀dẹ bàbà.
Àwọn alágbẹ̀dẹ bàbà ni àwọn tó ń rọ ohun ọ̀ṣọ́ tí àwọn obìnrin máa ń lò sí ọwọ́, ọrùn àti etí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn kan sọ pé láti ọ̀dọ̀ àwọn Òyìnbó ni a ti gba nǹkan yìí, àwọn mìíràn sọ pé ara iṣẹ́ ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá ni nítorí pé ìtàn ìgbà ìwáṣẹ̀ kan sọ fún wa pé Òrìṣà-ńlá ni ó kọ́kọ́ ní àdá bàbà tí kò wúlò fún ọ̀nà yíyẹ̀ nígbà tí àwọn irúnmọlẹ̀ rọ̀ sí òde ayé, tí wọ̀n sì ń lọ sí Ifẹ̀-Oòdáyé. Nígbà tí àdá Òrìṣà yìí kò lágbára láti yẹ̀nà mọ́ nítorí títẹ̀ ni ó ń tẹ̀, ni Ògún fi adá irin rẹ yẹ ọ̀nà náà fún wọn. Ìdí nìyí tí Yorùbá ṣe máa ń sọ ọmọ ní Ògúnlànà.
Yàtọ̀ sí àgbẹ̀dẹ bàbà, a tún máa ń rí àgbẹ̀dẹ ọlọ́kọ̀. Àwọn àgbẹ̀dẹ ọlọ́kọ̀ yìí náà ló ń rọ ààké, ògigi, àdá, ọ̀bẹ, sẹ́kẹ́sẹkẹ̀, dòjé, idà, abẹ́rẹ́, kọ́só ẹṣin, agogo, ẹ̀mú, tàkúté àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4,4 Iṣẹ́ Ìkòkò Mímọ:

Kí àwọn Òyìnbó tó kó abọ́ ìdáná onírin dé ilẹ̀ Yorùbá, ìkòkò ni àwọn Yorùbá fi máa ń dáná oúnjẹ wọn. Níbikan tí wọn ń pè ní Ẹbu ni wọ́n ti máa ń yọ ìkòkò wọ̀nyí. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń pe ibẹ̀ ni Ẹbu-Ìkòkò.
Ní àkókò yìí, kò sí ìgò tàbí rọ́bà bí kò ṣe ṣágo tí a fi ń rọ ẹmu, sẹ̀kẹ̀té, ọtíkà àti bùrùkùtù. Yàtọ́ sí akèrèǹgbè (agbè) tí a fi máa ń rọ omi, kete tàbí ládugbó ni Yorùbá máa ń lò láti pọn omi lódò. Nísinsinyí, gbogbo àwọn nǹkan àtijọ́ tí a máa ń pèsè fún lílò ní ẹbu ìkòkò ni àwọn nǹkan ìgbàlódé ti rọ́pò. Ṣùgbọ́n a tún máa ń rí àwọn ènìyàn kan ti wọ́n máa ń lo àmù láti rọ omi mímu wọn sí, nítorí wọ́n gbàgbọ́ pé bí iná ọba ìgbàlódé kò bá sí omi àmù yìí máa ń tutù yàtọ̀.
Nítorí ìgbàgbọ́ àwọn amọ̀kòkò yìí pé Mọ́remí, tí í ṣe ọmọ Olókun ni ó kọ́kọ́ yọ ìkòkò, ọdọọdún ni àwọn amọ̀kòkò máa ń ṣe ọdún Edì àti ọdún Mọ́remí pàápàá ni Ilé-Ifẹ̀ àti Ẹdún-àbọ̀n.
Àwọn ènìyàn péréte ni ó kù sí ìdí ìkòkò mímọ lónìí. Wàyí o, bí a bá wo òrìṣà tí iṣẹ́ náà jẹ mọ́, a ní láti mọ̀ pé iṣẹ́ obìnrin ni.

## 4,5 Iṣẹ́ Ọsẹ Dúdú

Iṣẹ́ ọsẹ dúdú jẹ́ ọ̀kan nínú iṣẹ́ àwọn obìnrin láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Níbi tí kò bá ti sí èròjà iṣẹ́ yìí ni àwọn obìnrin ibẹ̀ kò ti máa ń ṣe iṣẹ́ náà. Iṣẹ́ tí ó gba sùúrù ni iṣẹ́ ọsẹ dúdú nítorí pé ààtò iṣẹ́ náà ti pọ̀ jù, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ tí ó rọrùn láti dá sílẹ̀ ni.

Láyé àtijọ́, ọsẹ dúdú ni àwọn Yorùbá fi máa ń wẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àdí ni wọ́n fi máa ń para bí wọ́n bá wẹ̀ tán. Ọsẹ yìí kan náà ni wọ́n fi máa ń fọ aṣọ àti àwo oúnjẹ wọn.
Gẹ́gẹ́ bí ìkòkò amọ̀ tí a mẹ́nubà lókè, Ẹbu Ọṣe ni wọ́n ti máa ń dána ọṣẹ wọn. A sọ fún wa pé iṣẹ́ yìí kò jẹ mọ́ ẹbí kan, ẹnikẹ́ni ni ó le kọ́ṣẹ́ ọsẹ ṣíṣe yìí, pàápàá àwọn obìnrin tí wọ́n bá tẹ̀lé ọkọ wọn lọ mú Igbógàn.
Nípa ti àdí, àwọn ọlọ́sẹ yìí náà ló máa ń pèsè àdí àyan tí àwọn ènìyàn wọn fi máa ń para. Èyí ni pé kí ó tó di pé àwọn Òyìnbó kó ọsẹ tiwọn wọ̀lú, ọsẹ dúdú ni Yorùbá máa ń lò, èyí tí wọ́n ń pè ní ọsẹ àwẹ̀dá.
Àwọn nǹkan èlò fún ọsẹ dúdú ni òkú ọ̀pẹ tí ó ti gbẹ, igi àràbà tí ó ti kú, èèpo kòkó, ṣoso ẹyìn àti pa-nsẹkẹ ni wọ́n máa ń sun nínú iná tí yóò sì di eérú. Òrìṣà tí àwọn ọlọ́sẹ dúdú yìí máa ń bọ ni wọ́n ń pè ní Ìyámọ̀pó, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń bọ òrìṣà yìí ni àwọn ìlú ti wọ́n gbé ń ṣe ọsẹ dúdú bíi Aáwẹ́, Ìlọràá, Orígbó, Ifẹ̀-Ọ̀dàn àti Modákẹ́kẹ́.
Gẹ́gẹ́ bí òǹkọ̀wé Fágbọrún (1989:286) ṣe sọ "bí ìgbà tí ènìyàn bá ń gbá epo nínú ni wọ́n ṣe ń gbà àdí. Bí o ba ti gboná níwọ̀ntunwọ̀nsì ni wọn yóò da ẹyin aró sí i" Ọsẹ dúdú wúlò púpọ̀. Ó wúlò fún àwọn oògùn kan nítorí pé àwọn oníṣègùn máa ń lò ó láti gúnsẹ fún oníbààrà wọn. Èyí lè jẹ́ ọsẹ kòkòrò bí èélá, nárun tàbí ìgbóná ọmọdé. Wọ́n sì máa ń lo ògidi ọsẹ láti ṣòògùn àwúre.
Wàyí o, lílo ọsẹ dúdú sì tún ń wáyé lóde òní. Àwọn ènìyàn kan wà tí wọn máa ń lo ọṣẹ dúdú láti wẹ̀ lẹ́yìn tí wọ́n bá ti po àwọn èròjà mìíràn tí ó le mú ara jọ̀lọ̀ mọ́ ọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Iṣẹ́ ohùn pípè ń fi ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye Yorùbá hàn àti pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọgbọ́n àti ìmọ̀ yìí ni wọ́n ṣúyọ nínú ìrírí àyíká ẹni nípa ìhùwàsí àti àbùdá gbogbo ẹ̀dá, ìbáà ṣe ènìyàn, ẹranko tàbí igi.
Bákan náà, iṣẹ́ ìṣègùn ni a fi sìkejì iṣẹ́ mìíràn tí ó ṣe pàtàkì jù lọ lẹ́yìn iṣẹ́ àgbẹ̀. Iṣẹ́ ìṣègùn yìí ni ó jẹ́ mọ́ ìwòsàn ara àti ẹ̀mí èyí tí ó ń ta kàn-ǹgbọ̀n pẹ̀lú ìṣègùn àwọn Òyìnbó lónìí.
A kò sàì mẹ́nuba iṣẹ́ arọ́, a sì ṣe àlàyé ní sókí ìwúlò àwọn alágbẹ̀dẹ bàbà àti àwọn yòókù látijọ́ àti lóde òní.
Ní ìparí, a ṣe àlàyé lórí iṣẹ́ ìkòkò mímọ àti iṣẹ́ ọsẹ dúdú, tí a sì rí ipò tí wọ́n wà lóde òní.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe:

1. Sọ pàtàkì iṣẹ́ Ohùn Pípè ni àwùjọ Yorùbá
2. Ǹjẹ́ o rò pé iṣẹ́ ìkòkò mímọ àti iṣẹ́ Ọsẹ Dúdú ń gbilẹ̀ sí i lóde òní mọ́?
3. Kín ni èrò rẹ nípa òrìṣà tí àwọn ọlọ́sẹ dúdú máa ń bọ?

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí:

Ilésanmí, T.M. ed 1989. *Iṣẹ́ ìṣèǹbáyé Yorùbá,* Ile-Ifẹ, OAU Press.
Daramọla, O. & 1968. *Àwọn Aṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ibadan, Onibon-Oje Press & Book Industries (Nig) Ltd.
Ojo, J.A. 1966. *Yorùbá Culture.* London, Univesity Presss.

Ologundudu, D. 2008. *The Cradle of Yorùbá Culture.* U.S. Center for Spoken Words, Institute of
Yorùbá Culture.

Laver, H. 2003. *Tradition Versus Modernity: Re-appraising A False Dichotomy,* Ibadan, Hope
Publications Ltd.

Akinyemi, T. 1989 "Iṣẹ́ Arọ̀" in Ilesanmi, T.M. ed *Iṣẹ́ Ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá,* Ilé-Ifẹ̀, O.A.U Press.

Fágbọrún, G. 1989 "Iṣẹ́ Ìkòkò" in Ilesanmi, T.M. ed. Iṣẹ́ *Ìṣẹ̀ǹbáyé Yorùbá,* Ile-Ifẹ̀, O.A.U. Press.

**MÓDÙ KẸTA**

**ÌPÍN KẸRIN: ÌLÙ, ORIN ÀTI IJÓ LÁÀRIN ÀWỌN YORÙBÁ**

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ìwúlò Ìlù àti Orin
4.2 Agbe ṣíṣe ní Ìdílé Aláyàn
4.3 Àwọn Ìlù tí a ń Lù
4.4 Ohun tí a n fi Ìlù Wí
4.5 Ibi tí Àwọn Ìlù wọ̀nyí Ti Wá
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ìlù orin àti ijó ṣe pàtàkì láwùjọ Yorùbá. Oríṣìíríṣìí ìlù ni ó wà. Bí ìlù ayẹyẹ ṣe wà, bẹ́ẹ̀ ni ìlù òrìṣà wà pẹ̀lú. Àwọn agogo wà tí a máa ń lù láti mú kí ìlù àti orin kolẹ̀, kí ó sì lárinrin.
Orin náà jẹ́ alábàárìnpọ̀ ìlù. Bí a bá ń lu ìlù ní àwùjọ Yorùbá, ó sábà máa ń dá lórí nǹkan ayọ̀ àti ìdùnnú, bẹ́ẹ̀ ni a le kọrin tí yóò mú orí àwọn ènìyàn wú, tí wọ́n sì le máa ta onílù náà lọ́rẹ nítorí inú ẹni kì í dùn kí á pa á mọ́ra.
Nínú ìpín yìí, a wo ìwúlò ìlù àti orin ní àwùjọ Yorùbá, a sì tọ́ka sí ìlù lílù gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ìdílé.
Ní ìtẹ̀síwájú, a mẹ́nuba irú àwọn ìlù tí a ń lù ní ilẹ̀ Yorùbá, pàtàkì wọn àti ibi ti ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìlù wọ̀nyí ti wá sí ilẹ̀ Yorùbá tàbí ibi tí a ti ṣe wọn

## 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánílẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó:

- Mọ ìwúlò ìlù láàrin àwùjọ Yorùbá
- Mọ àbùdá àwọn ìlú kọ̀ọ̀kan àti ibi ti wọ́n ti sẹ̀ wá
- Mọ orúkọ àwọn ìlú kọ̀ọ̀kan yìí àti àkokò tí wọ́n ń lù wọ́n.
- Mọ ohun tí àwọn Àyàngalú máa ń fi ìlù kọ̀ọ̀kan wí.
- Mọ àwọn èèwọ̀ tí ó so mọ́ àwọn ìlù kọ̀ọ̀kan

## 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Dárúkọ àwọn ìlù ìbílẹ̀ Yorùbá mẹ́ta kí o sì ṣe àwọn àkókò tí a ń lù wọ́n.
2. Kín ni o mọ̀ nípa ìdílé àyàn?
3. Dárúkọ àwọn gbajúmọ̀ onílù àti àtẹrun ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́.

## 3.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìwúlò Ìlù àti Orin:

Bí a bá wò ó dáadáa, a ó rí i pé ohun ìdárayá ni ìlù àti orin kíkọ jẹ́ jákèjádò gbogbo àgbáyé láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀. Èyí kò yọ àwùjọ Yorùbá sílẹ̀.
Láàrin àkójọpọ̀ ẹ̀yà Yorùbá kan, kò sí ibi tí kò sí ohun ìdárayá. Bí ó ti wulẹ̀ kí ó rí, wọ́n lè máa pàtẹ́wọ́ sí orin, kí wọ́n sì máa jo ijó ayọ̀. Nítorí náà, a lè sọ pé ìlù, orin àti ijó jẹ́ ọmọ ìyá mẹ́ta tí kò ṣe é yà sọ́tọ̀. Bí ìlù lílù bá ti bẹ̀rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni orin àti ijó yóò tẹ̀lé e. Nínú àwọn ìlù mìíràn, wọn lè má ní ìlù tí ó gbajú gbajà, ṣùgbọ́n wọ́n lè ní àwọn ìlù kéékèèké bíi igbá, agbè, agogo, ìgò àti kìtìpó.
Ìlù lílù kì í ṣe fún ayẹyẹ nìkan, àwọn Yorùbá máa ń lùlù láti bá ara wọn sọ̀rọ̀ pàápàá àwọn tí wọ́n bá mọ èdè àyàn. A tún máa ń lu ìlù ní àkókò ọdún òrìṣà nígbà tí àwọn onílù yìí yóò máa fi ìlù lílù máa ń wáyé ni àsìkò ogun, ìjàkadì tàbí ìkọlù. Èyí nìkan kọ́, ìlù lílù máa ń wáyé ní àkókò ọdún egúngún, tí àwọn onílù yóò sì máa lu dùndún láti sọ̀rọ̀, èyí tí ó lè dá rúgúdù sílẹ̀ láàrin àwọn ọmọlẹ́yìn egúngún kan àti èkejì.

### 4.2 Ìdílé Àyàn

Bí a bá ń sọ̀rọ̀ ìlù lílù, a kò gbọdọ̀ gbàgbé pé àwọn ìdílé kan wà tí wọ́n ń fi ìlù lílù ṣe iṣẹ́, bẹ́ẹ̀ ni Àyàngalú ni òrìṣà tó jẹ mọ́ wọn. Ìtàn àtẹnudétí kan sọ fún wa pé ènìyàn ni òrìṣà yìí nígbà ayé rẹ̀ àti pé Kúsanrín Àyàn ni orúkọ rẹ̀. Ilẹ̀ Ìbàrìbá ni ọkùnrin yìí ti wá, bẹ́ẹ̀ ni òun ni ó kọ́kọ́ lu ìlù ní ilẹ̀ Yorùbá. Nígbà tí Àyàn kú tán ni wọ́n sọ ọ́ di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òrìṣà yìí kò ní ibi kan tí wọ́n yà sọ́tọ̀ bí ojúbọ rẹ̀ bí àwọn òrìṣà yòókù.
Àwọn onílù máa ń bọ Àyángalú fún ààbò, wọ́n sì máa ń bèèrè ohun gbogbo tí wọ́n bá ti ń fẹ́ lọ́wọ́ rẹ̀, bí ọmọ, owó àti aásìkí. Ẹ̀kọ́ àti ohun mìíràn tí ẹnu ń jẹ ni wọ́n fi máa ń bọ ọ́, bẹ́ẹ̀ ni ìlù gúdúgúdú àti àwọn ọ̀pá ìlù tí a kó jọ sí apá kan inú ilé ni àmì òrìṣà yìí.
A máa ń sọ pé àwọn ìdílé àyàn máa ń ní àbùdá kan tí ó yàtọ̀ sí ti àwọn ìdílé yòókù ní ilẹ̀ Yorùbá. Èyí ni pé, bí wọ́n bá bímọ, wọ́n yóò tọrọ omi, ọṣẹ àti kàn-in-kàin-ìn tí wọ́n yóò fi wẹ̀ ẹ́ ni. wọ́n ń ṣe èyí kí ó le mọ agbe ṣíṣe lágbo eré. Lóde òní ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ni wọn yan iṣẹ́ ìlù lílù láàyò ṣùgbọ́n tí wọn kò wá láti ìdílé onílù.

### 4.3 Àwọn Ìlù tí À ń Lù:

(a) **Gbẹ̀dù**: èyí ni oríṣìí ìlù kan tí ó tóbi tí wọn máa ń lù fún Aláàfin Ọ̀yó. A kì í sábà lu ìlù yìí bí kò ṣe ní àkókò pàtàkì bí i ìgbà tí Aláàfin tuntun bá ń gorí ìtẹ́ tàbí ní àkókò tí Aláàfin bá wàjà.

(b) **Ìgbin**: Bákan náà ni ìlù Gbẹ̀du àti ìlù Ìgbìn rí. Ìyàtọ̀ wọn ni pé Ìgbìn kéré sí Gbẹ̀du, ṣùgbọ́n ìrísí wọn dọ́gba. Awọ tó nípọn ni a fi ń ṣe é, bẹ́ẹ̀ ni igi tàbí ọ̀pá ni a fi máa ń lù ú bíi Gbẹ̀du. Ìlù Ìgbín náà kì í ṣe ẹyọ kan. Oríṣìí mẹ́rin ni. Àwọn ni Ìyá-ńlá, Ìyá-gan, kẹ̀kẹ̀ àti Aféré.
Ìlù Ìgbìn yìí jẹ́ ìlù tí a máa ń lù nígbà tí a bá ń ṣe ọdún Orìṣà-ńlá tàbí Ọbàtálá, bẹ́ẹ̀ ni lára orúkọ àwọn olùsìn òrìṣà yìí ni Onígbìndé,

Bámiṣígbìn, Adéṣígbìn, Ìgbíntádé, Akínjógbìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Wọ́n sọ pé lára ohun tí wọ́n máa ń fi ìlù yìí sọ ni pé:

Ọbalúfọ́n gbobì jẹ,
Gbobì.
Òrìṣà gbobì jẹ,
Gbobì.

(d) **Ìpèsè**: ìlù yìí kò tóbi tó Ìgbìn ṣùgbọ́n wọ́n fi ara jọra, ó sì ṣe é gbé káàkiri. Ìlù yìí ní ojú kan, bẹ́ẹ̀ ni awọ tí a fi ṣe é nípọn dáadáa. Mẹ́rin ni ìlù Ìpèsè yìí – Ìpèsè, Àràn, Omele tàbí Aféré àti Agogo. Ìlù Ifá ni ìlù yìí bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń lù ú ní àsìkò ọdún Ifá.

(e) **Àgẹ̀rẹ̀**: Ìlù olójú kan ni Àgẹ̀rẹ̀ náà, bẹ́ẹ̀ ògún ni wọ́n máa ń lù ú fún ní àsìkò ọdún rẹ̀. Líle líle ni ìlù lílù, bẹ́ẹ̀ ni ijó rẹ̀ pẹ̀lú.

(ẹ) **Ìlù Dùndún**: Ìlù Dùndún yàtọ̀ sí àwọn ìlù mẹ́rin tí a ti mẹ́nubà. Igi ọmọ ni wọ́n fi máa ń gbẹ́ ẹ. Ìlù Dùndún ni wọ́n sábà máa ń lù níbi gbogbo ayẹyẹ tàbí àríyá ní ilẹ̀ Yorùbá.

(f) **Bàtá**: Ìlù Bàtá ni wọ́n máa ń lù fún Sàngó bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n ti ń lù ú níbi mìíràn tí kì í ṣe ọdún Sàngó lóde òní.

(g) **Ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ àti Aro**: Àwọn ìlú yìí ni wọ́n máa ń lù pẹ̀lú láti gbe ìlù dùndún lẹ́ṣẹ̀ kí ó le lárinrin.

(h) **Ìlù Bẹ̀mbẹ́**: Ìlù ogun ni ìlù yìí, bẹ́ẹ̀ ni àsìkò ogun ni wọ́n máa ń lù ú. Olójú méjì ni ìlù yìí gẹ́gẹ́ bí ìlù Dùndùn. Igi ọmọ náà ni wọ́n fi ń gbẹ́ ẹ.

(i) **Kósó**: Kóso fẹ́ ìlù olójú kan tí wọ́n máa ń lù fún Aláàfin Ọ̀yọ́ láyé àtijọ́.

## 4.4 Àwọn Ohun tí A máa Ń fi Ìlù Sọ:

Oríṣìíríṣìí àwọn ìpèdè ni a máa ń fi ìlù sọ pàápàá ìlù Dùndún tí o gbajú gbajà níbi àríyá. A le fi ìlù bú ènìyàn, wọ́n sì le fi ìlù yin ènìyàn. Ó dá lórí bí ẹni náà ṣe jẹ́ tàbí ìwà tí ó bá ń hù. Ṣùgbọ́n sá o, kò sí ẹni tí ó lè sọ pàtó nígbà mìíràn, ohun tí a ń fi ìlù sọ. Ìdí nìyí tí a fí máa ń gbọ́ pé, ‘kò sí ẹni mọ èdè àyàn bí kò ṣe ẹni tí ó mú ọ̀pá rẹ̀ lọ́wọ́’.

## 4.5 Ibi Tí Àwọn Ìlù ti Wá:

Nínú ìtàn àtẹnudétí ni a ti gbọ́ pé ó ni ibi tí ìlù kọ̀ọ̀kan ti wá sí ilẹ̀ Yorùbá. A jẹ́ kí á mọ̀ pé oríṣìíríṣìí agbègbè ní ilẹ̀ Yorùbá ni àwọn ìlù kọ̀ọ̀kan ti wá. Àwọn mìíràn bá òrìṣà Ọbàtálá wọlé. Eléyìí ni ìlù Ìgbìn, bẹ́ẹ̀ ni a sọ fún wa pé Ọ̀rúnmìlà ni ó mú ìlù ìpèsè, àràn, àgbà, agogo àti ọ̀pá wá bẹ́ẹ̀ ni Ṣàngó olúkòso ni ó mú ìlù bàtá wá sí Ọ̀yọ́ Ilé. Nípa báyìí, ìlù àwọn òrìṣà wọ̀nyí bá wọn sẹ̀ wá láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni.

## 5.0 Ìsọnísókí

Nínú ìpín yìí ni o ti kà nípa oríṣìíríṣìí àwọn ìlù tí a máa ń lù ní ilẹ̀ Yorùbá, ìrísí wọn àti ìwúlò ọ̀kọ̀ọ̀kan kan wọn. A rí i pé iṣẹ́ ìlù lílù jẹ́ iṣẹ́ àwọn ìdílé kan ní ilẹ̀ Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ni a mẹ́nuba onírúurú àwọn ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ ohun tí a máa ń fi ìlù sọ fún àwọn tí wọn bá gbọ́ èdè Àyàn, èyí ni àwọn tí ń lu ìlù náà. A jẹ́ kí ó ye akẹ́kọ̀ọ́ pé ìlù lílù, orin kíkọ àti ijó jíjo máa ń mú ènìyàn lárayá, ó sì máa ń sọ àwọn ìjìnlẹ̀

èdè, èyí tí ó ṣe é ṣe kí gbogbo ènìyàn tàbí àwọn tí kò bá mọ èdè Àyàn má lè túmọ̀ rẹ̀ bí ó ti ye.
A ti ṣe àlàyé, a sì ti dárúkọ àwọn ìlù kọ̀ọ̀kan tí a ń lù ní ilẹ̀ Yorùbá àti àkókò tí a ń lù wọ́n. A rí í bí ìlù lílù, orin kíkọ àti ijó jíjó kò ṣe ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn yíká gbogbo ilẹ̀ Yorùbá àti ní gbogbo àgbáyé lápapọ̀.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe:

1. Ṣàlàyé àwọn ohun tí a ń fi ìlù ṣe àti ìwúlò ìlù lílù, orin kíkọ àti ijó jíjó láàrin àwọn Yorùbá àti ní àgbáyé lápapọ̀.
2. Ṣàlàyé lẹ́kùn-rẹ́rẹ́ àwọn àléébù ìwà tí a fi máa ń wo àwọn Àyàn láyé àtijọ́, kí o sì sọ ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀.
3. Kọ àwọn ohun díẹ̀ tí a ń fi ìlù wí tàbí sọ láti ọwọ́ àwọn Àyàn

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Ládélé, T.A.A et. Al 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ibadan, Gavima Press Ltd.

Ọlajubu, O. 1975. *Ìwé àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ibadan, Longman.

Ologundúdú, D. 2008. *The Cradle of Yorùbá Culture.* U.S., Center for Spoken Words, Institute of Yorùbá Culture.

Biobaku, S.O. ed. 1973. *Sources of Yorùbá History.* Oxford, Oxford University Press.

Johnson, S. 1921. *History of the Yorùbás from the earliest times to the Beginning of the British Protectorate.* Lagos, C.M.S.

# MÓDÙ KẸTA

## ÌPÍN KARÙN-ÚN: ERÉ ÌDÁRAYÁ LÁÀRIN ÀWỌN YORÙBÁ LÁYÉ ÀTIJỌ́

### Àkóónú

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹbà
3.0 Ìbéèrè Ìsaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Ayò Ọlọ́pọ́n
4.2 Eré Àrín
4.3 Ẹkẹ tàbí Ìjàkadì
4.4 Eré Òkòtó
4.5 Eré Òṣùpá
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Eré ìdárayá ni àwọn eré tí Yorùbá máa ń ṣe ní ayé àtijọ́ nígbà tí ọwọ́ bá dilẹ̀. Nínú àwọn eré ìdárayá tí a mẹ́nubà níbí ni ó sábà jẹ mọ́ ọkùnrin nítorí pé àwọn obìnrin kì í sábà ní ààyè láti jókòó tẹtẹrẹ níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé àwọn ni yóò dáná oúnjẹ fún ìdílé wọn.

O ó ka àwọn eré ìdárayá bí ayò ọlọ́pọ́n, èyí tí ó gbajú gbajà jù lọ nínú àwọn eré ìdárayá àwọn ènìyàn yìí ní ayé àtijọ́ bẹ́ẹ̀ ni a kò sàì sọ̀rọ̀ lórí eré àrín àti eré ẹkẹ tí wọ́n tún gbájúmọ́ láàrin àwọn eré ìdárayá wọ̀nyí ní ayé àtijọ́. O ó tún kà nípa eré òkòtó títa, èyí tí a máa ń ta ní ojú-ọlọ́mọ-ò-tóo, èyí ni kọ̀rọ̀ níbi tí àwọn ọ̀ta ti le fi ìyà jẹ ara wọn láìbínú àti láìdìjà.

Ní ìparí ìpín yìí ni a ti sọ nípa eré òṣùpá, èyí tí àwọn ọmọdé sábà máa ń ṣe ní alẹ́, kí oúnjẹ alẹ́ tó délẹ̀. Àwọn eré wọ̀nyí kò fi bẹ́ẹ̀ wáyé mọ́ nítori ọ̀làjú ti gba gbogbo rẹ̀ lọ́wọ́ wọn. Nínú àwọn eré ìdárayá wọ̀nyí, eré ayò ọlọ́pọ́n nìkan ni kò tí ì wọlẹ̀ tán nítorí pé a rí àwọn àgbàlagbà tí wọ́n tún ń ta ayò ọlọ́pọ́n yìí lóde-òní.

### 2.0 Èròǹgbà/Àfojúsùn

Èròǹgbà wa nínú ìpín yìí ni kí o mọ̀:

- Nípa oríṣìíríṣìí eré ìdárayá tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe láyé àtijọ́
- Bí àwọn eré ìdárayá wọ̀nyí ṣe gbayì tó ní ayé ìgbàanì.
- Àǹfààní àti àléébù tí ó wà nínú ṣíṣe àwọn eré ìdárayá wọ̀nyí ní ayé àtijọ́ àti lóde òní.
- Pàtàkì ohun tí eré ìdárayá ń ṣe nínú ìlera àwọn ènìyàn títí di òní olónìí.
- Láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ ìyípadà tí ó dé bá àwọn eré ìdárayá wọ̀nyí ní òde-òní.

## 3.0 Ìbéèrè Ìsaájú

1. Ipa wo ni o rò pé eré ìdárayá ń kó ní àwùjọ wa lóde òní?
2. Ṣàpèjúwe ayò ọlọ́pọ́n Yorùbá àti ọ̀nà tí wọn ń gbà ta á.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 <u>Ayò Ọlọ́pọ́n</u>:

Ayò ọlọ́pọ́n títa jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn eré ìdárayá tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe láyé àtijọ́. Àwọn àgbàlagbà ọkùnrin ni wọ́n sábà máa ń ta ayò yìí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé nígbà mìíràn, a máa ń rí àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin náà nídìí ayò yìí.
Ayò ọlọ́pọ́n títa yìí máa ń mú ìrònújinlẹ̀ tí kò lẹ́gbẹ́ wá, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọlọgbọ́n ni ó tó gba-ngba sùn lọ́yẹ́ nídìí ayò ọlọ́pọ́n. Eré ayò ọlọ́pọ́n yìí jẹ mọ́ ìdíje láàrin ọ̀ta méjì. Ẹni tí ó bá ń gbégbá orókè ni a ń pè ní ọ̀ta bẹ́ẹ̀ ni ẹni tí kò bá rọ́wọ́ mú ni a ǹ pè ní òpè nídìí ayò ọlọ́pọ́n.
A máa ń ń fi igi gbẹ́ ọpọ́n ayò ni, bẹ́ẹ̀ ni ihò méjìlá ni ó máa ń wà nínú ọpọ́n yìí, èyí tí wọ́n máa ń pín sí méjì lọ́gbọọgba, tí ihò mẹ́fà yóò wà ní abala kan, bẹ́ẹ̀ ni mẹ́fà yóò wà ní abala kejì.
Ọmọ ayò mẹ́rin ló máa ń wà nínú ihò kọ̀ọ̀kan, èyí tí ó jásí pé ọmọ ayò méjìdínláàádọ́ta ni ó wà lójú ọpọ́n ayò kan. Ọmọ ayò yìí ni ó wá láti inú èso igi kan tí a sábà máa ń rí ní ẹ̀bá odò. Òfin wà nínú títa ayò ọlọ́pọ́n. Lára òfin yìí ni pé ọwọ́ ọ̀tún ni a gbọ́dọ̀ máa ta á sí, tí ọ̀ta yòó sì máa kó àwọn ọmọ ayò tí ó bá jẹ.
Àǹfààní pọ̀ nínú ayò ọlọ́pọ́n títa. Lára rẹ̀ ni ìdárayá, níbi tí a ó ti máa rẹ́rìn-ín, tí a ó máa na apá na ẹsẹ̀. Èyí nìkan kọ́ ayò ọlọ́pọ́n títa máa ń mú kí ọpọlọ ènìyàn jí pépé sí i,ó ń múni ronú kíákíá, ó sì máa ń mú ojú kí ríran sí pẹ̀lú. Àǹfààní mìíràn ni pé ayò ọlọ́pọ́n títa kì í jẹ́ kí ènìyàn máa yọjú sí ohun tí kò tọ́, bẹ́ẹ̀ ni kì í jẹ́ kí a rin ìrìnkurìn.
Wàyí ò, kò sí ohun tí ó le ní àǹfààní, kí ó máa ní àlèébù tirẹ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rọ̀ ẹ̀fẹ̀ tí kò bákùn gbé ló máa ń wáyé nídìí ayò ọlọ́pọ́n, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwàdà ni wọn yóò fi máa ṣe. Àléébù mìíràn ni pé ayò ọlọ́pọ́n sábà máa ń múni mọ́lẹ̀ de ebi ni. Bí ayò bá wọra tán, ènìyàn yóò gbàgbé pé ebi ń pa òun. Yàtọ̀ sí ebi, bí ọmọ ọ̀ta kan bá ń sàìsàn, ó le má tètè dìde nídìí ayò náà.

### 4.2 Eré Àrín:

Eré àrín náà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì ni ayé àtijọ́. Bí àwọn èniayàn bá fẹ́ ṣe eré àrín ní àtijọ́, wọn yóò wá èso ìtàkun kan tí a ń pè ní àrin nínú igbó.
Ọ̀nà méjì ni a ń gbà ṣe eré àrín. Lọ́nà kìnní, àwọn ọmọdé lè tẹ́ ẹni sínú ihò kékeré kan tí wọ́n bá wà. Gẹ́gẹ́ bí eré ayò ọlọ́pọ́n, a máa ń ta àrín nígbà tí ọwọ́ bá dilẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni a máa ń yan olórí láti wo àrín ẹni tí ó jẹ́. Dípò ènìyàn méjì tí ó máa ń ta ayò ọlọ́pọ́n, àwọn mẹ́ta ni ó máa ń ta àrín.
Ọ̀nà kejì tí a ń gbà ta àrín ni pé lẹ́yìn tí a bá tí kó àrín jọ, wọn yóò fa ìlà sílẹ̀, èyí tí yóò ní orígun mẹ́rin tí gígùn rẹ̀ lóòró yóò jẹ́ bíi ọ̀pá méjìlá àti ọ̀pá mẹ́sàn-án ní ìbú. Nígbà tí a bá ṣètò tí ó yẹ tán, àwọn olùta yóò bẹ̀rẹ̀ sí i dárayá nípa títa àrín yìí.

Abẹ́ igi tí ó ní ibòji ni wọ́n ti sábà máa ń ta ayò yìí tàbí kí wọ́n ta á ní abẹ́ ilé. Àwọn ènìyàn tí wọ́n máa ń wòran eré àrín máa ń pọ̀ ju àwọn tó máa ń wà níbi ayò ọlọ́pọ́n lọ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé bí wọ́n tí ń yọ sùtì ètè sí àwọn aláyò ọpọ́n bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń ṣe níbi ayò àrín.
Àwọn àǹfààní pọ̀ nínú ṣíṣe eré àrín bẹ́ẹ̀ ni lára irú àǹfààní wọ̀nyí ni dídá ara ẹni lára yá nítorí àti àwọn olùta àti àwọn òǹwòran ni ara wọ́n máa ń yá gágá. Yàtọ̀ sí èyí, a máa ń pa ara wa lẹ́rìn-ín nínú eré àrín títa, èyí sì máa ń mú kí ìlera jí pépé sí i. Èyí nìkan kọ́, eré náà máa ń kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ bí a ti máa ń fi ojjú sun nǹkan lókèèrè, ó sì tún máa ń fún ojú ní agbára láti mọ́lẹ̀ kedere sí i. Yàtọ̀ pé eré àrín ṣíṣe máa ń mú àwọn olùta àti àwọn o òǹwòran gbàgbé àwọn èrò búburú tí wọ́n ní, ó tún máa ń mú kí àwọn ènìyn fi ojú kan ara wọn láti ṣẹ̀fẹ̀ tàbí kí wọ́n tilẹ̀ bá ara wọn dọ́rẹ̀ẹ́.

## 4.3 Ẹkẹ tàbí Ìjàkadì

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ ìjàkadì tí ó máa ń sábà wáyé nípaṣẹ̀ aáwọ̀ tàbí èdè-àiyedè wà, eré ẹkẹ yàtọ̀ sí èyí nítorí pé eré lásán tàbí ìdíje ni eléyìí jẹ́. Bí olùkópa kan bá ṣèse nínú eré yìí, kò sí pé ó ń bínú sí ẹnìkejì rẹ̀ nítorí ìdíje láti mọ ẹni tí ó lágbára jù ni a mọ̀ ọ́n sí. Láàrin àwọn Òyìnbó lóde òní, wọ́n máa ń fi ẹkẹ (wrestling) dìje láàrin ara wọn ni, bẹ́ẹ̀ ni ẹni tí ó bá gbégbá orókè yóò gba ẹ̀bùn lọ́pọ̀lọpọ̀.
Oríṣìíríṣìí orin ni wọ́n máa ń fi dá kí àwọn tí ó ń kópa nínú ẹkẹ le ní okun àti agbára. Bí àpẹẹẹ, àwọn òǹwòran lè máa kọrin pé:
Akítì ló le jà,
Ìjà ló le jà.
Ó gbé pára, ó fi tá
Ìja ló le jà.
Ó ró kìì bí ìbọn
Ìjà ló le ja…
Irúfẹ́ orin báyìí máa ń mú ìwúrí bá àwọn tí wọ́n ń kópa nínú ẹkẹ jíjà yìí, wọ́n sì máa ń lókun sí i láti jà ìjàkadì náà.
Ní àkókò ọdún Ògún nígbà tí kì í sábà sí iṣẹ́ púpọ̀ ni ẹkẹ jíjà sábà máa ń wáyé, bẹ́ẹ̀ ni orí iyanrin tí kò ti le sí ìpalára púpọ̀ ni a ti sábà máa ń jà ẹkẹ tàbí ìjàkadì. Níbi tí wọn ti máa ń ja ìjàkadì yìí, wọ́n ti máa ń sa òkúta àti àwọn nǹkan tí ó bá le panilára kúrò kí ẹkẹ tó bẹ̀rẹ̀.
Bí àwọn ènìyàn méjì tí wọn ń díje ìjàkadì náà bá jọ subú pọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà, wọ́n máa ń sọ pé wọ́n jà ọgba ni, èyí ni pé ẹnìkan kò ṣe ju ẹnìkejì lọ.
Àǹfààní tí a máa ń rí nínú eré ẹkẹ tàbí ìjàkadì ni pé àwọn ọ̀rẹ́ àti ojúlùmọ̀ máa ń pàdé, bẹ́ẹ̀ ni nínú ìpàdé yìí ni àwọn mìíràn ti máa ń fẹ́ ìyàwó tàbí ní ọkọ. Ẹni tí ó bá tilẹ̀ gborí nínú ìdíje yìí ni àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin àti wúndíá máa ń fẹ́ràn jù, tí wọn yóò sì fẹ́ lát fi ṣe ọkọ. Ẹkẹ tàbí ìjàkadì máa ń kọ́ àwọn ọ̀dọ́ tàbí géńdé ọkùnrin ní ìlò agbára, wọ́n sì tún máa ń ní ìgboyà sí i. Wàyí o, bí eré ẹkẹ yìí ṣe ní àǹfààní ni ó ní àléébù tirẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, ọ̀pọ̀ olùdíje ni wọ́n máa ń fi ara bó fẹ́lẹ́fẹ̀lẹ. Olùdíje lè kán lápá, kí ó kán lẹ́sẹ̀ tàbí kí ó fọ́ lójú bẹ́ẹ̀ ni bí ìdí bá bàjẹ́, ti onídìí ni yóò dà. Kò sí à-ńpeni-lẹ́jọ́ tàbí a-ngbẹ̀san nínú ìdíje yìí.

## 4.4 Eré Òkòtó Títa:

Òkòtó títa náà jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú eré ìdárayá láwùjọ àwọn Yorùbá láyé àtijọ́. Eré òkòtó yìí wọ́pọ̀ láàrin àwọn ọ̀dọ́mọdé ní àwùjọ, kì í ṣe eré àwọn àgbàlagbà rárá.
Kòròfo ìgbín kékeré tí a mọ̀ sí èèsàn tàbí ìpére ni wọ́n fi máa ń ta òkòtó. Lẹ́yìn ìgbà tí a bá ti mú ẹran inú èèsàn tàbí ìpére yìí kúrò, a ó gún etí tàbí ẹnu rẹ̀ régérégé, àwọn olùdíje yóò sì máa fi ọwọ́ ta á, tí yóò sì máa jó ran-inran-in nínú ebútú tàbí yẹ̀ẹ̀pẹ̀ tàbí yanrìn búlẹ́búlẹ́ báyìí. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń kọrin pé,
Òkòtó,
Ọmọ afidí jó ran-in-ran-in,
Òkòtó,
Ọmọ afìdí jó ran-in-ran-in.
Àwọn òǹwòran eré òkòtó kì í pọ̀ tó ti eré àrín tàbí ti eré ẹkẹ rárá. Wọn yóò máa ta òkòtó yìí kí wọ́n sì máa dé e, èyí ni pé kí ojú rẹ̀ dà bolẹ̀. Olùdíje tí òkòtó tí ó ta kò bá dojú délẹ̀, ẹni tí wọ́n jọ ń díje yìí yóò sọ pé kí ó tẹ́ ẹ̀yìn ọwọ́ rẹ̀ sílẹ̀, yóò sì gán onítọ̀ún ní ẹ̀yìn ọwọ́ fún iye ìgbà tí wọ́n bá ṣe àdéhùn rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n tún le bẹ̀rẹ̀ òkòtó títa mìíràn lẹ́yìn èyí.

## 4.5 Eré Òṣùpá:

Eré òṣùpá jẹ́ eré tí àwọn ọmọdé máa ń fi alẹ́ ṣe pàápàá kí oúnjẹ alẹ́ tó délẹ̀. Eré òṣùpá yìí gbilẹ̀ púpọ̀ ní ayé àtijọ́ ṣùgbọ́n lóde òní, bí ó bá tilẹ̀ wà ní apá ibòmíràn, kò wọ́pọ̀ láàrin àwùjọ Yorùbá mọ́ nítorí pé ọ̀làjú ti gbá ẹ̀ka eré ìdárayá yìí nílẹ̀. Lára àwọn eré ìdárayá bẹ́ẹ̀ ni;

(a) Bọ́ọ̀kọ-bọ́ọ̀kọ
(b) Bojúbojú
(d) kín ní ń hewú
(e) Gbádìí-gbádìí

Gẹ́gẹ́ bí orúkọ tí a fún àwọn eré yìí (eré òṣùpá), àkókò tí òṣùpá bá ń ràn ni àwọn ọmọdé wọ̀nyí sábà máa ń bọ́ síta gbangba láti ṣe eré òṣùpá bọ́ọ̀kọ-bọ́ọ̀kọ, àwọn ọmọdé bíi mẹ́fà sí méjọ tàbí jù bẹ́ẹ̀ ni yóò jókòó sí ìta gbangba tí ọ̀kan nínú wọn yóò mú òkúta kékeré kan lọ́wọ́, yóò máa fi ọwọ́ rẹ̀ bọ ọwọ́ àwọn yòókù lọ́kọ̀ọ̀kan, tí yóò máa wí pé 'bọ́ọ̀kọ-bọ́ọ̀kọ' tí àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ yóò máa dáhùn pé 'àlùbọ́ọ̀kọ'. Ẹni tí ó mú òkúta lọ́wọ́ yẹn yóò máa kọrin síwájú sí pé, 'bọ́kọkọ rẹ' tí àwọn yòókù yóò máa gbè é pé 'àlùbọ́ọ̀kọ' yóò sì máa bọ̀ wọ́n lọ́wọ́ títí yóò fi sí ọwọ́ ọ̀kan nínú wọn. Ẹni tí ó bá fi sí ọwọ́ rẹ̀ yìí ni yóò si gba ipò rẹ̀. Báyìí ni wọn yóò ṣe títí wọn yóò fi parí eré náà.
Ní ti eré òṣùpá 'Bojúbojú', àwọn ọmọdé bíi méjọ, mẹ́wàá tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ lè ṣe eré yìí. Bí wọ́n bá fẹ́ ṣe eré yìí, wọn yóò mú ẹnìkan tí wọn yóò fi aṣọ dì lójú, àwọn yòókù yóò lọ fi ara pamọ́ bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ sí ibi kan. Lẹ́yìn náà ni ẹni tí a di lójú yóò máa sọ pé, 'Bojú bojú o' ti àwọn tó sapamọ́ yóò máa dáhùn pé, Òo'. Ẹni tí wọ́n dì lójú yóò bèèrè pé 'ṣé kí n sí i?' bẹ̀ẹ̀ ni àwọn tí wọ́n fara pamọ́ náà yóò sọ pé, 'si i', bẹ̀ẹ̀ ni ẹni náà yóò sí aṣọ ojú rẹ̀, yóò sì máa wá àwọn tí ó sápamọ́ kiri. Bí ó bá ti rí ọ̀kan nínú wọn ni yóò dì í mú tí yóò sì sọ pé 'mo rí ọ'. Eléyìí ni yóò gba ipò rẹ̀ títí eré náà yóò fi parí.
Àwọn eré òṣùpá yìí máa ń mú kí àwọn ọmọdé ṣeré papọ̀, kí wọ́n làágùn, kí ara wọn sì túbọ̀ le sí i, bẹ́ẹ̀ ni àwọn eré òṣùpá yìí máa ń mú ọmọdé lágbára sí i. Wàyí

o, àléébù eré òṣùpá ni pé wọ́n máa ń mú kí àwọn ọmọdé fi ara pa, bí wọ́n bá subú tàbí fi ẹsẹ̀ gbún òkúta.

## 5.0 Ìsọníṣókí

O ti kà ní ìpín yìí pé eré ìdárayá ṣe pàtàkì nínú ìlera àlàáfíà ẹ̀dá gbogbo. Eré ìdárayá yìí kì í ṣe ohun tí àwọn baba-ńlá wa kò mọ̀ nípa rẹ̀ tàbí mọ pàtàkì rẹ̀ tẹ́lẹ̀ nítorí onírúurú eré ìdárayá ni wọ́n máa ń ṣe. Lára àwọn eré ìdárayá ni ayò ọlọ́pọ́n títa, àrín títa, mímu ẹkẹ, títa òkòtó láàrin àwọn ọ̀dọ́mọdé àti àwọn onírúurú eré òṣùpá mìíràn tí àwọn ọmọdé máa ń ṣe ní ayé àtijọ́.
Àwọn eré ìdárayá wọ̀nyí kò wọ́pọ̀ lóde mọ́ nítorí ọ̀làjú òde-òní ti mú kí á pa àwọn kan tí, bí ó tilẹ̀ ṣe pé àwọn kan wà tí ó sì gbajúmọ̀ títí di òní-olónìí.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé ipò tí ọ̀làjú mú bá àwọn eré ìdárayá ìbílẹ̀ Yorùbá àti pé àtúnṣe wo lo rò pé ó yẹ?
2. Sọ ohun tí ó bá mọ̀ nípa eré ayò ọlọ́pọ́n àti eré ẹkẹ ní àwùjọ wa lánà, lónìí àti lọ́jọ́ iwájú.
3. Ṣe àlàyé àléébù tí ó wà nínú àwọn eré ìdárayá wa ní àtijọ́ àti lóde òní. Kín ni o rò pé a le ṣe láti kápá àwọn àléébù bẹ́ẹ̀?

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí

Ẹkúndayọ̀ àti Kọ́mọláfẹ́, 1975. “Eré Ṣíṣe ní Ilẹ̀ Yorùbá” in Olájubù, O, ed. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn. Longman.
Daramọla, O & Jẹjẹ, A. 1968. *Àwọn Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá,* Ìbàdàn, Oníbọn-Oje Press & Book Industries (Nig.) Ltd.
Adeoye, C.L. 19 *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ibadan, Oxford University Press (Nig.) Ltd.
Ọlajubu, O. 1976. *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ibadan, Longman.